1. Ifá ní éni ti ó dá Ogbè wúnlé ki ó rú'bọ ki àrun ki ó bá
Ma á ṣe áwọn ọmọ rè. Ifa pé ki eléyiun ó má ṣe àigbóràn. Ifá pé ẹbọ ni kó'rú

Ìté gùdùgbè
Ló d'Ífá fún Elédìró

Elédìró tí Ifá ńsọ yìí, adiyẹ ni. Ni ayé àtijó, àrun orí ńṣe àwọn ọmọ rè, ni ó bá lọ bèrè l'ódó Ifá. Àwọn Awo ní kí ó rú'bọ, wọn yàn án l'ẹbọ. Ṣùgbòn ó fi gbigbó ṣe aláigbó, kó rú'bọ. Ni àrun àwọn ọmọ rè bá tún pò si. Báyíí ni àrun orí yíí ṣe ńpa àwọn ọmọ ré. ṣúgbón ki ó tó di wipe wọn ó ma fi ọrún yi'lè, wọn ó ma sipé, iyá áwọn ni kò ṣ'ẹbọ. Òkóòkán méji kò ṣ'ẹbọ; éjèèje meje meje.

2. Ayegbe ihin
Ayegbe òhun
A d'Ifá fún érìnlójọ ẹranko
L'ọjó tí wón ńlọ rèé fé Mọlújanjan ọmọ ulúigbó
Ayegbe óhún
A d'Ifá fún oorẹ sẹgi-sẹgi
L'ọjọ tó ńlọ rèé fé Mọlújanjan ọmọ olùigbó

Mọlújanjan tí Ifá sọ yíí, ọmọ olúigbó níí ṣe. ó tó àkókò tí yí óó ni ọkọ, ní àwọn ẹranko bá bá njá l'òrí i rè. Èkíní wipe òun l'óun ó fẹ, ekeji náà wipe óun ni òun yó fe. Àwọn ẹranko bierín, efon, àgbònrin, oore. Ni olùigbó bá ni òun ó ṣe ìdànwò fún wọn. ẹní tí ọmọ óun bá dìmó, tó gba ọsán l'ọwọ rè ni yí óò fẹ. Nì àwọn ẹranko yoku bà lọ dá'fá. Wọn ni kí wọn ó rù'bọ. Oorẹ nikan ló rú'bọ. Àwọn ẹranko kó rú'bọ. Wòn ní bí ẹni gbogbo yi óò ma bá áwọn fi orí gbá'rí. Erin ni "Nibití mo wà" ẹfọn náá ní "nibiti mo wá, "ágbònrìn náà wí béè, Wọn l'áwọn ó rú'bọ. Ni oorẹ bá ra ọsán, ọsàn tí oorẹ rà ni àwọn Awo bá ṣe Ifá sí. Gbogbo ẹranko dá'jó, ojó pé. Gbogbo wón bá péjọ: ni wón bá ńkọrín. Erin ló kókó yọ 'jú, ó k'ọrin wipe.

Mọlújanjan wá gb'ọsán o, àlújanjan-kíjan (èèméjì
Èmi erin má de asalu (olórí igbó), àlùjanjan-kijan
ẹfọn l'ọmọ abila o, àlùjanjan-kijan
Oorẹ l'ẹrú àwa, àlújanjan-kíjan
Mọlújanjan wá gb'ọsán o, àlújanjan-kíjan

Mọlújanjan kò dahun, kó gba ọsàn l'ọwọ erin. Ni éfọn bà
Bó sibe, ni òun náá bá bèrè si ni k'ọrin.

Mọlújanjan wá gb'ọsán o, àlújanjan-kíjan (èèméjì)
erin ni olórí igbó, àlùjanjan-kijan
Èmí ẹfọn l'ọmọ òdòfin, àlùjanjan-kijan
Àgbònrín l'ọmọ abilá o, àlújanjan-kíjan
Oorẹ l'ẹrú àwa, àlújanjan-kíjan
Mọlújanjan wá gb'ọsán o, àlújanjan-kíjan

Mọlújanjan kò dahun, kó gba ọsàn l'ọwọ ẹfọn. Ni àgbònrín
Bó bọ sibe, ni òun náá bá bèrè si ni k'ọrin.

Mọlújanjan wá gb'ọsán o, àlújanjan-kíjan (èèméjì)
erin ni olórí igbó, àlùjanjan-kijan
ẹfọn l'ọmọ òdòfin, àlùjanjan-kijan
Èmi àgbònrín l'ọmọ abilá o, àlújanjan-kíjan
Oorẹ l'ẹrú àwa, àlújanjan-kíjan
Mọlújanjan wá gb'ọsán o, àlújanjan-kíjan

Mọlújanjan kò dahun, kó gba ọsàn l'ọwọ àgbònrín. Ni oorẹ
Bó bọ sibe, ni òun náá bá bèrè si ni k'ọrin.

Mọlújanjan wá gb'ọsán o, àlújanjan-kíjan (èèméjì)
erin ni olórí igbó, àlùjanjan-kijan
Èfọn l'ọmọ òdòfin, àlùjanjan-kijan
Àgbònrín l'ọmọ abilá o, àlújanjan-kíjan
Èmi oorẹ l'ẹrú àwa, àlújanjan-kíjan
Mọlújanjan wá gb'ọsán o, àlújanjan-kíjan

Ni Mọlújanjan bá sáré, ni ó wipe, "Ìyẹn ni wipe iwọ kíí ṣe ẹrù wonyi" oorẹ ni òun kìí ṣe ẹrú o wọn.

Bàyìí ni oorẹ fé Mọlújanjan ọmọ olúigbò nipa irúbọ Ifá àti iyè Ifá tí wón pè sí ọsán, ó jé kí ọsán tì oorẹ wọ Mọlújanjan l'ójú. Báyìí ni oorẹ fé Mọlújanjan mó áwọn ẹranko yọkù
l'ọwọ.

Àṣẹ: Ifá yìí kó wa pé kí a má ojú témbélú eni keji ì wa. Ifá pé ẹni ti ó dá Ogbè-wúnlé kí ó rú'bọ kí ó lé bá gbayì l'ọwọ àwọn iyókù rè.

3.
Egbirin l'awo aja ile
A d'Ifá fún yemòó
Ti i ṣe obinrin Òrìṣà
L'ójó tí ó ńsunkún pé óun kó bí'mọ

Yemòó tí Ifá ńsọ yìí, obinrin ni ní ayé àtijó. Óṣe titi kò rí ọmọ bi: ojú ọmọ pọn púpò. Ni ó bá mú ééjì kún ééta ó lọ si oko awo. Ifá pé kó rú'bọ. Yi óò bi'mọ púpò. Wón yán án l'ẹbọ. Yemóò rú'bọ. Olòdùmarè sì gbọ ohún un rẹ, ó sì fì ọmọ mérìndìnlógún rànṣé si láti òde òrun. Báyìí ni yemòó di ólómó. Ó sì nyin Awo, àwọn Awo nyin Ifá, Ifá sì nyin Olódùmarè.

**Àṣẹ:** Ifá pé ẹmi ti ó dá Ogbè-Wúnlé ki ó rú'bọ ọmọ lópólọpọ; kí ó sì má fi etí pálábá ẹbọ náá. Ifá pé òun pé ire ọmọ fún eléyiun.

4. Ifá pé ẹní ó dá Ogbè-Wúnlé ki ó rú'bọ, ki wón bá ma gba ọkọ mọ l'ówó, tàbi gba iyawo o rè. Ifà pé kì eléýíun kí ó ma déjáá.

Imú ilé là á hun
Kí a tó ma hun òde
A d'Ìfá fún porogodo
Tîì ṣe obinrin ákókó.

Porogodo tí Ifá sọ yìí, obinrin ákókó ní í ṣe, Ákókó fura wipe wón fé gba Ìyàwò òun ni ó bá lọ ṣe àyéwó.wọn ni ẹbọ ní kí àkókò ó rú. Ṣúgbón àkókò kò rú'bọ: ó ní kaka kí óun ó rú'bọ, ogbọn ni òun ó ta. Ni àkókò bá lọ fi ẹnu gbé íhò sí ara igi kan, ni ó bá lọ gbé iyawo rè pamo si inú ihò igi yìí, ni ó bá dí i pa. Ṣùgbón gégé bi àìgbónran átí ẹjá dida, àkókò padá dé ibi igi kò mọ ojú ibiti ó gbé ìyàwò rè sí mọ. Láti ákókó yìí ni ákókó tí ma á fi énu sọ igi káákiri ayé, ti ìdààmú sí ba, tí yí óó ma wípé "Pongodoro, pongodoro"

## Traducción:

1. Ifá recomienda ẹbọ para la buena salud de los niños de quien Ogbè òwónrín sale. Ifá advierte a la persona que no desestime los mandatos de Ifá. Ifá dice make ẹbọ

Ìté gùdùgbé
Divina para elédió (gallina)

Elédíó en referencia aquí era una gallina en los viejos días. Los pollos de gallina estaban enfermos de alguna neurosis, por lo tanto, la gallina consultó a Ifá para la cura. Gallina se le dijo que hiciera ẹbọ, pero no hizo el ẹbọ. Debido a la incapacidad de la gallina para hacer el ẹbọ, la neurosis de los pollitos empeoró, y comenzaron a morir, sin embargo, antes de que los pollitos murieran, se lamentaron diciendo que su madre se negó a hacer ẹbọ fue la causa de sus muertes.

2.
Ayegbe aquí
Ayegbe allí
Adivinado para un grupo de animales
Cuando querían casarse con Mọlújanjan, hija de Olúigbó
Ayegbe aquí
Ayegbe allí
Adivinado para oore (puercoespín)
Cuando iba a casarse con Mọlújanjan, hija de Olúigbo

**Ifá** está hablando de Mọlújanjan, hija de Olúígbó, todos los animales en el bosque Elefante, búfalo, ciervo, oore, y así sucesivamente, decidieron probar los animales. Para pasar la prueba, Mọlújanjan debe abrazar sólo uno de los animales, y cualquiera de ellos que abrace y acepte una naranja, será su marido elegido. Todos los animales fueron a la adivinación, pero sólo oorẹ realizó el ẹbọ prescrito por Ifá los animales subestimados en el concurso. El elefante dijo: "Conmigo por aquí ...", dijo el búfalo. "Conmigo alrededor ..." dijo ciervo, "conmigo alrededor, oorẹ no ganaría el amor de Mọlújanjan." Confiando en sus poderes, los animales se negaron a hacer el ẹbọ prescrito. oorẹ hizo el ẹbọ y compró una naranja. Oorẹ llevó la naranja a su Babalàwo para la bendición. El Babalàwo bendijo la naranja. En el día del concurso, todos los animales estaban allí, y comenzaron a cantar. Elefante fue el primero en cantar, diciendo:

Mọlújanjan acepta mi naranja, àlújanjan-kíjan
Yo, elefante, soy el rey del bosque, àlújanjan-kíjan
El búfalo es el hijo de Òdòfin, àlújanjan-kíjan
Ciervo es el hijo de abilá (ciervo es el que tiene marcas).
Àlújanjan-kíjan
Oorẹ es nuestro esclavo, àlújanjan-kíjan
Mọlújanjan acepta mi naranja, àlújanjan-kíjan

Mọlújanjan no respondió, y tampoco aceptó la naranja. Buffalo le dijo al elefante que lo excusara. Buffalo comenzó a cantar a Mọlújanjan, diciendo:

Mọlújanjan acepte mi naranja, àlújanjan-kíjan
Elefante, soy el rey del bosque, àlújanjan-kíjan
Yo, el búfalo hijo de Òdòfin, àlújanjan-kíjan
Ciervo es el hijo de abilá (ciervo es el que tiene marcas).
Àlújanjan-kíjan
Oorẹ es nuestro esclavo, àlújanjan-kíjan
Mọlújanjan aceptar mi naranja, àlújanjan-kíjan

Mọlújanjan no respondió, y tampoco aceptó la naranja. ciervo le dijo al bufalo que lo excusara. El comenzó a cantar a Mọlújanjan, diciendo:

Mọlújanjan aceptar mi naranja, àlújanjan-kíjan
Elefante, soy el rey del bosque, àlújanjan-kíjan
El búfalo es el hijo de Òdòfin, àlújanjan-kíjan
Yo, ciervo soy el hijo de abilá (venado es el que tiene marcas).
Àlújanjan-kíjan
Oorẹ es nuestro esclavo, àlújanjan-kíjan
Mọlújanjan aceptar mi naranja, àlújanjan-kíjan

Mọlújanjan no respondió, y no aceptó la naranja de venado. Todos los demás animales tomaron su turno, pero Mọlújanjan no aceptó naranja de ninguno de ellos. Entonces le tocó el turno, y él pidió ser excusado. Oorẹ también empezó a cantar a Mọlújanjan, diciendo

Mọlújanjan acepte mi naranja, àlújanjan-kíjan
Elefante, es el rey del bosque, àlújanjan-kíjan
El búfalo es el hijo de Òdòfin, àlújanjan-kíjan
Ciervo es el hijo de abilá (ciervo es el que tiene marcas).
Àlújanjan-kíjan
Yo, Oorẹ no soy su esclavo, àlújanjan-kíjan
Mọlújanjan acepte mi naranja, àlújanjan-kíjan

Para sorpresa de todo el mundo Mọlújanjan respondió, abrazó oorẹ y aceptó la naranja de él. Entonces ella preguntó, "¿así que no eres su esclavo?" Oorẹ respondió que él no era los animales "y por el trabajo especial de Ifá hecho en la naranja, oorẹ se le dio Mọlújanjan en matrimonio a la decepción de todos los demás animales.

**Àṣẹ:** Ifá nos enseña a no mirar hacia abajo a nadie o ser egocéntrico. Ifá dice que para quien sale Ogè òwónrín debe hacer ẹbọ para el éxito en una prueba por delante de él/ella.

3.
Egbinrin es el adivino para aja Ilẹ
Adivinado para Yemòó
Quien era / es la esposa de Òrìṣàs (Ọbátálá)
Cuando estaba llorando por falta de hijos

Yemòó en referencia aquí era sin hijos, y ella estaba desesperada por los niños. Para resolver el problema, se fue a la adivinación. El Babaláwo le dijo a Yemòó que hiciera ẹbọ asegurando
Ella que tendría muchos hijos después del ẹbọ. Le dieron a Yemòó la lista de cosas que necesitaba. Yemòó proveyó las cosas, y el ẹbọ fue hecho para ella. Olódùmarè (Dios) respondió a las oraciones de Yemòó y envió a sus 16 hijos; Por lo tanto, comenzó a alabar el Awo, el awo elogió a Ifá, mientras que Ifá elogió Olódùmarè.

**Àṣẹ:** Ifá dice que la persona por la que sale Ogbè Òwónrín tendrá muchos hijos, pero él / ella debe hacer ẹbọ. Ifá advierte a la persona que no desestime este consejo para ẹbọ.

4. Ifá dice que la persona que Ogbè Òwónrín sale debe hacer ẹbọ para que su esposo, o su esposa, no lo dejen por un rival. Ifá dice que la persona debe adherirse al consejo de este Ifá.

Debemos pensar primero en nuestras familias
Antes de pensar en forasteros (alguien más)
Adivinado para porogodo
Esposa de Àkókó (pájaro carpintero)

Porogodo era la esposa de Àkókó. Un día àkókó sospechaba que su esposa, porogodo, le iba a ser quitada de él, por lo tanto, fue a la adivinación. Ellos (los Babaláwo) le dijeron hacer ẹbọ. Àkókó no hizo el ẹbọ. Àkókó dijo que en lugar de hacer el ẹbọ pensaría en una forma mas sabia de evitar perder a su esposa por un rival. Por lo tanto, àkókó cavo un agujero en un árbol, escondio a su esposa dentro de él, a continuación, cubrio el agujero y voló a casa. Cuando akókó volvió a buscar a su esposa, no pudo localizar el árbol en particular que la escondió porque no hizo ninguna señal en el árbol. Akoko tiene abejas picoteando árboles desde entonces en busca de su esposa, porogodo, y llamando, "Porogodo, porogodo" en todas partes donde iba.

# Èfà (6)
## Ogbè-Òbàrà

1. Ifá pé óun pé ire iṣégun áti ire éyónú fún ẹni ó dá Ogbè Òbàrà. Ifá pé ẹbọ ni ki ó ru.

Írúlá kò ṣe ọmọ inú ré ṣe pèlé
A d'Ífá fún Olúkóso lá'lú
Arábámbí a fi igba ọta ṣé'gun
Èyí tí yí óó fi àlàpà ṣé'gun ótá ré
L'ójó tí Olúkóso lá'lú ńbínú.
Írúlá kó ṣe ọmọ inu rè ṣe pèlé
A d'Ífá fún Ogbè
L'ọjọ tí ó ńlọ rèé bẹ àrírá

Ní àkókò tí Ifá sọ yíí, àwọn òtá yájú si Ṣàngó, ni Ṣàngó bá binu sí àwọn òtá ré nipa ńrọ òjò iná lé wón l'óri. Àwọn òtà kò gbádùn mó, ni wón bá ro'nú titi wipe tani yí óò bá áwọn bẹ Ṣàngó. Ni wón bá lo ké sí Òrúnmìlà wipe kó wá lọ bá àwọn bẹ Ṣángó. Wón bọ orisi-risi nkan tí ẹnu ńjẹ pelu igba (200) orógbó, óbúkọ kan. Ni Òrúnmìlà bá kó gbogbo nkan wonyi lọ sí òdọ Ṣàngó. Bi Ṣàngó ṣe fi ojú orógbó, ní ó bá yonu si àwón òtà ré, ó l'òun kò ni binu sí wọn mọ. Bí Òrúnmìlà ṣe kúrò l'ódò Ṣàngó ni òjò ṣú.Òrúnmìlà pelu òjò ló padá wọ'lé. Òjò tó ti ńrọ gbígbònà, tutu ni ó rò. Láti ọjó yií ni Ṣàngó tí yónú sí áwọn òtà ré. Òrúnmìlà ni:

Írúlá kò ṣe ọmọ inú ré ṣe pèlé
A d'Ífá fún Olúkóso lá'lú
Arábámbí a fi igba ọta ṣé'gun
Èyí tí yí óó fi àlàpà ṣé'gun ótá ré
L'ójó tí Olúkóso lá'lú ńbínú.
Írúlá kó ṣe ọmọ inu rè ṣe pèlé
A d'Ífá fún Ogbè
L'ọjọ tí ó ńlọ rèé bẹ àrírá
Ogbè ni ó bẹ àrìrà, òjò ni ó bose awo.

2. Ifá pé óun pé ire àìkú fún ẹni tí ó dá Ogbè Òbàrà. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú. Ifá pé óun yí óó ba ṣé'gun ótá.

Ogbè bàràbàrà làá g'ẹtì
Ṣóńṣó orí ẹ l'òógùn
A d'Ífá fún Àágbérí ọga
ọmọ akan'run ma yùn-ún
ọmọ akan'run ma lọ
ọmọ akan'lẹkùn òrun gbọn-gbọn-gbọn má rè
l'ójó ti wón ńránṣé ìkú pé e l'órun

Áágbèrí ti Ifá s'òrò rè yíí nì áwọn òtá pó fún, tí ó sì ńlà álá búburú. Ni ó bá mú ééji kún ééta ó lọ si oko awo. Wón ni ẹbọ ni ki ó rú. Wón yàn án l'ẹbọ, ó rú'bọ. Kó pé àwọn òtá tún bèrè sì ní è'rí ré. Wón pe'rí rè tíktí kò dá wọn l'óhún, béè ni kò sì kú, kaka ki ó kú àwọn òtá rè ni wón ńkú, tí ibi sì mbá wọn. Ló bá nyin àwọn Awo, àwọn Awo nyin Ifá, Ifá nyin Elédùmarè Ò ni béè l'àwọn Awo òun wí pé:

Ogbè bàràbàrà làá g'ẹtì
Ṣóńṣó orí ẹ l'òógùn
A d'Ífá fún Àágbérí ọga
ọmọ akan'run ma yùn-ún
ọmọ akan'run ma lọ
ọmọ akan'lẹkùn òrun gbọn-gbọn-gbọn má rè
l'ójó ti wón ńránṣé ìkú pé e l'órun
À ńpe Ààgbèrí l'òrun kò jẹ agogo
Idẹ ńro ké
Ọlórun ti'kún.

**Àṣẹ:** Ifá pé òun kó ni jé kí ọwọ ótá tẹ ẹní tí ó dá Ogbè Òbàrà.

3. Ifá pé óun pé ire àìkú fún ẹni tí ó dá Ogbè Òbàrà. Ifá pé ki eléyìun ó má ṣe àìgbórán, kí í sì má déjàá. Ifá pé ki ó rú'bọ.

Òpìpí yé díè díè kí o lè baa r'ápá bo eyin
A d'Ífá fún eku
Tí ńjẹ ní mórín àfọn
Òpìpí yé díè díè kí o lè baa r'ápá bo eyin
A d'Ífá fún ejò
Tí ńjẹ ní mórín àfọn
Òpìpí yé díè díè kí o lè baa r'ápá bo eyin
A d'Ífá fún ìgbín
Tí ńjẹ ní mórín àfọn

Àwọn meteeta yíí ní wọn ní kí wọn ó rú'bọ kí ikú má baa pa wọn. Abẹ àfón ni wón fi ṣe ilé ti wón ti ma ńjẹ ni abérè. Wón ni ikú ńbọ o, kí wọn ó rù'bọ. Ítí réé agbede méjí áfón ni ó wà. Ìtí ńlérí fún wọn wipe kò sí ńkan tó jọ ikú tí yi óó dé bá wọn ní ilé óun. Kó sí ńkan ti ó ńbò ti ilé kò gbà dúró. Kì wọn ó má dàáhún. Ninú àwọn meteeta yìì, ìgbín nikan ni ò rú'bọ. Kò pé atégùn lile dé, ki ó tó di wipe ìjì dè, ìgbin ti fi ẹnu la ílè ó kò Sí abé ilè, ó fi yanrin bo ara rè. Kò pé, kò jina, àfòn dúró ó já kúró l'órí iti, ó já jalu eku átí ejó nílé: ó pa wòn. Kò lè dé òdò ìgbin. Báyíí ni ikú kò pa ìgbin tí eku pèlú ejó fi àìgbórán pèlú èjá dida rán ara wọn ní òrun òsan gangan. Láti ìgbà yí ló ti dí ikìlò fún ènìyàn tí ènìyàn bá ńlérí wípé ṣọ'ra à rẹ ò iti kò r'óri gba àfàndùró.

4. Ifá pé ẹni ti ó dá Ogbè-Bàrà, Ifá pé ẹbọ kí àìsan má ba ṣé ni kó rú, kí ó ma ṣe fi eti pálábá ẹbọ rè.

Àṣèṣè yọ òdúndún
Níí f'ara jọ etí adétè
A d'Ífá fún àjídèwe Èdú
Ájídèwe Èdú ni à ńpe Òrúnmìlà.

Ara óun le báyìí mi ó dá Ifá si. Wọn ni ẹbọ ni kó'rú kí àìsan má bá ṣee mó. Òrúnmìlà bèrè ẹbọ, wón yán àn l'ẹbọ: Òrúnmìlà rù'bọ. Láti ọjọ náà ni Òrúnmìlà kò tí ṣe àìsàn mò. Ó wá nyin Elédùmarè Ọba l'órun.

Àṣèṣé yọ ódúndún
Níí f'ara jọ etí adétè
A d'Ífá fún Àjídèwe Èdú
Àjídèwe Èdù ni à ńpé Òrúnmìlà.

traducción

1. Ifá prevé la victoria y recomienda ẹbọ para lograr la victoria.

Írúlá (okra muerto) controla tu ruido
Adivinado para Olúkòso lá'lú * (Ṣàngó alias)
Arábámbí *, rockero (* Ṣàngó alias)
Que mató a sus enemigos aplastados con la
pared el día que estaba enojado
Ìrúlá (okra seco) controla su ruido
Adivincion para Ogbè
El día que fue a apelar a Ṣàngó.

En el momento de esta historia mitológica, algunos enemigos irrespetuosos Ṣàngó. Ṣangó estaba tan enfurecido por el mal comportamiento de estos enemigos que los visitó con serias tormentas. Las enemistades se enfermaron por el efecto de la devastadora tormenta de truenos. Cuando se dieron cuenta de sus errores, se sintieron arrepentidos y solicitados Òrúnmìlà les dijo que les ofreciesen muchos comestibles y que les proporcionaran un macho cabrío y 200 orògbó. Òrúnmìlà tomó los 200 orógbó y el macho cabrío a Ṣàngó. Tan pronto como Òrúnmìlà dio Ṣàngó las ofrendas, Ṣàngó instantáneamente perdonó a los enemigos de sus delitos menores. En lugar de las incesantes tormentas devastadoras que se avecinan, Ṣàngó soltó una lluvia pacificadora curativa. Òrúnmìlà aún no había podido regresar de su visita al santuario de Ṣàngó cuando empezó la lluvia. Òrúnmìlà dijo

Írúlá (okra muerto) controla tu ruido
Adivinado para Olúkòso lá'lú * (Ṣàngó alias)
Arábámbí *, luchador de rock
Que mató a sus enemigos aplastados con la
pared el día que estaba enojado
Ìrúlá (okra seco) controla su ruido
Divined para Ogbè
El día que fue a apelar a Ṣàngó.

2. Ifá fomenta la larga vida y recomienda ẹbọ para la victoria sobre los adversarios.

Ogbé bárábárá es el sonido de indigo pounding
Su pico es la medicina potente
Adivinado por el rey de Irágbérí
El que no moriría joven
Y vivió hasta una edad muy avanzada
Incluso cuando fue convocado al cielo

**Àágbérí** estaba teniendo pesadillas constantes, por lo tanto, decidió consultar Ifá. El Babaláwo le dijo que hiciera ẹbọ y le diera una lista de cosas para el ẹbọ. Àágbérí hizo el ẹbọ. Y estaba protegido contra los ataques de sus enemigos. Poco después del ẹbọ, los enemigos comenzaron a librar la guerra en Àágbérí una vez más, pero en virtud del ẹbọ que hizo, las malas acciones de los enemigos regresaron a ellos, y comenzaron a morir. Àgbérí comenzó a elogiar a su Awo por su buen trabajo, el Awo agradeció a Ifá, y Ifá (Òúnmìlà) agradeció a Olódùmarè. Con felicidad, Àágbérí dijo que su Awo le dijo que:

Ogbé bárábárá es el golpeteo del sonido de indigo
Su pico es la medicina potente
Divined para el rey de Irágbérí
El que no moriría joven
Y vivió hasta una edad muy avanzada
Incluso cuando fue llamado al cielo
No respondió a la llamada (no murió)
Porque Ifá lo protegía en virtud de un encanto hecho en
Agogo Ifá para él
Ese encanto hizo que la puerta de los puentes se trabara contra él.

3. Ifá dice larga vida para quien salga Ogbé Òbàrà. Ifá advierte a la persona que no desestime el consejo de Ifá y no desobedezca ningún consejo para ẹbọ. Ifá dice make ẹbọ

Gallina ponen una pequeña cantidad de huevos para poder tramarlos
Adivinado para eku (rata)
Que juega alrededor de la trampa para los animales
Gallina ponen una pequeña cantidad de huevos para poder tramarlos
Adivinado para serpiente
Que corre alrededor àfọn (un árbol)
Gallina ponen una pequeña cantidad de huevos para poder tramarlos
Adivinado para el caracol
Que se arrastra alrededor

Estos tres reptiles fueron aconsejados hacer ẹbọ para salvar sus vidas. Los reptiles vivían y hacían todo bajo el Èfón y se les decía que la muerte estaba acechando a su alrededor, debian hacer ẹbọ para la prevención. Ítí (planta parásita en los árboles) por su cuenta estaba en el centro de Àfòn. Ítí les dijo que no hicieran ẹbọ porque sentía que nada malo podía sucederles, y que no les importaría a los Babaláwos. De los tres reptiles, el caracol fue el único que hizo ẹbọ. Poco después de que el consejo de los Babaláwos hacer ẹbọ, un viento fuerte ocurrió. Antes de eso, sin embargo, el caracol había cavado un agujero y se había enterrado bajo la arena. La fuerza del viento separada del árbol de Ítí; Si cayó sobre la rata y la serpiente, y los mató, pero el caracol fue salvado por haberse enterrado bajo la arena. Cuando en todas partes se volvió a calmar, el caracol salió de su escondite. De esta manera, la vida del caracol fue salvada y la desobediencia y la falta de respeto por el consejo espiritual asesinaron a la rata ya la serpiente.

4. Ifá dice a quienquiera que este Odù Ifá salga para debe hacer ẹbọ para prevenir enfermedad. La persona debe siempre hacer ẹbọ prescrito.

Un ódúndún en germinación
Parece una hoja de Euphorbia bateri
Adivinado para Ájídèwe Èdú
Àjídéwe Édú es otro nombre para Òrúnmìlà

"¿Gozaré de buena salud?" Fue la pregunta de Òrúnmìlà planteada a Ifá. Ellos (los Babaláwo) le dijeron que hiciera ẹbọ para librarse de la enfermedad. Òrúnmìlà preguntó cuáles eran los requisitos de ẹbọ. Le dijeron; Él hizo el ẹbọ. Desde entonces, Òrúnmìlà gozaba de buena salud. Por lo tanto, comenzó a alabar Òlódùmarè diciendo:

Un ódúndún en germinación
Parece una hoja de Euphorbia bateri
Adivinado para Ájídèwe Èdú
Àjídéwe Édú es otro nombre para Òrúnmìlà.

# Èje (7)

## *Ogbè-Òkànràn*

1. Ifá pé óun pé ire ọmọ fun ẹni tí ó dá Ogbè-Kánrán. Ifá pé ẹbọ ni kí ò rù. Ifá pé ìrin ájò kan ni eléyiun fé lọ, kí ó rù'bọ kí ibè le ba san án sí owó, kí ó san án si ọmọ.

Ká bù'jẹ, ká bù tà
A d'Ífá fún Áwújẹ
Tí ó ńlọ oko áléró l'ódún
Ó ní rí'rú ẹbọ  níí gbe ni
Áìrú kìí gbè'niyán

Áwújẹ tí Ifá ńsọ yii ojú ọmọ ńpọn kò rí ọmọ bí. Ló bá mú ééjí kún ééta, ó llọ oko awo wipe bawo ni òun yí óò ṣe rí ọmọ bí àti wipe óun fé rin irin àjò, ǹjé ibè yi óó sna òun ni ó dá Ifá si. Wón ní á ri ọmọ bí ní ibè, wón ni ẹbọ ni kí ó rú. Wọn yàn án l'ẹbọ, ó sì rú ẹbọ náà. Kò pé tí Áwùjẹ di ọlọmọ púpò. Ó wá nyin Awo, Awo nyin Ifá, ó ni béè ni wón wó:

Ká bù'jẹ, ká bù tà
A d'Ífá fún Áwújẹ
Tí ó ńlọ oko áléró l'ódún
Ó ní rí'rú ẹbọ  níí gbe ni
Áìrú kìí gbè'niyán
Kèè pé o, kèè jina
Ẹ wá bá wa laarin ọmọ
Áárin ọmọ làá bá'ní l'ẹsẹ Ọbárìṣà

2. Ifá pé óun pé ire iṣégun òtà. Ifá pé òun yi óó yọ ó laarin òtá. Ifá pé òun yí óò jé ki ó ri ojútùú ayé e rè. Ifá pé ẹbọ ni ki ó rú.

Ọtapẹtẹmoso
A d'Ifá fún ọró

Ọró tí Ifá s'óró rẹ yií, àárín ọtá ẹlẹyẹ ni ó wá dé ibi wipe wọn kò jẹ ki ó rí ojútùú ayé ré. Wọn kò jẹ kí ó nilaari. Ọró ro'nú titi wipe kini òun lè ṣe, loba ko'ri s'ilé alawo. Wón dá Ifá fún, wónòtá ẹlẹyẹ ló ńba já wipe ẹbọ ni ki ó rú. Kí ó rú ékọ fifọ, ata pupa, abéré lópòlọpọ. Oró tó'jú gbogbo nkan wonyi. Ni wòn bá rú'bọ fun. Wọn ṣe Ifá fun s'inú èkọ fifó: wón fá èkọ yii pò mọ abéré, ni wón bá ní kí Ọ ró gbé èkọ náà mu. Ọró gbé ẹkọ náà mu. Bi ó ṣe mu ú tán, áwọn ẹlẹyẹ kò lé dé òdọ ré mó. . abẹrẹ ọjó yẹn ni ègún tí ó wà ní ara ọró di òni. Ẹkọ ọjó náà ni ó di oje ara ré, ata ọjó náà ni ó wà l'ára oje rè ti kò fi gbodo dá si ojú. Báyii ni áwọn ẹlẹyẹ kó lè dé ódò oró mọ, tí ọró sí ṣé'gun àwọn ẹlẹyẹ pátápátá.

3.
Ido apata ab’idí jẹjẹrẹ
A d’Ifá fún Ọlágbégi
Ti ńlọ Òkitì Ẹfón
Ti ńlọ rèé bá wọn mí’lẹ ibùdo

Ọlágbégí yií ènìyàn ni. Ninú ilú ré, awọn ótá pò fún nitori Orúkọ rè. Orúkọ yii ni áwọn èniyàn fi ńbinú ré wipe koni tîì dé ibikan, ti yi óò fi di ẹni ńla gẹgẹbí orùkọ ré, Àwọn òtá kó jẹki ó dide. Ó wa ro’nú wipe kini òun lé ṣe. ni ò bá mú ééjí kún ééta ló lọ oko awo. Wón ni kí ó kùrò ninú ilú yìí ki ó lọ si ìlú mìíràn, ki ó sì rú’bọ. Wipe tí ó bá ti rú’bọ, yi óò si à orúkọ rè dá, òtò ni orùkọ ti yi óò ma jẹ ti yi óò fi di ẹni ńlá. Tí ó bá ti rí ṣe tán ti ó di ẹni ńla, yi óò wá mapadà jẹ orúkọ ré. Ni Ọlágbégí bá rú’bọ, ó pa orúkọ ré dá. Ìgbàtí ó dé ilú miran, báyìí ni ó bèrè si rí ṣe. ti gbogbo ńkan rẹ ńdára, tí ó si di ńla. Ó nyin Awo, Awo nyin Ifá, Ifá nyin Elédùmarè ọba l’órun. Nigbati ó de òde Òkitì Èfọn, wọn bí í léèrè pé. “kinni  orúkọ rẹ o?” Ó dahun wipe Ọlájùwéré ni orúkọ òun jẹ. Ni wón bá bu ilè ilè átí ilè oko fún. Ló bá tè’lù dó sibe náà. Òun ló wá kù ti ńjẹ ọba ni òde Ọwọ- Ọlágbégí (Ọlọwò of Òwò) Ifá pé òun yi óò bá eléyiun ṣé’gun òtá. Ifá pé ẹbọ ni ki ó rú, ki ó si ma fi eti pàlábá ẹbọ tí wón bá ni ki ó rú.

4. Ifá pé ẹni tí á dá Ogbè Òkànràn ki ó rú'bọ nitori ajogun ibi fún eléyiun.

Àdán l'awo arà riri rá riri
Ògbigbì l'awo arà riri rá riri
A d'Ífá fún Ogbè

L'ójó ti ó ńlọ rèé kan ikú, kan ófò, kan òràn, ni Ifè Oòyè lagbèmoró.

Ni ayé àtijó àwọn ara Ifẹ ni àwọn ajogun pò fún, ti wón ndá wọn laamu, ni àwọn ara Ifẹ bá ranse pé Awo wipe kí ó bá áwọn bèrè l'ówó Ifá. Ígbàti wọn ó dá Ifá, wọn da Ogbè-Kànràn. Ifá ni ki wọn ó pa órúkọ (òbúkọ) ńlà kan, ki wọn ó pe iyé Ifá sì, ki wọn ó lọ rèé fi s'ẹnu odi ilú. Kí wọn kàn-àn mó ígí ńlá l ehin odi ilú. Ni àwọn ará Ifé bá ṣe ohun tí Ifá wí. Láti ọjọ ti wọn ti ṣe irúbọ yii ni òfò, ikú òjìji, pelu gbogbo ibi yooku kò ti ṣẹlé sí wọn mó, ni wón bá ṣe áṣàrò wipe orúkọ wo ni wọn ó ma pé Odú yí, wọn ni Ogbè-kánrán ni toripé óun ló lọ rèè kan ikú, tó kan òfò, tò kan ìyà, tó kan òràn n'Ífẹ Oòyé Lagbèmoró.

***Traduccion:***

1. Ifá dice que bendecirá a la persona que Ogbè Òkànràn sale con un niño, pero que la persona debe hacer ẹbọ. Ifá dice que la persona va en un viaje, por lo tanto, él/ella debe hacer ẹbọ para que el viaje sea fructífero-fructífero para todo ire, salud, riqueza, éxito y niños buenos

Comer, vender
Adivinado para Áwúję̣ (tipo de frijoles)
Quien iba en un largo viaje
Ella dijo que hacer ẹbọ tiene su recompensa generosa
Negativa a hacer ẹbọ tiene su retroceso

**Àwùjẹ** en referencia aquí era sin hijos, y ella estaba muy desesperada por un niño. Como resultado de su problema, consultó Ifá para la solución. Además de la cuestión de la falta de hijos, también consultó a Ifá por un viaje que planeaba hacer. Ifá aseguró Àwùjẹ que ella sería bendecida con niños pero recomendó ẹbọ. Ifá también le aseguró que su viaje sería beneficioso. El Babaláwo le dijo a Àwùjẹ las cosas requeridas para ẹbọ. Àwùjẹ siempre que las cosas, ẹbọ se hizo en consecuencia para ella. Poco después del ẹbọ, Àwùjẹ comenzó a tener hijos y dinero. Por lo tanto, le dio las gracias a Awo mientras el Awo le agradecía a Ifá, Ifá a Òlodùmaré. Àwùjẹ dijo:

Comer, vender
Adivinado para Áwúję̣ (tipo de frijoles)
Quien iba en un largo viaje
Ella dijo que hacer ẹbọ tiene su recompensa generosa
Negativa a hacer ẹbọ tiene su retroceso
Poco después del ẹbọ
Fuimos bendecidos con niños
Regocíjate con nosotros en la adoración del Òrìṣà.

2. Ifá prevé la victoria para quien quiera que sale este Odú, Ifá dice que protegerá a la persona contra todos los adversarios. Ifá dice que coronará los esfuerzos de la persona con sucesos. Ifá recomienda ẹbọ

Ọtapẹtẹmoso
Adivinado por ọró

**Ọró** en su referencia estaba rodeada de brujas que arruinaron su vida. Ọró estaba deprimido y pensó en lo que podía hacer para salvarse de las garras de las brujas. La solución que le vino a la mente fue Ifá. Por lo tanto, fue a la casa de un Babaláwo y consultó a Ifá. El Babaláwo adivinó para él y confirmó que verdaderamente, las brujas estaban en su contra. El Babaláwo entonces le aconsejó hacer ẹbọ. Ọró le dijo que proveyera ẹkọ (comida tradicional de Yorúbá. Ẹkọ es una comida de almidón de maíz), mucha pimienta de cayena, muchas abéré (agujas). Ọró proveyó las cosas, y ẹbọ fue hecho para él. Se realizó un trabajo especial en el Ẹkọ después del cual se mezcló con el abéré. Le dijeron a Ọró que bebiera la mezcla que hizo. Tan pronto como bebió la medicina, todos los que se encontraban más allá de molestarlo huyeron. El abéré usado para la medicina de Ifá ese día se metamorfoseó para ser la espina encontrada en ọró hasta hoy. Ese día ẹkọ es la savia de ọró, la pimienta de cayena de ese día es el veneno que viene con la savia que hace la savia venenosa a los ojos. A través de esta obra espiritual, ọró venció a sus enemigos-las brujas.

3.
Ido apata
Adivinado para Ọlágbédí
Cuando viajaba a Òkìtì Èfòn (una ciudad)
Cuando iba a tener una residencia permanente allí

**Ọlágbégí** era una persona muy trabajadora y famosa. Dondequiera que iba, la gente lo respetaba por el buen nombre que hacía para sí. sin embargo. La fama de Ọlágbégí hizo a sus enemigos incómodos, y lo despreciaron gravemente por eso. Estos enemigos hicieron cosas horribles para mantener a Ọlágbégí abajo, pero sus ángeles de la guarda lo protegieron. Instintivamente, Ọlágbégí sabía que algunas personas estaban librando una guerra contra él, y esto le dio un concierto muy serio. Un día, decidió consultar a Ifá a través de su Babaláwo. Fue a su Babaláwo, y el Babaláwo consultó Ifá para él. Ifá le dijo a Ọlágbégí que abandonara la ciudad de su nacimiento para otro lugar. Él también fue aconsejado hacer ẹbọ y cambiar su nombre-para el progreso rápido-tan pronto como él consiguiera a ese otro pueblo. Además, Ifá le dijo a Ọlágbégí que tan pronto como tuviera éxito, debería volver a su verdadero nombre. Ọlágbégí hizo el ẹbọ y se fue. Tan pronto Ọlágbégí llegó a su pueblo predicho Ifá, Ókìtì Ẹfọn, cambió su nombre según la sinjunción de Ifá. Cada vez que se le preguntaba cuál era su nombre, él les diría que su nombre era Ọlájùwéré. Él comenzó su nueva vida allí con trabajo duro. Por suerte para él, su negocio creció, y se convirtió en próspero. Pronto, se ganó el amor y el respeto de la comunidad. Para demostrar cuánto lo amaban, la comunidad le dio una gran superficie de tierra. Ọlágbégí construyó casas en la tierra, mientras que utilizó gran parte de ella para la agricultura. Ọlágbégí construyó muchas casas y asumió allí su residencia permanente. Pronto, Ọlágbégí fue hecho rey de Ọwọ, y se hizo conocido como Ọlágbégí, Ọlọwò (rey) de Òwò. Él mientras que su Awo elogió Ifá, e Ifá (Ọrúnmìlà) elogió Olódùmarè.

**Àṣẹ̀.** Ifá dice que hará que la persona que este Odù salga victorioso. Ifá recomienda ẹbọ y advierte a la persona que nunca desobedezca el consejo.

3. Ifá dice quien Ogbè Òkànràn sale para debe hacer Ebo para rechazar las fuerzas del mal que rodean a él / ella.

Àdán lá awo arà rírí rà rírí (Descripción de los movimientos de la barra)
Ògbìgbì l'awo arà bábábá ka'lẹ
(Descripción de los movimientos de ògbìgbì)
Adivinado para Ogbè
El día en que debía combatir la muerte, combatir la enfermedad, combatir las pérdidas, combatir todos los problemas en ilé Ifé durante el reinado del rey Lagbémoró.

Érase una vez en la antigüedad, la gente del Ifé estaba constantemente aterrorizada por ajogun (fuerzas malas), y cuando ya no podían soportar más, mandaron llamar a un Babaláwo para consultar a Ifá por ellos. Cuando Ifá hablaba, Ifá les hablaba a través de Ogbè-Kànràn. Ifá les dijo que ofrecieran un macho cabrío grande, Ifá instruyó a los Babaláwo a bendecir la ofrenda con un canto especial de Ifá, clavar el ofering en un árbol grande fuera de la puerta a la ciudad. La gente de Ifé hizo el ẹbọ según la instrucción de Ifá. Desde el día que la gente de Ifé hizo el ẹbọ, la muerte, enfermedad, pérdidas, problemas y todas las otras cosas malas dejaron de sucederles. Después de eso, la gente se reunió y se preguntó: "¿Qué nombre debemos llamar a este Odú?" Respondieron unánimemente: "Llamemos al Odù, Ogbè Òkànràn porque fue el Odù el que clavó (enterró) la muerte, enfermedad, pérdidas y Todos los problemas en Ilé Ifé "

# Èjọ (8)

## ***Ogbè-Ògúndá*** (Ogbè Yónú)

1. Ifá pé óun pé ire ọmọ fun ẹni tí ó dá Ogbè Yónú. Ifá pé áwọn méji ni ojú ọmọ ńpón. Ifá pé ki wọn ó rú'bọ nitori ki wọn ó le ba bí'mọ.

Ẹbọ: Ewúré kan ni ẹbọ. Ẹ gbó bi Ifá ti wi:

ọká gbé'nú ìtẹ
Ọká ńyọ'ri ọlá idada idada
Eré gbé'nú àbàtà ga'rún oyé
A d'Ífá fún àgà dúdú
A bù fún àgan pupa
Ẹkunọmọ ni wọn ńsun.

Ni ayé àwọn ágán méjì kan wá ti ojú ọmọ ńpọn. Àgàn ákókó ni óro, àgan elékéji ni ọsán ágbálùmò. Ojú ọmọ ńpọn àwọn àgan méjèèjì yi debi wipe ekun ni wọn ma á fi ṣe oúnjẹ Wọn ro nu titi wọn kó mọ ohun tí wón le ṣe. ni wọn bá mú ééjì kún ééta wọn lọ si oko awo. Ńjẹ àwọn lé bi'mọ bayii ni wọn dá Ifá sí. Ifá ni wọn óò ni'mọ, ẹbọ ni kí wọn ó rú. Ni wọn bá yàn wón l'ẹbọ. Ọsàn àgbálùmó ló kókó rú'bọ, ó fi ewúré kékeré rú'bọ tirè, Ìgbàtí yi óò fi'mọ, ọmọ rè kere. Bí òro ṣe gbó wipe ọsán àgbálúmò l'óyún, ó bí'mọ, ọmọ ré kere, ni òro náà bá sáré mú ewúré. Ìgbátí òun fé rú'bọ tire, ewúré ńlá ni ó rú l'ẹbọ. L'éhin irúbọ tirè nàà, oyun dé, nigbati yí óò bí'mọ, ọmọ tirè tobi. Inú àwọn méjèèjì dùn, wó nyín Awo, Awo nyin Ifá, Ifá nyin Elédùmarè. Wón ni béè ni àwọn Awo wipe:

ọká gbé'nú ìtẹ
Ọká ńyọ'ri ọlá idada idada
Eré gbé'nú àbàtà ga'rún oyé
A d'Ífá fún àgà dúdú
A bù fún àgan pupa
Ẹkunọmọ ni wọn ńsun.
Àgán dudu làá pé òro, àgan pupa làá pé ọsán àgbálúmọ

2. Ifá pé ẹni ti ó dá Ogbè Yónú, Ifá pé kí ó má ṣe yájú si áwọn ti ó júú lọ. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú.

Ìbínú kó ṣe ńkan rere fún ni
Suuru ni baba ìwà
Àgbà tí ó bá ní suuru
Ohun gbogbo ló ní
D'Ífá fún Ọrúnmìlà
L'ọjọ ti ó nṣawo r'ode Íwó

Òrúnmìlà ló ṣ'awo lọ si Óde Íwò. Ígbáti ó de òde Ìwó ni Olúiwó bá pé é l'áwo. Òrúnmìlà ki Ifá fún Olúiwó, ó já Ifá. Ara kó ró wọn ni ilú Íwó ni wọn dá Ifá si. Òrúnmìlà ní ẹbọ ni ki wọn ó rú. Wọn rú'bọ. Gbogbo ńkan ti ó le fún wọn ní ìlú Íwó, ara bèrè si ni ró wón, ara kó ni wón mó. Gbogbo ńkan wọn bèrè sí ni dára, ni Olúiwó bá ro'nú títí wípé kíní òun lè fi ta Òrúnmìlà l'órẹ Olúiwó si ni ọmọbinrin kan, ni ó bá fi fún Òrúnmìlà wipé kó fi ṣe aya. Ni Òrúnmìlà bá ṣe awo lọ, ìgbàti yi óò bá fi padá dé ilé, iyáwó rè yí óò ti la ọpọn Ifá dá'ná. Ó sá à nṣe ńkan tí ó lé bí Òrúnmìlà ninú, súgbón kàká kí Òrúnmìlà ó binu, ó nfi ara dá á Ìgbàti ó dì ọjọ kan ni iyàwó yií náà bà ro'nú wípé ẹni ti òun ńṣe gbogbo àidàra wònyí si tí kó binu, á jé wípé yí óò lè sin òun. Báyìí ní ó yí iwá padà ti ó si bérè ni hu iwà rere. Báyíí Òrúnmìlà padà wa si ilé pèlú iyawo rè. Bí wọn ṣe ri obinrin yii ni èyin Òrúnmìlà wọn ńbèèrè l'òwò rè wípé. "Tanì eleyii?" Òrúnmìlà wá ndá wọn l'óhun wípé, "Íyà tí mo je ni Íwò níyí" Iyà ni wọn ńpè ni Ìyàwó. Ifá ńfi eléyii kó wa ni èkó wípé ki a ni ifarada l'órí ohun gbogbo.

3. Ifá pé òun pé ire áíkú fún ẹni tí ó dá Ogbè Yónú. Ifá pé òun yí óò ba ṣé'gun ótá lópólọpó.

sègi dudu lawo inú igbo
Àyìnrin a b'èdó gòlòǹtọ
Báábá ni í ṣ'awo ayé
A d'ífá fún Ngò-ni-ṣe-báyìí-ku
Tí í ṣe ọmọ onípapósin
L'ójó tí i r'ayé aláníikú

Ngó-ni-ṣe-bàyíí-kù ti Ifá sọ yii, èniyàn ní í ṣe. Àwọn òta pọ fun, wọn sì ńléri si wipé àwọn yi óò ma wo bí yi óò ṣe gbé ilé ayé, wipe àwọn kó ní jeki ó ri ilé ayé gbé. Bayii ni wón nran àwọn ajogun ibi si. Ko mọ eyiti yí ó ṣe mó. Ni ò bá gba oko alawo lọ. Àwọn awo yán án l'ẹbọ. Kí ó lè ṣé'gun áwọn òtá rè ni ki ó rú'bọ sí. Báyíí ní ó bere sí ni í'ségun àwọn òtá rè ni ki ó rú'bọ sí. Báyíí ní ó bere sí ni íṣégun àwọn òtá rè. Ikú ti àwọn òtá rè sọ wipé yi óò kú. Ngó-ni-ṣe-báyìí-kú kó kú mó. Àwọn òtá ré ló bèrè si ni kú. Ó nyin Awo, Awo nyin Ifá, Ifá nyin Elédùmarè ọba l'ọrun. Ó ní béé l'áwọn Awo wí pé:

sègi dudu lawo inú igbo
Àyìnrin a b'èdó gòlòǹtọ
Báábá ni í ṣ'awo ayé
A d'ífá fún Ngò-ni-ṣe-báyìí-ku
Tí í ṣe ọmọ onípapósin
L'ójó tí i r'ayé aláníikú
Ifá ngò ni ṣe báyíí kú
À gbó ra koro ni ti igbin
Bí ẹyẹ olóḡoṣé bá gbógbógbó
A dabi èwe
Àgbó mi kán nkò kú mó
Ọdọọdún l'ewé
Ájídèwe ni ti eku èléri.

4. Ifá pé òun pé ire ọmọ fún ẹni tí ó dá Ogbè Ògúndá. Ifá pé Ìbejì ni óò bi. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú.

Àbò wá l'éré ọjá
A d'Ífá fún alátẹóde
Tí yí óò l'óyún Ogbè òun Ògúndá ninu

alátẹóde tí Ifá ńsọ yìì, àgan ní. Ojú ọmọ pón-ọn gidigidi. Ó bere sí ni ro'nú. Í yá ó lọ rèé ṣe àyèwò. Wòn nì yí óò bì'mọ, ẹbọ ní kí ó rú wipe ibeji ni yi óò fi bí. Ó rú'bọ. Ígbàtí yí óò ni'mọ, ó bí ibeji. Idí niyi ti a fi ńpe orúkọ. Odú yi nì Ogbè Yónú.

Àbò wá l'éré ọjá
A d'Ífá fún alátẹóde
Tí yí óò l'óyún Ogbè òun Ògúndá ninu
Alátéóde wa fi ohun okun sílè
Ide ló fi ńké ọmọ
Àbọ wá l'èrè ọjá.

*Traduccion.*

1. Ifá dice ire para quienquiera que Ogbè Ògúndá salga. Ifá dice que dos personas están desesperadas por los niños. Ifá dice que la gente debe hacer ẹbọ con el fin de tener a los niños.

**Ẹbọ:** 1 hembra de cabra. La autoridad de Ifá para este mensaje es la siguiente:

Oká (víbora del gaboon) maravilla en su trono majestuoso
Oká se comporta majestuosamente
Èrè (real python) se maravilla en su majestuoso trono de barro
Adivinacion para una hermosa mujer negra estéril
Adivinacion misma para una de tez clara
Estaban llorando por falta de niños.

En la antigüedad, había dos personas estériles; Eran òro (fruto carnoso de Yorùbà) y ọsán ágbálúmó (una fruta anaranjada de Yorúbà). Òro y àgbálùmò estaban tan desolados con su falta de hijos que lloraban todo el tiempo incesantemente. Antes de renunciar a la esperanza, sin embargo, consultaron a Ifá. Le preguntaron a Ifá si iban a tener hijos. Ifá les aseguró que tendrían hijos, pero para hacer ẹbọ. Ágbálúmó fue el primero en hacer el ẹbọ, ofreció una cabra pequeña para ẹbọ. Por lo tanto, cuando ágbálúmó empezó a tener hijos, los niños eran todos pequeños. Viendo que ágbálúmó pudo tener hijos en virtud del ẹbọ, òro se apresuró a hacer su propio ẹbọ y sacrificó una gran cabra. Cuando òro debía tener sus propios hijos, los niños eran eran todos grandes. Ágbálúmó y òro estaban felices por sus preciados dones, y elogiaron su Awo. Sus Babaláwo elogiaron a Ifá (Òrúnmìlà), e Ifá elogió a Olódúmarè. ellos dijeron:

Oká (víbora del gaboon) maravilla en su trono majestuoso
Oká se comporta majestuosamente
Èrè (real python) se maravilla en su majestuoso trono de barro
Adivinacion para una hermosa mujer negra estéril
Adivinacion misma para una de tez clara

Òro (personificado) es la hermosa persona estéril negro aquí
Ágbálúmó (personificado) es la persona de tez clara aquí

2. Ifá advierte a quienquiera que Ogbè Yónú salga para no despreciar a las personas que son su/sus mayores de edad ya sea por edad o por posición. Ifá también recomienda ẹbọ

La ira no sirve
La paciencia es el padre del buen carácter
Y anciano bendecido con la sabiduría de paciencia
tiene todo
Adivinado para Òrúnmìlà
El día en que emprendió el viaje espiritual a Íwó
Cuando fue allí a casarse con Íyá, la hija del rey de iwó

**Òrúnmìlà** emprendió un viaje espiritual a la ciudad de Ìwó. Cuando llegó allí, el rey de Ìwó lo invitó a la divinación. Òrúnmìlà adivinó para el rey y le dijo exactamente cuál era el problema con el rey. El problema era que el pueblo de Íwó estaba en dificultades y esa era la razón principal de la consulta del rey con Ifá. Òrúnmìlà les dijo que hicieran ẹbọ Íwó la gente hizo el ẹbọ, y su dificultad desapareció tan pronto como el ẹbọ fue hecho. Todo empezó a ser bueno para ellos. El rey estaba contento e impresionado por el trabajo de Ifá hecho por su pueblo que decidió mostrar su gratitud a Òrúnmìlà. Pensó en la mejor manera de compensar a Òrúnmìlà por el alivio que trajo a su pueblo. Mientras tanto, el rey tenía una hija a Òrúnmìlà como esposa. Òrúnmìlà tomó a la princesa como su esposa y siguió viviendo en Ìwó - sólo por un tiempo. Cada vez que Òrúnmìlà prosiguió su viaje espiritual, la princesa/apètèbí destruia parte de la parafernalia Ifá de Òrúnmìlà. Una vez agarro ọpọn Ifá y la utilizó como leña. Hizo todas estas cosas para provocar Òrúnmìlà, pero Òrúnmìlà nunca mostró cólera. Un día, sin embargo, la princesa penso que definitivamente Òrúnmìlà era el hombre adecuado para ella porque Òrúnmìlà era probablemente el único hombre que tomaría todas las cosas feas que hizo sin una sola venganza. La princesa cambió su mala actitud por una buena. Con este cambio de buen carácter, Òrúnmìlà decidió volver a casa, y llevó a la princesa con él. Tan pronto como Òrúnmìlà llegó a casa, vecinos y amigos empezaron a preguntarle, "¿Quién es esta mujer?" La respuesta de Òrúnmìl'a a la pregunta era "Íyá tí mo jẹ ni Íwó rè é" que significa "este es mi sufrimiento en la ciudad Íwó", por lo tanto, "Íyá tí mo jé Íwó" se metamorfoseó a Ìyàwò.

**Àṣẹ̀:** Ifá nos enseña una lección de que debemos tener paciencia en lo que hacemos.

3. Ifá predice longevidad para quien quiera que Ogbè Ògúndá salga, Ifá también predice la victoria sobre sus adversarios.

Negro sẹgi es el adivino de la madera
Báábá es el adivino para la tierra
Adivinado para yo-no-morir-pobre
Hijo de onípápósin
Cuando iba a disfrutar de una "vida sin fin"

Yo-no-morire-pobre era una persona rodeada de muchos enemigos celosos que rezaban por su caída. Como parte de su complot, los enemigos enviaron hechizos e incluso contrajeron la ayuda de fuerzas malignas para derribar a yo-no-moriré-pobre. Cuando yo-no-moriré-pobre estaba cansado de huir de estos enemigos, consultó Ifá para ayuda y protección. El Babaláwo le dijo que tenía que hacer ẹbọ para vencer a los enemigos. Yo-no-moriré-pobre hizo el ẹbọ, tan pronto como él hizo el ẹbọ, maquinaciones malignas de los enemigos volvieron a ellos; Murieron de sus parcelas. Por lo tanto, yo-no-moriré-pobre comenzó a alabar a los Babaláwo; El Babaláwo elogió Ifá (Òrúnmìlà), e Ifá elogió a Olódùmarè en el cielo yo-no-moriré-pobre dijo que su awo le aseguró que:

Negro sẹgi es el adivino de la madera
Báábá es el adivino para la tierra
Adivinado para yo-no-morir-pobre
Hijo de onípápósin
Cuando iba a disfrutar de una "vida sin fin"
Ifá dice: "yo-no-morir-pobre"
Longevidad, así es como vive la tortuga
Longevidad, así es como vive el caracol
Cuanto más larga sea la vida ológoṣẹ́ (pájaro), más joven parecerá
No moriré más
Cada año estoy vivo
Bebé fresco es cómo Eleri (rata) se mira

**Àṣẹ̀:** Ifá nos hará victoriosos sobre nuestros enemigos

4. Ifá dice que bendecirá a la persona que Ogbè Ògúndà sale con bebés gemelos. Dice Ifa hacer Ebo.

El beneficio en las ventas hace al vendedor feliz
Adivinado para Alátẹ̀òde (un vendedor)
Que estaba embarazada de Ogbè y Ògúndá

**Alátẹ̀òde** era una mujer estéril que estaba desesperada por un niño y estaba muy preocupada por la falta de hijos. Para resolver el problema, fue a un Babaláwo a consultar a Ifá. El Babaláwo le aseguró que tendría un hijo, pero para hacer ẹbọ y que después del ẹbọ, tendría gemelos. Alátóóde hizo el ẹbọ, quedó embarazada. Cuando llegó el momento de la entrega, ella entregó bebés gemelos. Por eso este odú se llama Ogbé Yónú.

El beneficio en las ventas hace al vendedor feliz
Adivinado para Alátẹ̀òde (un vendedor)
Que estaba embarazada de Ogbè y Ògúndá
Alátẹóde llegó a ser tan próspero que
Mimaba a sus hijos con cosas caras
El beneficio en las ventas hace al vendedor feliz.

# Èsán (9)

## *Ogbè-Sá*

1.
Ọwó ri iyan, ọwó y'óké
Àtàǹpàkò ló rí àgbàdo òjò ló ṣe mùlúnkú mùlúnkú
A d'Ífá fún Òrúnmìlà
Yí óò gb'ọmọ rè sá g'àjà nitori ikú.

Òrúnmìlà ni ó fura si àwọn òtà nigbati wọn ńbá a já, ni ó bá gbé òkéìpònrí rè ka'lé ó pé áwọn Awo, wón ba dá Ifá. Wọn ní ẹbọ ni kí ò rú. Wọn yàn-àn l'ẹbọ, ó rú'bọ. Àsìkò tì àwọn òtá bá nran àwọn ajogun ibi, wọn kíí bá Òrúnmìlà ni ilé, wọn kó ni bá ọmọ rè, béè ni wọn kó ni bá iyáwó ré. Ni àwọn ajogun ibi bá ńfi ábó s'órí àwọn òtá Òrúnmìlà. Ó ni:

Ọwó ri iyan, ọwó y'óké
Àtàǹpàkò ló rí àgbàdo òjò ló ṣe mùlúnkú mùlúnkú
A d'Ífá fún Òrúnmìlà
Yí óò gb'ọmọ rè sá g'àjà nitori ikú
Ikú wọ'lé mi kò bá mi
Kérégbè òfifo o mà kú àrin nú
Àrún wo'lé mi kò bá mi
Kèrégbè òfifo o mà kú àrin nù
Gbogbo ajogun ibi wọ'lé mi wọn kò bá mi
Kèrègbè òfifo o mà kú àrin nù

2.
Ìbájé owó kò  láṣànú
A d'Ífá fún Òrúnmìlà
L'ọjọ ti ó nr'oko réé lá.

Òrúnmìlà ni ó fẹ ṣ'awo lọ si ìgbèriko, ni ominú wá ńkọ ó wípé àbi kí òun ó lọ tàbí ki òun ó má lọ. Ni ó bá gbe ókéìpònrí ré ka'lè, ó pé àwọn Awo, àwọn Awo ba dá Ifá, wón ní ẹbọ ni Kí ó rú wipé Òrúnmìlà yí óò lá wá'lé Láti ibé ni. Wọn bá yan Òrúnmìlà l'ẹbọ. Ó rú'bọ. Ó de ibẹ, ení tí kò rí ṣe. Òrúnmìlà ṣe Ifá fún wọn, onikálukú bèrè sí rí ṣe. bayii ni wón ṣe ńkó ẹrú Kó ẹni fún Òrúnmìlà ti ó sì ti oko là wá'lé. Ó ni.

Ìbájé owó kò  láṣànú
A d'Ífá fún Òrúnmìlà
L'ọjọ ti ó nr'oko réé lá.
Ó ni Ogbè sá òòò
Ogbe là
Ogbè ló r'oko rèé lá

**Àṣẹ:** Ifá pé kí ó rú'bọ kí ó le ba ni ire lọpọlọpọ.

3. Ifá pé ẹni tí ó dá Ogbè-Sá, Ifá pé yí óò ni olusin lópòlọpọ, ẹbọ ni kó rú.

Gbómú-gbómú Ṣígídí
Ṣígìdì gbómú-gbómú
A d'Ífá fún ọba l'Óyòó
ọmọ amúgba igbin p'èrò loye
gbómú-gbòmú-gbómú

ọba l'Óyóó tí Ifá ńsọ yíí kó ni olusin, ni ó bá pe Awo wípé kí wọn ó bá òun ṣe iwádìí rè ohun ti ó fàá. Wón ní ẹbọ ni ki ó rú, kí ó fi igba ìgbín bọ Odú, wón ni yi óò ni olìsìn. Wón yán án l'ẹbọ. Ó rú'bọ. Wón bá fi igba ìgbín bọ Odú. Kò ì pé ni ọba lóyòó bá bèrè si ni olusin. Alárá fi olùsín ránṣé sí ọba l'Óyòó, Ajerò náà fi ránṣé, Owárángùn náà bèè, bàyìí ni ọba lóyòó bèrè sì ni olusin lópólọpọ. Ó wa nyin Awo, Awo nyin Ifá. Ó ni:

Gbómú-gbómú Ṣígídí
Ṣígìdì gbómú-gbómú
A d'Ífá fún ọba l'Óyòó
ọmọ amúgba igbin p'èrò loye
gbómú-gbòmú ṣígídì
Ṣígìdì gbómú-gbómú
Alárá a ó sin
gbómú-gbòmú ṣígídì
Ṣígìdì gbómú-gbómú
Ajerò a ó sìn
gbómú-gbòmú ṣígídì
Ṣígìdì gbómú-gbómú
Ọwáràngùn a ó sìn
gbómú-gbòmú ṣígídì
Ṣígìdì gbómú-gbómú

4.
Àtíòro Ìbínì
Ògóngó Ìjámó
Àgbìgbò n'Ìwọnràn
Àwọn ni wọn ṣ'awo ọba 'Léyò kanhan
A d'Ífá fún Orídára
Tíí ṣe ẹrú Ọṣòrun àkókò

Orídára tí Ifá nsọ yíí, táláká ni, kò ri ṣe, ojú npon ó gidigidi: erú tún ni Erú tún ni. Ó wá pinu wípé kinni óun lè ṣe, àti wípé ònà wo ni òun lè gbá tí yí óò fi dára fun óun. Ó ni ohun tí òun lè ṣe ní wípé kí òun ó fi ilú sílè lọ si ibòmirán. Ṣùgbón kí òun ó tó lọ, òun ó ṣe iwádìí. Ni ó bá lọ sí òdó àwo. Àwọn Awo ní kí ó tó lọ, ki ó rù'bọ, ki ori rè lè gbe dé ibi tí yí óò tí lá. Ó gbó riru ẹbọ ó rú. Ẹbọ tún, ẹbọ dà ni ó bá gbéra ó lọ, Ígbàtí Orídára Dé ibẹ, ẹsé rè gbe dé ibi tí yí óò tí lá. Orídára bere sí níí yọ. Inú un rè dùn. Í nyin Awo, àwọn Awo nyin Ifá, ó béè l, àwọn Awo wi:

Àtíòro Ìbínì
Ògóngó Ìjámó
Àgbìgbò n'Ìwọnràn
Àwọn ni wọn ṣ'awo ọba 'Léyò kanhan
A d'Ífá fún Orídára
Tíí ṣe ẹrú Ọṣòrun àkókò
Ibi rere t'órí ngbe mi rè, nkó mọ ibè
Èfufu lele lò ti ńgb'átííòro ré 'Bíní
Ibi rere t'órí ńbé mi rè, nkó mọ bé

**Àṣẹ:** Ifá pé ẹni tí ó dá Ogbè-Sá, Ifá pé ẹbọ ni ó rú, kí orí i rè lé ba gbe dé ibi ire ti yíó ti lá.

***Traduccion***

1.
Mano sube cuando ve Iyán (ñame batido) - comida
El dedo gordo del pie es feliz en el avistamiento de los granos frescos
Adivinado para Òrúnmìlà
Quien ocultará a sus hijos en el ático por la muerte.

**Òrúnmìlà** estaba muy incómodo cuando los enemigos libraban la guerra contra él como resultado de lo cual consultó a su Babálawo para la adivinación. Adivinaron para él y le dijeron que hiciera ẹbọ. Le dieron una lista de las cosas requeridas para ẹbọ. Todos los malos mensajes de los enemigos de Òrúnmìlà nunca lo tocaron después de haber hecho el ẹbọ. El ẹbọ también protegió a la esposa e hijos de Òrúnmìlà. Como resultado de la potencia del ẹbọ. Las fuerzas malvadas volvieron a los enemigos. Òrúnmìlà dijo:

Mano sube cuando ve Iyán (ñame batido) - comida
El dedo gordo del pie es feliz en el avistamiento de los granos frescos
Adivinado para Òrúnmìlà
Quien ocultará a sus hijos en el ático por la muerte.
La muerte vino a mi casa y me extrañó
Calabaza vacía, que acaba de perder su tiempo
Todas las fuerzas del mal vinieron a mi casa y me extrañaron
Calabaza vacía, que acaba de perder su tiempo.

2.
Nadie tira dinero aunque esté sucio
Adivinado para Òrúnmìlà
Que será rico de tratar con gente en el pueblo.

**Òrúnmìlà** iba a ir a un pueblo remoto para su trabajo espiritual, pero la perspectiva del viaje lo molestaba. Por lo tanto, estaba dividido entre dos decisiones: ir o no ir. Para obtener una comprensión clara, Òrúnmìlà convocó a su Awo a divinizar por él. Su Awo consultó a Ifá. Le dijeron que hiciera ẹbọ. También le aseguraron que el viaje lo beneficiaría, y que él cosecharía muchos de la recompensa de la aventura. Le dieron una lista de cosas necesarias para ẹbọ. Òrúnmìlà recolecto todo, y su ẹbọ fue hecho para él. Òrúnmìlà partió para el viaje tan pronto como el ẹbọ fue terminado. Llegando al pueblo, la gente con varios problemas comenzó a consultarlo. Òrúnmìlà adivinó y resolvió todos sus problemas. Los que estaban en dificultades antes de Òrúnmìlà llegaron a experimentar cambios positivos poco después del ẹbọ que hizo para ellos. Las mujeres estériles comenzaron a tener hijos. Los enfermos fueron sanados. De hecho todo cambió de malo a bueno para la gente en la aldea. La gente estaba tan feliz por los maravillosos cambios en sus vidas que regaron Òrúnmìlà con muchos regalos caros.

Nadie tira dinero aunque esté sucio
Adivinado para Òrúnmìlà
Que será rico de tratar con gente en el pueblo.
Exclamó, "Ogbè-Sá óóó, que es" Ogbé-enriquece "
Ogè fue a un lugar remoto para conseguir riquezas.

**Àṣẹ̀:** Ifa dice que la persona por la que sale Ogè-Sá está planeando ir de viaje. Ifá dice que el lugar que la persona va a ser beneficioso para él / ella, que la persona no se pierda ninguna de estas cosas buenas que Ifá prevé.

3. Ifá dice que la persona por la que sale Ogbè-Sá tendrá discípulos (o seguidores o hijos de dioses), pero para hacer ẹbọ.

Gbómú gbómú ṣígídí
Ṣígídí gbómú-gbómú
Adivinado para Òyó rey
Quien ofreció 200 caracoles a Óbàtálá por la paz en su dominio
Gbómú gbómú ṣígídí
Ṣígídí gbómú-gbómú

1 Ifá foresees *ire* for the person that Ogbè Ìwòri comes out for. Ifá says the person should make ẹbọ.

Ogbè let me look behind to see if my dog killed *ikún* (a rat)
The dog killed ikún and there was trouble
Divined for the king of Ọ̀yọ́
The day he woke up worried for lack of subjects to worship him.

King of Ọ̀yọ́ divined when his subjects were very few. The Babaláwo told him to make ẹbọ; he made the ẹbọ. After the ẹbọ, the Babaláwo prepared a special Ifá medicine for ọba of Ọ̀yọ́. Not long afterward, ọba of Ọ̀yọ́'s subjects started increasing in number, and life turned for the better for him. Ọba of Ọ̀yọ́ started to thank the Babaláwo, the Babaláwo in turn thanked Ifá saying:

Ogbè let me look behind to see if my dog killed ikún
After the dog killed ikún, trouble began
Divined for the king of Ọ̀yọ́
The day he woke up worried for lack of subjects to worship him
Ifá says multitude of people will worship me
Ìrókò in the forest, people must assemble to worship me.

2. Ifá says the person that Ogbè Wẹ̀hìn comes out for will inherit, or take for ever, something that he borrowed from somebody, probably a friend. Or that the person should never loan anything to a friend or anybody else except something that he can give away. Ifá advises the person to make ẹbọ.

When they have bad *ori* (destinies)
It is somebody's ori (destiny) they borrow when going for important appointments
Divined for Ọ̀rúnmìlà
Who will borrow Èṣù Ọ̀dàrà's ori (head) when he (Ọ̀rúnmìlà) was to receive a chieftaincy award.

Ọ̀rúnmìlà wanted to receive a chieftaincy title. Meanwhile, he was Èṣù Ọ̀dàrà's friend, and Èṣù Ọ̀dàrà has a lucky ori particularly in terms of chieftaincy awards. Because of this fact, Ọ̀rúnmìlà went to Èṣù Ọ̀dàrà and borrowed Èṣù Ọ̀dàrà's ori promising to return the ori to Èṣù Ọ̀dàrà as soon as the chieftaincy conferment was over. Based on this promise, Èṣù gave his ori to Ọ̀rúnmìlà. Ọ̀rúnmìlà was conferred the chieftaincy title. After the ceremony, Ọ̀rúnmìlà refused to return Èṣù Ọ̀dàrà's ori to him. Therefore, Èṣù Ọ̀dàrà went to Ọ̀rúnmìlà and asked Ọ̀rúnmìlà to give him back his ori. Ọ̀rúnmìlà went for divination and asked what he could do to keep Èṣù Ọ̀dàrà's ori to himself forever. The Babaláwo divined and advised Ọ̀rúnmìlà to make ẹbọ. They told him the things to provide for the ẹbọ. Ọ̀rúnmìlà provided the things. The Babaláwo made the ẹbọ and also made a **ṣìgìdì** that looked exactly like an ori (head). They took the ṣigìdi to Èṣù's shrine and left it there. When Èṣù Ọ̀dàrà saw the *ṣìgìdì-head*, he put it on his head, then went immediately to Ọ̀rúnmìlà and told





Ọ̀rúnmìlà that the ori left in his shrine was not his. Ọ̀rúnmìlà said that was the head he borrowed, and that it was the exact one he returned to Èṣù Ọ̀dàrà saying, "I have no other ori to give you, Èṣù Ọ̀dàrà." Disappointed, Èṣù Ọ̀dàrà turned back and left Ọ̀rúnmìlà. With the ẹbọ, Ọ̀rúnmìlà succeeded in keeping Èṣù Ọ̀dàrà's lucky ori to himself for ever. With happiness, Ọ̀rúnmìlà started singing:

Èṣù Ọ̀dàrà keep off my back (twice)
Head taker never take the same head two times
Èṣù Ọ̀dàrà keep off my back.

***Àṣẹ:*** Whomever Ogbè Wẹ̀hìn comes out for must avoid giving out his/her things, except things that he/she is willing or ready to give away. This message is important because the person that borrow something from the client that this Odù Ifá comes out for will not return it.

3.
Should I look back to see if a visitor is coming
Divined for Ẹ̀búrẹ́ (a vegetable)
When going for annual farming event.

Ẹ̀búrẹ́ went for divination to know if the journey he wanted to make would be successful; ẹ̀búrẹ́ said, "Will the place I am going benefit me, will I own land and properties there?" They [Babaláwo] told ẹ̀búrẹ́ to make ẹbọ. They gave him a list for the things for ẹbọ. Ẹ̀búrẹ́ made the ẹbọ. When ẹ̀búrẹ́ got to the farm, he took over the farmland and things became good for him. Ẹ̀búrẹ́ started praising the Babaláwo while the Babaláwo praised Ifá. Ẹ̀búrẹ́ said:

Should I look back to see if a visitor is coming
Divined for Èbùré (a vegetable)
When going for annual farming event
Take over the farmland and its surrounding
Take over the farmland and its surrounding, èbùré!
Take over the farmland and its surrounding

4.

When life is sweet for them
When life is good for them
That is when they start to misbehave
Divined for Onígbìmọ̀
Who was so powerful
That he broke a taboo by taking his wife to the sacred groove.

Onígbìmọ̀ that Ifá is talking about was a very poor man who walked about aimlessly. Even when he worked hard, he never reaped any reward. When he could not bear his destitution any longer, he went to a Babaláwo for divination. The Babaláwo told him that he would be rich, and that he would also become a respectable and honorary person if only he could make ẹbọ. Onígbìmọ̀ disregarded the advice for him to make ẹbọ - he did not make it. Soon after, things changed for the better for Onígbìmọ̀, he became rich and was made a king. In the town that he presided over, a routine ritual called *orò* must be performed every year for peace and tranquility, and as the king of the town, Onígbìmọ̀ must be present during the rituals. Onígbìmọ̀'s wife wanted to go to the sacred groove with him even though it was a taboo for women to go to the groove. For





a long period of time, Onígbìmọ̀ resisted his wife's persuasions to take her to the sacred groove. On a particular year, Èṣù went to Ọ̀rúnmìlà, and asked him if Onígbìmọ̀ made the ẹbọ that he prescribed during his [Onígbìmọ̀'s] destitute years. Ọ̀rúnmìlà told Èṣù that Onígbìmọ̀ did not make the ẹbọ. Therefore, Èṣù convinced Onígbìmọ̀ to take his wife to the sacred groove when the wife persuaded the husband once again. With Èṣù's command, Onígbìmọ̀ forgot the taboo and consented to his wife's demand. Onígbìmọ̀ instructed his palace messengers to weave a big basket, big enough to contain a human being, and to make two holes through which a person could view the outside. The servants made the basket. On the night that preceded the ritual performance, Onígbìmọ̀ took his wife to the sacred groove and hid her inside the basket. Meanwhile, the king must lean his foot on a basket during ritual performances at the groove.

On the day of the ritual, all Awo were present, and the ritual began. Onígbìmọ̀'s wife, hiding inside the basket, saw everything from the beginning of the ritual until it got to the point when the Awo had to throw *obì àbàtà* (kolanuts) as the rule demanded. When the *obì àbàtà* were thrown, they came up negative. Immediately, the atmosphere in the sacred groove became tense because it never happened that way. Digging for answers to the negative reading, the Awo consulted Ọ̀rúnmìlà, Ọ̀rúnmìlà told them that Onígbìmọ̀'s wife was inside the basket under the oba's foot. Immediately, the Babaláwo sang Ifá song saying:

We called on itá, itá did not answer
We called on ìrẹ̀lẹ̀, ìrẹ̀lẹ̀ did not answer
We called pákòkò, pákòkò did not answer

Open the king's foot [box] support.

They opened the basket and inside the basket was the queen. At that time, a taboo breaker and his/her accomplice usually suffer the same fate together. Therefore, when the king broke the taboo, they killed him and also killed the queen. It was after this that things went well at the sacred groove.

*Àṣẹ:* Ifá tells us never to break a taboo, a law, or a regulation. It also tells us not to disregard Ọ̀rúnmìlà's injunctions.



# Ẹ̀ta (3)

## Ogbè-Dí

1.

Òní wiriwiri Ogbè-Di
Ọ̀la wiriwiri Ogbè-Di
Ẹyẹ nlá ní fi apá sọ̀gan
Òkú ọ̀pẹ̀ nii hù ọmú l'ọ̀rùn
A d'Ifá fún Olúkònjọ
Ti yi óò ma ṣ'òwò ẹ̀jẹ̀ l'órọṣù l'órọṣù
Wọ́n ni kó rú'bọ , kó lè baà d'ọlọ́mọ.

Olúkònjọ tí Ifá ńsọ yìí, obinrin ni. Kò rí ọmọ bí, oṣooṣù nii maá ri ẹ̀jẹ̀, tíi maá ṣe ǹkan oṣù. Ojú ọmọ ńpọ gidi. Ó di ọjọ́ kan, ó mú ééjì kún ẹ̀ẹ̀ta, ó lọ oko awo. Wọ́n dá'Fá, wọ́n ní yì óò bí'mọ wípé ẹbọ ni kó rú. Yi óò di ọlọ́mọ rere. Wọ́n yàn án l'ẹ́bọ; ó rú'bọ. Lẹ́hin irúbọ, wọ́n ṣe Ifá fún, ó jẹ ẹ́. Kò pẹ́, àkókò tíi maá rí ǹkan oṣù dé, ó retí wípé bóyá òun ó rí, ọjọ́ kìnní, ọjọ́ kejì, títí kò rí ǹkan oṣù; ó ti di oyún. Ó di àkókò ìbímọ, ọmọ ló fi bí. Bí Olúnkònjọ ṣe bẹ̀rẹ̀ sí ní bí'mọ nìyí. Ó ní bẹ́ẹ̀ l'àwọn awo òun wí:

Ọni wiriwiri Ogbè-Di
Ọla wiriwiri Ogbè-Di
Ẹyẹ ńlá ní f'apá sọgan,
Okú ọ̀pẹ́ ni i hù ọmú l'ọ̀rún,
A d'Ífá fún Olúkọ̀njọ
Ti yí óò ma ṣ'òwò ẹ̀jẹ̀ l'óroṣù l'óroṣù
Wọ́n ní kí ó rú'bọ, kó lè ba à d'ọmọ
Òwò ẹ̀jẹ̀ ta ńṣe l'óroṣù yìí,
Ẹ jẹ́ ká rú'bọ kó d'ọmọ.

2.
Ogbè-Di
Ogbè-Di
Èmi ò f'ọ̀rọ̀ mi ṣ'àwàdà
Èmi ò f'ọ̀rọ̀ mi sayanrun
A d'Ífá fún dùndún
Tí ńlọ s'òde Ọ̀yọ́.

Ní ayé àtijọ́, ní igbàtí ọba l'Ọ́yọ̀ọ́ fẹ́ yan ìlù tí yí óò ma lu ààyò, ìlù tí yí óò gbayì tí wọ́n ó ma lù fún ọba l'Ọ́yọ̀ọ́. Ní ó bá ránṣẹ́ pe gbogbo ìlù sí Ọ̀yọ́. Kí ọjọ́ tó pé ni dùndún bá gbéra, ó lọ s'óko awo, ó bèrè bí òun ó ṣe gbayì ní Òde Ọ̀yọ́, tí wọn yó fi yan òun láàyò lọ́hùn ún, ló wa dá Ifá sí. Wọ́n ní yí óò gbayì, wọn ó si yàn án láyò, wípé ebọ ni kí ó rú. Wọ́n yàn án l'ẹ́bọ; ó rú'bọ. Wọ́n ṣe Ifá fún. Ọjọ́ tí wọ́n dá pé, gbogbo ìlù lọ s'Òde Ọ̀yọ́, ní Ọba l'Ọ́yọ̀ọ́ bá ńpè wọ́n ní ọ̀kọ̀ọ̀kan láti wá má a dún. Bàtá bọ́ síbẹ̀, gàngan àti bẹ̀ẹ̀ bẹ̀ẹ̀ lọ bọ́ sí. Ó kan dùndún, gẹ́gẹ́bí irúbọ Ifá, ìlù dùndún ni ó dún l'étí ọba l'Òde Ọ̀yọ́. Ìdí rẹ̀ nìyí tí ó fi jẹ́ wípé dùndún ni wọ́n ma ńlù fún Ọba l'Ọ́yọ̀ọ́. Ìlù dùndún ni Aláàfin Ọ̀yọ́ jó.





*Àṣẹ:* Ifá pé ẹni tí ó dá Ogbè-Di, kí ó rú'bọ kí ó lè baà nìyí láàárín àwọn ẹgbẹ́ ẹ rẹ̀ yòkù.

3.
Ogbè-Di
Ogbè-Di
A d'Ífá fún àdàbà ṣùṣù
Tí yí óò ma ná'jà kiri ayé
Wọ́n ní kí ó rú'bọ àṣeyọrí.

Àdàbà ni Ifá ńsọ̀rọ̀ nípa rẹ̀. Àdàbà tí Ifá wí yìí kò ní ibùjókòó; kò sí ifọkànbalẹ̀ fún, ló bá lọ oko awo. Wọ́n ní kó rú'bọ àṣeyọrí, wọ́n yàn án l'ẹ́bọ. Àdàbà fi gbígbọ́ ṣe àìgbọ́, kò rú'bọ. Bí àdàbà ṣe di aláìní ibùgbé nìyí, tí kò sì ní àṣeyọrí kankan, tí a bá rí àdàbà níbíyìí l'ónìí, ibòmíràn ni a ó ti rí l'ọ̀la. Ó ní:

Ogbè-Di
Ogbè-Di
A d'Ífá fún àdàbà *ṣùṣù*
Tí yí óò ma ná'jà kiri ayé
Òun kiri dé Ẹ̀gbá ajá
Òun kiri dé ẹsẹ̀ adìẹ
Ó ní òun àdàbà kelúkelú
Ó ní kò sílẹ̀ t'òun kò dé rí.

*Àṣẹ:* Ifá pé kí ẹni tí ó dá Ogbè-Di kí ó má ṣe àìgbọ́ràn, kí ó sì rú'bọ kí ó lè ba ní ibùjókòó rere.

4. Ifá pé òun pé ire ifọkànbalẹ̀ fún ẹni tí ó dá Ogbè-Di. Ifá pé ẹbọ ni kó rú.

Ọ̀rọ̀ jáhàrámò tẹ̀sùn
A d'Ifá fún Ọ̀rúnmìlà
Tí yí òò sin'kú àìsinmi iyá Èṣù Ọ̀dàrà.

Ọ̀rúnmìlà ní ó fura nígbàtí ọkàn rẹ̀ kò balẹ̀, tí kò ní ìsinmi. Ní ó bá pe àwọn Awo, ó gbé òkè ìpọ̀nrí rẹ̀ ka'lẹ̀, àwọn Awo bá bèrè. Wọ́n ní Ọ̀rúnmìlà yí òò ní ìsinmi, wípé kí ó lọ sin'kú àìsinmi iyá Èṣù Ọ̀dàrà, kó ṣe ètùtù fún iyá Èṣù Ọ̀dàrà. Ní Ọ̀rúnmìlà bá ṣe ètùtù yìí. Ọkàn rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí ní balẹ̀. Ó bẹ̀rẹ̀ sí ní ìsinmi. Ó ńyin Awo, àwọn Awo ńyin Ifá. Ifá nyin Elédùmarè ọba l'ọ̀run:

Ọ̀rọ̀ jáhàrámò tẹ̀sùn
Ló d'Ifá fún Ọ̀rúnmìlà
Ní'jọ́ tí yí òò sin'kú àìsinmi iyá Èṣù Ọ̀dàrà.

*Àṣẹ:* Ifá ní òkú kan òò kú fún eléyìun tó yẹ kí ó ná'wó níbẹ̀. Kó ṣe sààrà fún òkú nàà kó lè ní ìsinmi. Ifá pé kó fi ajá kan rú'bọ f'Èṣù. Ọ̀kẹ́ mẹ́jọ (₦4.00).





***Translation:***

1.
Today Ogbè-Di
Tomorrow Ogbè-Di
Big bird has the ability to fly higher
Dead palm tree saps juice
Divined for Olúkònjọ
Whose monthly menstruation never stopped
She was asked to make ẹbọ so that she could bear children.

Olúkònjọ that Ifá speaks about was a woman who had no children, her monthly menstrual cycle ran on continuously. She was very desperate for children. One day, she decided to see a group of some Babaláwo for divination. The Babaláwos consulted Ifá on her behalf, and told her that she would have children, but to make ẹbọ. The Babaláwo told her what the ritual things were. She made the ẹbọ. After the ẹbọ was made, the Babaláwo prepared a special Ifá medicine for her to use. Some weeks later, it was time for her menstruation, and as usual, she expected to see the sign. First day, second day, some weeks later, no sign of her menstruation. It soon dawned on her that she was pregnant. When it was time for delivery, she had a bouncing, beautiful, and healthy baby. Thereafter, she had many more children, and she reminiscenced saying, "Hmmm, the Babaláwo said I would have children."

Today Ogbè-Di
Tomorrow Ogbè-Di
Big bird has the ability to fly higher
Dead palm tree saps juice

Divined for Olúkónjọ
Whose monthly menstruation never stopped
She was asked to make ẹbọ so that she could bear children
This continuous monthly menstrual cycle
Let us make ẹbọ so that it brings children.

2.
Ogbè-Dí
Ogbè-Dí
I do not joke about my life
I do not deceive myself either
Divined for dùndún (talking drum)
When going to Ọ̀yọ́ town.

In the olden days when Ọ̀yọ́ king wanted to choose a special and melodious dùndún drum for use in his palace, he sent messages out to *all* dùndún drums in his county to assemble in his palace in Ọ̀yọ́. Before the day of the assemblage, dùndún drum went to his Babaláwo for divination. Dùndún's concern that he posed to Ifá was how he could be chosen as the best drum when he got to the meeting in Ọ̀yọ́. They [the Babaláwo] assured dùndún that he would be chosen the best, but that he should make ẹbọ. They gave dùndún a list of ritual things to buy. Dùndún made the ẹbọ. They gave dùndún a special Ifá medicine after the ẹbọ. On the appointed day, all *drums* assembled in Ọ̀yọ́ town. Then ọba started calling the *drums* one after the other to come out and perform. Bàtá drum performed, gángan drum performed, other drums performed also until it got to dùndún's turn, By virtue of the ẹbọ and the special Ifá medicine made for dùndún, its performance





was the most pleasing to ọba of Ọ̀yọ́. This is the reason why dùndún is the drum beat for ọba of Ọ̀yọ́. Aláàfin (Ọba of Ọ̀yọ́) has since then been dancing to dùndún drum beats.

Ifá says whomever Ogbè-Dí comes out for must make ẹbọ so that he/she can outshine his/her mates/colleagues.

3.
Ogbè-Dí
Ogbè-Dí
Divined for a group of doves
That will move about aimlessly around the world
They were advised to make ẹbọ for success of their endeavors.

Ifá is talking about a dove - personified. The dove that Ifá talks about had no permanent home, he had no peace of mind either. He went for a divination. He was told to make ẹbọ for success of his endeavors. They [the Babaláwos] gave him a list of the things needed for ẹbọ. Dove did not make the ẹbọ. As a result of this failure, dove did not have a home and still does not have. Dove lacks success too. "If dove is seen here today, it will be seen somewhere else tomorrow", He said:

Ogbè-Dí
Ogbè-Dí
Divined for a group of doves
That will move about aimlessly around the world
"I travelled all over Ẹ̀gbáland
I travelled all over Ìjẹ̀ṣàland

I, the restless dove
There is no where in the world that I had not been to.''

*Àṣẹ:* Ifá says whomever Ogbè-Di comes out for should never disobey orders, sanctions, or rules that have been set forth. The person must also make ẹbọ so that he/she can have a permanent place of abode.

4. **Ifá** says, ''peace of mind'' for whomever Ogbè-Di comes out for. Ifá says make ẹbọ.

Fairy's leaf-mat
Divined for Ọ̀rúnmìlà
Who will bury **restlessness**, Èṣù Ọ̀dàrà's mother.

Ọ̀rúnmìlà thought deeply when he was troubled and lacked peace of mind, and when he was also restless. He went to his Babaláwo for divination. The Babaláwo consulted Ifá and told Ọ̀rúnmìlà that he would have peace of mind, but that he should make arrangement to bury *Àìsinmi* **(restlessness)** who was Èṣù Ọ̀dàrà's mother; he was told to make *ètùtù* for her also. Ọ̀rúnmìlà buried *Àìsinmi*, and also made the etùtù; thereafter, he enjoyed peace of mind. Ọ̀rúnmìlà, therefore, thanked the Babaláwo while the Babaláwo thanked Ifá, and Ifá thanked Elédùmare, king in heaven.

Fairy's leaf-mat
Divined for Ọ̀rúnmìlà
Who will bury **restlessness**, Èṣù Ọ̀dàrà's mother.





*Àṣẹ:* Ifá says there is a burial that the person who this Odù comes out for must participate in actively and financially. The person should also make *sàárà* (generous feeding or gift to the needy) on behalf of the dead person so that the person making the ẹbọ will enjoy peace of mind.

**Ẹbọ:** Ifá says make an offering of *ajá (dog)* to Èṣù plus $4.00.

# Ẹ̀rin (4)

## Ogbè-'Rosùn

1. Ifá pé ẹni tí ó dá Ogbè-Rosùn pé kí ó rú'bọ kí ó lè ba bí'mọ lọ́pọ̀lọpọ̀.

Mo rú wẹ́rẹ́
Mo tù wẹ́rẹ́
A d'Ifá fún Òsùngàgàgà
Tí ńsunkún p'óun ó bí'mọ.

Òsùn tí Ifá ńsọ yìí, obìnrin ni l'áyé àtijọ́. Ojú ọmọ ńpọ́n o, ló bá mú ẹ́ẹ̀jì kùn ẹ̀ẹ́ta ló lọ oko Awo, ǹjẹ́ òun lè bí'mọ ló dá Ifá sí. Wọ́n ní yí òò bí'mọ, ẹbọ ni kó rú. Wọ́n yàn án l'ẹ́bọ, ó rú'bọ. Kò pé Òsùn bẹ̀rẹ̀ sí ńbí'mọ. Ó sì di ọlọ́mọ púpọ̀. Ẹnu tó yà kótó, orin awo ló bọ sí lẹ́'nu, ó ní:

Mo rú wẹ́rẹ́
Mo tù wẹ́rẹ́
Òsùngàgàgà ló bí'mọ báwọ̀nyìn
Mo rú wẹ́rẹ́
Mo tù wẹ́rẹ́.



2. Ifá pé òun yí òò ṣẹ́'gun ọ̀tá fún ẹni tí ó dá Ogbè-Rosùn. Ifá pé ẹbọ ni kó rú. Ifá pé òun yí òò ba ṣẹ́'gun ọ̀tá lọ́pọ̀lọpọ̀.

Àdó ńlá a bídí kotopo
A d'Ifá fún Eléríwo
A bù fún Ẹlẹ̀da
L'ọ́jọ́ tí àwọn méjèèjì jọ ńṣọ̀tá.

Eléríwo pẹ̀lú Ẹlẹ̀da tí Ifá ńsọ yìí, ọ̀tá ni àwọn méjèèjì, onìṣégùn tí ó gbónà gìdìgìdì ni Eléríwo; nídìí èyí, omínú ńkọ Ẹlẹ̀da, ni Ẹlẹ̀da mú ẹ́ẹ̀jì kùn ẹ̀ẹ́ta ó lọ sí oko awo. Ó bèrè l'ọ́wọ́ Ọ̀rúnmìlà bí òun yí ó ti ṣe ṣẹ́'gun Eléríwo. Wọ́n ní ẹbọ ni Ẹlẹ̀da ó rú. Awo yàn án l'ẹ́bọ, Ẹlẹ̀da rú'bọ. Ẹbọ fín, ẹbọ dà. Eléríwo tún bẹ̀rẹ̀ sí ní sa òògùn sí Ẹlẹ̀da. Ìrúbọ Ẹlẹ̀da òò dá òògùn Eléríwo padà sí ọ̀dọ̀ rẹ̀ ni Eléríwo bá kú. Ó fi orí ara rẹ̀ rù òògùn ara rẹ̀. Ẹbọ ni Ẹlẹ̀da fi ṣẹ́'gun Eléríwo. Nígbàtí ó ṣẹ́'gun tán, ó ńyin Babaláwo, Babaláwo ńyin Ifá, ó ní:

Àdó ńlá a bí'dí kotopo
A d'Ifá fún Eléríwo
A bù fún Ẹlẹ̀da ò l'òògùn l'ọ́wọ́
Ó wá fi ẹbọ Ogbè-Rosùn pa Eléríwo dànù.

3. Ifá ní ẹni tí ó dá Ogbè-Rosùn Ifá pé kí ó rú'bọ orìyìn. Ifá pé eléyiun tí ńṣe ǹkan tẹ̀lẹ̀ tí wọn kò sí fi yìn in. Ifá pé kí ó rú'bọ àṣeyìn. Ifá pé ẹbọ ni kó rú.

Erin nìí fi ibi mími ṣ'ọlá
Ìirà ò ní jọ̀bọ̀ tó ẹfọ̀n
Àyìnká awo ayé lo d'Ifá fún ayé
Wọ́n ní k'àyé ó rú'bọ kí wọ́n ó lè ma s'ọ̀rọ̀ ọ rẹ̀ ní rere.

Ayé ti Ifá ńsọ yìí, tí ó bá ṣe oore, ibi ni wọ́n ma ńfi ṣu. Ni ọ̀rọ̀ rẹ̀ kò ni ojútumọ̀. Ó wá mú ẹ̀ẹ́jì kún ẹ̀ẹ́ta, ó lọ sí oko awo. Wọ́n lè ma yìn òun báyìí ni ó dá'Fá sí. Wọ́n ní ẹbọ ni kó rú. Wọ́n ni won ó ma yìn ín pẹ̀lú gbogbo oore tí ó bá ṣe fún wọn. Wọ́n rú'bọ fún Ayé. Ẹbọ fín, ẹbọ dà, gbogbo ẹni tí ó bá wá ti ṣe oore fún ni ó wá ma yìn ín. Ni inú rẹ̀ dùn, ó ńjó, ó ńyọ̀, ó ńyin Babaláwo, ni Babaláwo ki Ifá:

Erin níí fi ibi mimi ṣ'ọlá
Ìirà ó ni jọ̀bọ̀ tó ẹfọ̀n
Àyinkà awo ayé
Ló d'Ifá fún ayé
Wọ́n ni k'àyé ó rú'bọ ki wọ́n lè ma s'ọ̀rọ̀ ọ rẹ̀ ni rere
Àyinká làá yin ayín
Ẹnu ti ẹ mú yin mi
Ẹ má má pádà
Àyinká làá yin ayín.

4.

Àlùkinrinjin awo ilé Ọ̀rúnmìlà
Ló d'Ifá fún Ọ̀rúnmìlà
Wọ́n ni ki Baba ó rú'bọ
Ki ibi ó má ba à f'ẹsẹ̀ wọ'lé e rẹ̀.

Ọ̀rúnmìlà ni àwọn ọ̀tá ńbá jà ni àkókò yìí, tí wọ́n ńrán àwọn ajogun ibi sí Ọ̀rúnmìlà. Ni Ọ̀rúnmìlà bá funra wipé àwọn ọ̀tá ńrán ajogun ibi sí òun ni ó bá gbe òkè ìpọ̀ori rẹ̀ ka'lẹ̀. Ó pe àwọn Awo, wọ́n dá'Fá fún Ọ̀rúnmìlà, wọ́n yàn án l'ẹ́bọ. Ọ̀rúnmìlà rú'bọ. Ẹbọ tù bá, ó tù ṣẹ. Wọ́n ṣe Ifá fún Ọ̀rúnmìlà. Wọ́n ṣe Ifá fitilà iṣẹ́gun fún Ọ̀rúnmìlà tí yi óò ma tàn ní alaalẹ́. Òru ọjọ́ kan ti Ọ̀rúnmìlà tàn án, ó ńfi àdá Òrìṣà lu'lẹ̀, ó dá'rin báyìí:





Òru ọjọ́ kinnii àwọn ajogun ibi wá
Wọ́n rí inà ninú ilé Ọ̀rúnmìlà, wọ́n si ńgbọ̀ ohùn
Òru ọjọ́ keji bẹ́ẹ̀. Ìgbàtí ó di ọjọ́ kẹta, wọ́n ò wá mọ́.

Báyìí ni Ọ̀rúnmìlà ṣẹ́'gun àwọn ọ̀tá rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ajogun ibi. Ifá pé òun yí óò bá ẹni tí ó dá Ogbè-Rosùn ṣẹ́'gun.

*Àṣẹ:* Ifá pé ẹbọ ni kó'rú.

***Translation:***

1. Ifá says the person that Ogbè-Rosùn comes out for must make ẹbọ for child blessings.

I make ẹbọ easily
I make ètùtù easily
Divined for Òsùngàgàgà
Who was disillusioned because she had no children.

Osùn that Ifá is talking about was a woman in ancient time. She was barren; therefore, she went to her Babaláwo for divination. Her question to Ifá was, "Will I ever have children?" They [the Babaláwo] assured her that she would have children, that she should make ẹbọ. They gave her a list of the things for ẹbọ. She made the ẹbọ. Soon after making the ẹbọ, she started having children. She became the mother of many children. She started singing, saying:

I made ẹbọ easily
I made ètùtù easily
Òsùngàgàgà is the mother of plenty children
I made ẹbọ easily
I made ètùtù easily.

2. Ifá says victory for whomever Odù Ifá Ogbè Ìrosùn comes out for. Ifá says He will make the person victorious over his/her enemies and over all adversaries.

Big gourd with narrow base
Divined for Eléríwo
Divined same for Ẹlẹda
The day the two of them became arch enemies.

Eléríwo and Ẹlẹda that Ifá is talking about were arch enemies. Eléríwo was a very powerful herbalists. Because of this, Ẹlẹda was scared and concerned for his life. The fear drove him to his Babaláwo for divination. He asked Ifá what he could do in order to be victorious over Eléríwo. They [the Babaláwo] told Ẹlẹda to make ẹbọ. They told him all the things he needed to provided. Ẹlẹda made the ẹbọ. Ẹbọ manifested. Soon after, Eléríwo started sending spells to Ẹlẹda again. By virtue of the ẹbọ that Ẹlẹda made, the spells did not affect Ẹlẹda, instead, they went back to Eléríwo, and Eléríwo died. Eléríwo died by his own sword. Ẹlẹda's ẹbọ made him victorious. After this victory, Ẹlẹda started praising the Babaláwo while the Babaláwo praised Ifá saying:





Big gourd with a narrow base
Divined for Eléríwo
Divined same for Ẹlẹda who had potent medicine
He killed Eléríwo by virtue of ẹbọ from Ogbè-Rosùn.

3. Ifá says the person that Ogbè-Rosùn comes out for should make ẹbọ to earn a deserved respect for his/her kindness. Ifá says the person had never been *thanked* or *given recognition* for past good deeds. Ifá recommends ẹbọ to correct the situation.

Elephant triumphs in its bigness
Ant's size can never be compared to that of a buffalo
Praises-everywhere, diviner for *ayé* (earth)
Was the one that divined for *ayé*
*Ayé* was asked to make ẹbọ so that people will say good things about her.

*Ayé* that Ifá is talking about was a kind person who was never appreciated for all her good deeds, instead, all she received was bad mouthing. When *ayé* could not take the bad mouthing any longer, she went to her Babaláwo for divination. She asked Ifá if she could ever be thanked and praised for her good deeds. They assured her that she would receive praises for her good deeds, but she should make ẹbọ. Ẹbọ was made for *ayé*. The ẹbọ manifested, and all the people that *ayé* helped before and after the ẹbọ started to thank and praise her. She was very happy; she then started dancing and merrying, praising the Babaláwo while the Babaláwo praised Ifá.

Elephant triumphs in its bigness
Ant's size can never be compared to that of a buffalo
Praises-everywhere, diviner for *ayé* (earth)
Was the one that divined for *ayé*
*Ayé* was asked to make ẹbọ so that people will say good things about her
Ayin *(praise)* is praised everywhere
The very mouth with which people praised me
People should not turn around and use the mount to say bad things about me
Àyin *(praise)* is praised everywhere.

4.
Àlùkinrinjin, a diviner in Ọ̀rúnmìlà's house
Divined for Ọ̀rúnmìlà
Baba [Ọ̀rúnmìlà] was told to make ẹbọ
To prevent any bad thing from entering his house.

Enemies were waging war on Ọ̀rúnmìlà and were sending evil forces to him also. Ọ̀rúnmìlà felt that enemies were sending evil forces to him; therefore, he called his awo for divination. Ọ̀rúnmìlà's awo divined for him and told him to make ẹbọ. Ọ̀rúnmìlà made the ẹbọ. Ẹbọ manifested. They [the awo] made a special Ifá medicine on a fitílà (traditional weak/palm oil lamp) for Ọ̀rúnmìlà and told him to light the fitílà every night. One night when Ọ̀rúnmìlà lighted the fitílà, beating the floor with his *àdá Òrìṣà* (Ọbàtálá's machete), he started singing:





The first night the evil forces came
They saw light in Ọ̀rúnmìlà's house as well as heard a voice
The second night the evil forces came
They saw light in Ọ̀rúnmìlà's house as well as heard a voice
Then on the third night, the evil forces stopped coming to Ọ̀rúnmìlà's house.



**Òsùn Ifá** (Ifá staff)

# Àrún (5)

## Ogbè Ọ̀wọ́nrín (Ogbè-Wúnlé)

1. Ifá ni ẹni ti ó dá Ogbè Wúnlé ki ó rú'bọ ki àrùn ki ó bá ma à ṣe àwọn ọmọ rẹ̀. Ifá pé ki eléyiun ó má ṣe àigbọ́ràn. Ifá pé ẹbọ ni kó'rú.

Ìtẹ́ gúdúgbè
Ló d'Ifá fún Elédiró.

Elédiro ti Ifá ńsọ yìí, adiyẹ ni. Ni ayé àtijọ́, àrùn ori ńṣe àwọn ọmọ rẹ̀, ni ó bá lọ bèrè l'ọ́dọ̀ Ifá. Àwọn Awo ní kí ó rú'bọ; wọ́n yàn án l'ẹ́bọ. Ṣùgbọ́n ó fi gbígbọ́ ṣe aláìgbọ́, kò rú'bọ. Ni àrùn àwọn ọmọ rẹ̀ bá tún pọ̀ si. Báyìí ni àrùn ori yìí ṣe ńpa àwọn ọmọ rẹ̀. Ṣùgbọ́n ki ó tó di wípé wọn ó ma fi ọrùn yí'lẹ̀, wọn ó ma sọ wípé, iyá àwọn ni kò ṣ'ẹbọ. Ọ̀kọ̀ọ̀kan méji kò ṣ'ẹbọ; ẹ̀jẹ̀ẹ̀jẹ méje méje.



2.

Ayegbe ihin
Ayegbe ọ̀hún
A d'Ifá fún érinlójọ ẹranko
L'ọ́jọ́ ti wọ́n ńlọ rèé fẹ́ Mọlújanjan ọmọ olúigbó
Ayegbe ọ̀hún
A d'Ifá fún Oorẹ ṣẹgi-ṣẹgi
L'ọ́jọ́ tó ńlọ rèé fẹ́ Mọlújanjan ọmọ olúigbó.

Mọlújanjan ti Ifá sọ yìí, ọmọ olúigbó nií ṣe. Ó tó àkókò ti yi óò ni ọkọ, ni àwọn ẹranko bá ńjà l'óri i rẹ̀. Ẹkíní wípé òun l'òun ó fẹ, èkéjì náà wípé òun ni òun yó fẹ. Àwọn ẹranko bí erin, ẹfọ̀n, àgbọ̀nrín, oorẹ. Ni olúigbó bá ni òun ó ṣe idánwò fún wọn. Ẹni ti ọmọ òun bá dimọ́, tó gba ọsàn l'ọ́wọ́ rẹ̀ ni yí óò fẹ. Ni àwọn ẹranko yókù bá lọ dá'Fá. Wọ́n ni ki wọn ó rú'bọ. Oorẹ nikan ló rú'bọ. Àwọn ẹranko kò rú'bọ. Wọ́n ni bí ẹni gbogbo yi óò tilẹ̀ bá àwọn fi ori gbá'ri, oorẹ lásán lásán wá ni yi óò ma bá àwọn fi ori gbá'ri. Erin ni "Nibiti mo wà," ẹfọ̀n náà ni "Nibiti mo wà," àgbọ̀nrín náà wí bẹ́ẹ̀. Wọ́n l'áwọn ó rú'bọ. Ni oorẹ bá ra ọsàn, ọsàn ti oorẹ rà ni àwọn Awo bá ṣe Ifá si. Gbogbo ẹranko dá'jọ́, ọjọ́ pé. Gbogbo wọ́n bá péjọ; ni wọ́n bá ńkọrin. Erin ló kọ́kọ́ yọ'jú, ó k'ọrin wípé:

Mọlújanjan wá gb'ọsàn o, àlújanjan-kíjan (èèméjì)
Èmi erin má de *asalu* (olórí igbó), àlújanjan-kíjan
Ẹfọ̀n l'ọmọ ọ̀dọ̀fin, àlújanjan-kíjan
Àgbọ̀nrín l'ọmọ abilà o, àlújanjan-kíjan
Oorẹ l'ẹrú àwa, àlújanjan-kíjan
Mọlújanjan wa gb'ọsàn o, àlújanjan-kíjan.

Mọlújanjan kò dáhùn, kò gba ọsàn l'ọ́wọ́ erin. Ní ẹfọ̀n bá bọ́ síbẹ̀, ni òun náà bá bẹ̀rẹ̀ sí ni k'ọrin:

Mọlújanjan wá gb'ọsàn o, àlùjanjan-kíjan (èèméjì)
Erin ni olórí igbó, àlùjanjan-kíjan
Èmi ẹfọ̀n l'ọmọ ọ̀dọ̀fin, àlùjanjan-kíjan
Àgbọ̀nrín l'ọmọ abilà o, àlùjanjan-kíjan
Oorẹ l'ẹrú àwa, àlùjanjan-kíjan
Mọlújanjan wa gb'ọsàn o, àlùjanjan-kíjan.

Mọlújanjan kò dáhùn, kò gba ọsàn l'ọ́wọ́ ẹfọ̀n. Ní àgbọ̀nrín bá bọ́ síbẹ̀, ni òun náà bá bẹ̀rẹ̀ sí ni k'ọrin:

Mọlújanjan wá gb'ọsàn o, àlùjanjan-kíjan (èèméjì)
Erin ni olórí igbó, àlùjanjan-kíjan
Ẹfọ̀n l'ọmọ ọ̀dọ̀fin, àlùjanjan-kíjan
Èmi àgbọ̀nrín l'ọmọ abilà o, àlùjanjan-kíjan
Oorẹ l'ẹrú àwa, àlùjanjan-kíjan
Mọlújanjan wá gb'ọsàn o, àlùjanjan-kíjan.

Mọlújanjan kò dáhùn, kò gba ọsàn l'ọ́wọ́ àgbọ̀nrín. Ní oorẹ bá bọ́ síbẹ̀, ni òun náà bá bẹ̀rẹ̀ sí ni k'ọrin:

Mọlújanjan wa gb'ọsàn o, àlùjanjan-kíjan (èèméjì)
Erin ni olórí igbó, àlùjanjan-kíjan
Ẹfọ̀n l'ọmọ ọ̀dọ̀fin, àlùjanjan-kíjan
Àgbọ̀nrín l'ọmọ abilà o, àlùjanjan-kíjan
Èmi oorẹ kii ṣ'ẹrú ẹ̀yin, àlùjanjan-kíjan
Mọlújanjan wá gb'ọsàn o, àlùjanjan-kíjan.





Ni Mọlújanjan bá sáré sí oorẹ, ni ó wípé, "Ìyẹn ni wípé ìwọ kii ṣe ẹrú àwọn wọ̀nyí." Oorẹ ni òun kii ṣe ẹrú u wọn.

Báyìí ni oorẹ fẹ́ Mọlújanjan ọmọ olúìgbó nipa irúbọ Ifá àti iyẹ Ifá ti wọn pè sí ọsàn. Ó jẹ́ ki ọsàn ti oorẹ wọ Mọlújanjan l'ójú. Báyìí ni oorẹ fẹ́ Mọlújanjan mọ́ àwọn ẹranko yókù l'ọ́wọ́.

*Àṣẹ:* Ifá yìí kọ́ wa pé ki a má fi ojú tẹ́mbẹ́lú ẹni kéji i wa. Ifá pé ẹni ti ó dá Ogbè-Wúnlé ki ó rú'bọ ki ó lè bá gbayì l'ọ́wọ́ àwọn iyókù rẹ̀.

3.
Egbirin l'awo aja ile
A d'Ifá fún Yemọ̀ọ̀
Ti i ṣe obinrin Òrìṣà
L'ọ́jọ́ ti ó ńsunkún pé òun kò bí'mọ.

Yemọ̀ọ̀ ti Ifá ńsọ yìí, obinrin ni ni ayé àtijọ́. Ó ṣe tití kò ri ọmọ bí; ojú ọmọ pọn púpọ̀. Ni ó bá mú èéjì kún ẹ̀ẹ́ta ó lọ sí oko awo. Ifá pé kó rú'bọ, yi óò bí'mọ púpọ̀. Wọ́n yàn án l'ẹ́bọ. Yemọ̀ọ̀ rú'bọ. Olódùmarè si gbọ́ ohùn un rẹ̀, ó sì fi ọmọ mẹ́rindinlógún ránṣẹ́ sí láti òde ọ̀run. Báyìí ni Yemọ̀ọ̀ di ọlọ́mọ. Ó si ńyin Awo, àwọn Awo ńyin Ifá, Ifá si ńyin Olódùmarè.

*Àṣẹ:* Ifá pé ẹni ti ó dá Ogbè-Wúnlé ki ó rú'bọ ọmọ lọ́pọ̀lọpọ̀; ki ó si má fi eti pàlàbà ẹbọ náà. Ifá pé òun pé ire ọmọ fún eléyiun.

4. Ifá pé ẹni tí ó dá Ogbè-Wúnlé kí ó rú'bọ, kí wọ́n bá ma gba ọkọ mọ l'ọ́wọ́, tàbí gba ìyàwó o rẹ̀. Ifá pé kí eléyiun kí ó ma dẹ́jàá.

Inú ilé là á hun
Kí a tó ma hun òde
A d'Ifá fún porogodo
Tíí ṣe obinrin àkókó.

Porogodo tí Ifá so yìí, obinrin àkókó ní í ṣe. Àkókó fura wípé wọ́n fẹ́ gba ìyàwó òun ni ó bá lọ ṣe àyẹ̀wò. Wọ́n ni ẹbọ ni kí àkókó ó rú. Ṣùgbọ́n àkókó kò rú'bọ; ó ni kàkà kí òun ó rú'bọ, ogbọ́n ni òun ó ta. Ni àkókó bá lọ fi ẹnu gbẹ́ ihò sí ara igi kan, ni ó bá lọ gbé ìyàwó rẹ̀ pamọ́ sí inú ihò igi yìí, ni ó bá di i pa. Ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí àìgbọ́nran àti ẹ̀jà dídá, àkókó padà dé ibi igi kò mọ ojú ibití ó gbé ìyàwó rẹ̀ sí mọ. Láti àkókò yìí ni àkókó tí ma á fi ẹnu sọ igi káàkiri ayé, tí ìdààmú sì ba, tí yí òò ma wípé, "Pongodoro, pongodoro."

***Translation:***

1. Ifá recommends ẹbọ for good health of the children of whomever Ogbè Ọ̀wọ́nrín comes out for. Ifá warns the person not to disrespect Ifá's injunctions. Ifá says make ẹbọ.

Itẹ́ gùdùgbè
Divine for elédiò (hen).





Elédìò in reference here was a hen in the olden days. The hen's chicks were sick of some neurosis; therefore, the hen consulted Ifá for cure. Hen was told to make ẹbọ, but it did not make the ẹbọ. Because of hen's failure to make the ẹbọ, the chicks' neurosis got worse, and they started dying. However, before the chicks died, they lamented saying their mother's refusal to make ẹbọ was the cause of their deaths.

2.

Ayegbe here
Ayegbe there
Divined for a group of animals
When they wanted to marry Mọlújanjan, daughter of Olúigbó
Ayegbe here
Ayegbe there
Divined for oorẹ (porcupine)
When he was to marry Mọlújanjan, daughter of Olúigbó.

Ifá is talking about Mọlújanjan, daughter of Olúigbó. All animals in the forest - elephant, buffalo, deer, oorẹ, and so on, wanted to marry her to themselves. Olúigbó, the father, decided to test the animals. To pass the test, Mọlújanjan must hug only one of the animals, and whichever of them she hugged and accepted an orange from, will be her chosen husband. All the animals went for divination, but it was only oorẹ that performed Ifá's prescribed ẹbọ. The animals underrated oorẹ in the contest. Elephant said, "With me around...;" buffalo said, "With me around...;" deer said, "With me around, oorẹ would not win Mọlúnjanjan's love." Relying on their mights, the animals refused to make the prescribed ẹbọ. Oorẹ made

the ẹbọ and bought an orange. Oorẹ took the orange to his Babaláwo for blessing. The Babaláwo blessed the orange. On the day of the contest, all the animals were there, and they started singing. Elephant was the first to sing, saying:

Mọlújanjan accept my orange, àlùjanjan-kíjan
I, elephant, am the king of the forest, àlùjanjan-kíjan
Buffalo is the child of ọ̀dọ̀fin, àlùjanjan-kíjan
Deer is the child of abilà (deer is the one with marks),
àlùjanjan-kíjan.
Oorẹ is our slave, àlùjanjan-kíjan
Mọlújanjan accept my orange, àlùjanjan-kíjan.

Mọlújanjan did not respond, and she did not accept the orange either. Buffalo told elephant to excuse him. Buffalo started singing to Mọlújanjan, saying:

Mọlújanjan accept my orange, àlùjanjan-kíjan
Elephant is the king of the forest, àlùjanjan-kíjan
I, buffalo, am the child of ọ̀dọ̀fin, àlùjanjan-kíjan
Deer is the child of abilà (deer is the one with marks),
àlùjanjan-kíjan.
Oorẹ is our slave, àlùjanjan-kíjan
Mọlújanjan accept my orange, àlùjanjan-kíjan.

Mọlújanjan did not respond, and she did not accept the orange either. Deer asked buffalo to excuse him, he too started singing to Mọlújanjan, saying:

Mọlújanjan accept my orange, àlùjanjan-kíjan
Elephant is the king of the forest, àlùjanjan-kíjan





Buffalo is the child of ọ̀dọ̀fin, àlùjanjan-kíjan
I, deer, am the child of abilà (one with marks), àlùjanjan-kíjan
Oorẹ is our slave, àlùjanjan-kíjan
Mọlújanjan accept my orange, àlùjanjan-kíjan.

Mọlújanjan did not respond, and she did not accept deer's orange. All the other animals took their turns, but Mọlújanjan accepted no orange from any one of them. Then it was oorẹ's turn, and he asked to be excused. Oorẹ too started singing to Mọlújanjan, saying:

Mọlújanjan accept my orange, àlùjanjan-kíjan
Elephant is the king of the forest, àlùjanjan-kíjan
Buffalo is the child of ọ̀dọ̀fin, àlùjanjan-kíjan
Deer is the child of abilà (deer is the one with marks),
àlùjanjan-kíjan
I, Oorẹ, am not their slave, àlùjanjan-kíjan
Mọlújanjan accept my orange, àlùjanjan-kíjan.

To everybody's surprise Mọlújanjan responded; she hugged Oorẹ and accepted the orange from him. Then she asked, "So you are not their slave?" Oorẹ answered that he was not the animals' slave. Having passed the test by virtue of the ẹbọ he made, and by the special Ifá work done on the orange, oorẹ was given Mọlújanjan in marriage to the disappointment of all the other animals.

*Àṣẹ*: Ifá teaches us not to look down on anybody or be egocentric. Ifá says whomever Ogbè Ọ̀wọ́nrín comes out for must make ẹbọ for success in a test ahead of him/her.

3.
Egbinrin is the diviner for *aja ilẹ̀*
Divined for Yemọ̀ọ́
Who was/is Òrìṣà's (Ọbàtálá's) wife
When she was crying for want of children.

Yemọ̀ọ́ in reference here was childless, and she was desperate for children. To solve the problem, she went for divination. The Babaláwo told Yemọ̀ọ́ to make ẹbọ assuring her that she would have many children after the ẹbọ. They gave Yemọ̀ọ́ the list of things needed. Yemọ̀ọ́ provided the things, and the ẹbọ was made for her. Olódùmarè (God) answered Yemọ̀ọ́'s prayers and sent her 16 children; therefore, she started praising the Awo, the awo praised Ifá while Ifá praised Olódùmarè.

*Àṣẹ:* Ifá says the person that Ogbè Ọ̀wọ́nrín comes out for will have many children, but he/she should make ẹbọ. Ifá warns the person not to disrespect this advice for ẹbọ.

4. Ifá says the person that Ogbè Ọ̀wọ́nrín comes out for must make ẹbọ so that her husband, or his wife, will not leave her/him for a rival. Ifá says the person should adhere to this Ifá's advice.

We must think of our families first
Before we think of outsiders (somebody else)
Divined for porogodo
Wife of àkókò (woodpecker).





Porogodo was àkókò's wife. One day àkókò suspected that his wife, porogodo, was to be taken from him; he, therefore, went for divination. They [the Babaláwo] told him to make ẹbọ. Àkókò did not make the ẹbọ. Àkókò said rather than make the ẹbọ, he would think of a wise way to prevent loosing his wife to a rival. Therefore, àkókò dug a hole in a tree, hid his wife inside it, then cover the hole and flew home. When àkókò went back to get his wife, he was unable to locate the particular tree he hid her because he did not make any sign on the tree. Àkókò has been pecking trees since then looking for his wife, porogodo, and calling, ''Porogodo, porogodo'' every where he went.

# Ẹ̀fà (6)

## Ogbè Ọ̀bàrà

1. Ifá pé òun pé ire iṣégun àti ire ẹ̀yọ́nú fún ẹni tí ó dá Ogbè Ọ̀bàrà. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú.

Ìrùlá kò ṣe ọmọ inú rẹ̀ ṣe pẹ̀lẹ́
A d'Ifá fún Olúkòso là'lù
Arábámbí a fi igba ọta ṣẹ́'gun
Èyí tí yí òò fi àlàpà ṣẹ́'gun ọ̀tá rẹ̀
L'ọ́jọ́ tí Olúkòso là'lù ǹbínú.
Ìrùlá kò ṣe ọmọ inu rẹ̀ ṣe pẹ̀lẹ́
A d'Ifá fún Ogbè
L'ọ́jọ́ tí ó ǹlọ rèé bẹ àrìrà.

Ní àkókò tí Ifá sọ yìí, àwọn ọ̀tá yàjú sí Ṣàngó, ni Ṣàngó bá bínú sí àwọn ọ̀tá rẹ̀ nipa rírọ òjò iná lé wọ́n l'órí . Àwọn ọ̀tá kò gbádùn mọ́, ni wọ́n bá ro'nú títí wípé taní yí òò bá àwọn bẹ Ṣàngó. Ni wọ́n bá lo ké sí Ọ̀rúnmìlà wípé kó wá lọ bá àwọn bẹ Ṣàngó. Wọ́n bọ orísì-rísì nkan tí ẹnu ńjẹ pẹ̀lú igba (200) orógbó, obúkọ kan. Ni Ọ̀rúnmìlà bá kó gbogbo nkan wọ̀nyí



lọ sí ọ̀dọ̀ Ṣàngó. Bí Ṣàngó ṣe fi ojú rí orógbó, ni ó bá yọ́nú sí àwọn ọ̀tá rẹ̀, ó l'òun kò ni bínú sí wọn mọ́. Bí Ọ̀rúnmìlà ṣe kúrò l'ọ́dọ̀ Ṣàngó ni òjò ṣú. Ọ̀rúnmìlà pẹ̀lú òjò ló padà wọ'lé. Òjò tó ti ńrọ gbígbóná, tútù ni ó rọ̀. Láti ọjọ́ yìí ni Ṣàngó ti yọ́nú sí àwọn ọ̀tá rẹ̀. Ọ̀rúnmìlà ni:

Ìrùlá kò ṣe ọmọ inú rẹ̀ ṣe pẹ̀lẹ́,
A d'Ifá fún Olúkòso là'lù
Arábámbí a fi igba ọ̀tá ṣẹ́'gun
Èyí tí yí òò fi àlàpà ṣẹ́'gun ọ̀tá ẹ
L'ọ́jọ́ tí Olúkòso là'lù ǹbínú.
Ìrùlá kò ṣe ọmọ inú rẹ̀ ṣe pẹ̀lẹ́
A d'Ifá fún Ogbè
L'ọ́jọ́ tí ó ǹlọ rèé bẹ àrìrà.
Ogbè ni ó bẹ àrìrà, òjò ni ó bose awo.

2. Ifá pé òun pé ire àìkú fún ẹni tí ó dá Ogbè Ọ̀bàrà. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú. Ifá pé òun yí òò ba ṣẹ́'gun ọ̀tá.

Ogbè bàràbàrà láá g'eti
Ṣọ̀rìṣò orí ẹ l'òògùn
A d'Ifá fún Àágbèrí ọga
Ọmọ akán'run ma yún-ún
Ọmọ akán'run ma lọ
Ọmọ akan'lẹ̀kùn ọ̀run gbọn-gbọn-gbọn má rè
L'ọ́jọ́ tí wọ́n ńránṣẹ́ ikú pé e l'ọ̀run.

Àágbèrí tí Ifá s'ọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí ni àwọn ọ̀tá pọ̀ fún, tí ó sì ńlá àlá búburú. Ni ó bá mú èéjì kún ẹ̀ẹ̀ta ó lọ sí oko awo. Wọ́n ni ẹbọ ni kí ó rú. Wọ́n yàn án l'ẹ́bọ; ó rú'bọ. Kò pẹ́ àwọn ọ̀tá tún bẹ̀rẹ̀

sí ni pe'ri rẹ̀. Wọ́n pe'ri rẹ̀ títí kò dá wọn l'óhùn, bẹ̀ẹ̀ ni kò si kú, kàkà kí ó kú àwọn ọ̀tá rẹ̀ ni wọ́n ńkú, tí ibi sì ńbá wọn. Ló bá ńyin àwọn Awo, àwọn Awo ńyin Ifá, Ifá ńyin Elédùmarè. Ó ni bẹ̀ẹ̀ l'áwọn Awo òun wí pé:

Ogbè bàràbàrà láá g'ẹti
Ṣónṣó orí ẹ l'óògùn
A d'Ifá fún Àágbèrí ọga
Ọmọ akàn'run ma yùn-ùn
Ọmọ akàn'run ma lọ
Ọmọ akan'lẹ̀kùn ọ̀run gbọn-gbọn-gbọn má rè
L'ọ́jọ́ tí wọ́n ńránṣẹ́ ikú pé e l'ọ́run
À ńpe Àágbèrí l'ọ́run kò jẹ́ agogo
Idẹ ńro kẹ́
Ọlọ́run ti'kùn.

*Àṣẹ:* Ifá pé òun kò ní jẹ́ kí ọwọ́ ọ̀tá tẹ ẹni tí ó dá Ogbè Ọ̀bàrà.

3. Ifá pé òun pé ire àìkú fún ẹni tí ó dá Ogbè Ọ̀bàrà. Ifá pé kí eléyiun ó má ṣe àìgbọ̀ràn, kí ó sì má déjàá. Ifá pé kí ó rú'bọ.

Òpipi yé diẹ̀ diẹ̀ kí o lè baa r'àpá bo ẹyin
A d'Ifá fún eku
Tí ńjẹ̀ nímọ̀rin àfọ̀n
Òpipi yé diẹ̀ diẹ̀ kí o lè baa r'àpá bo ẹyin
A d'Ifá fún ejò
Tí ńjẹ̀ nímọ̀rin àfọ̀n
Òpipi yé diẹ̀ diẹ̀ kí o lè baa r'àpá bo ẹyin
A d'Ifá fún igbin
Tí ó ńjẹ̀ nímọ̀rin àfọ̀n.





Àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí ni wọ́n ní kí wọn ó rú'bọ kí ikú má baa pa wọ́n. Abẹ́ àfọ̀n ni wọ́n fi ṣe ilé tí wọ́n ti ma ńjẹ̀ ni abẹ́ rẹ̀. Wọ́n ní ikú ńbọ̀ o, kí wọn ó rú'bọ. Ìtí rèé agbede méjì àfọ̀n ni ó wà. Ìtí ńlérí fún wọn wípé kò sí ǹkan tó jọ ikú tí yí óò dé bá wọn ní ilé òun. Kò sí ǹkan tí ó ńbọ̀ tí ilẹ̀ kò gbà dúró. Kí wọn ó má dààhùn. Nínú àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí, igbin nìkan ni ó rú'bọ. Kò pẹ́ atẹ́gùn líle dé, kí ó tó di wípé ìjì dé, igbin ti fi ẹnu la ilẹ̀ ó kò sí abẹ́ ilẹ̀ , ó fi yanrìn bo ara rẹ̀. Kò pẹ́, kò jìnà, àfọ̀n dúró ó já kúrò l'órí ìtí, ó já lu eku àti ejò nílẹ̀; ó pa wọ́n. Kò lè dé ọ̀dọ̀ igbin. Ìgbàtí gbogbo ǹkan rọ̀'lẹ̀ tán ni igbin bá tún fi ẹnu la ilẹ̀ jáde. Báyìí ni ikú kò pa igbin tí eku pẹ̀lú ejò fi àìgbọ̀ràn pẹ̀lú ẹ̀jẹ́ dídá ràn ara wọn ní ọ̀run ọ̀sán gangan. Láti igbà yí ló ti di ìkìlọ̀ fún èniyàn tí èniyàn bá ńlérí wípé ṣọ̀'ra à rẹ ò, ìtí kò r'órí gba àfàndúró.

4. Ifá pé ẹni tí ó dá Ogbè-Bàrà, Ifá pé ẹbọ kí àìsàn má ba ṣe ni kó rú, kí ó ma ṣe fi eti pálábà ẹbọ rè.

Àṣẹ̀ṣẹ̀ yọ ọ̀dúndún
Nìí f'ara jọ etí adẹ́tẹ̀
A d'Ifá fún àjídèwe Ẹ̀dú
Àjídèwe Ẹ̀dú ni à ńpe Ọ̀rúnmìlà.

Ara òun le báyìí ni ó dá Ifá sí. Wọ́n ni ẹbọ ni kó'rú kí àìsàn má bá ṣee mọ́. Ọ̀rúnmìlà bèrè ẹbọ, wọ́n yàn án l'ẹ́bọ; Ọ̀rúnmìlà rú'bọ. Láti ọjọ́ náà ni Ọ̀rúnmìlà kò tí ṣe àìsàn mọ́. Ó wá nyin Elédùmarè Ọba l'ọ́run.

Àṣẹ̀ṣẹ̀ yọ ọ̀dúndún
Nìí f'ara jọ etí adẹ́tẹ̀

A d'Ifá fún Àjidèwe Ẹdú
Àjidèwe Ẹdú ni á ńpé Ọrúnmìlà.

***Translation:***

1. Ifá foresees victory and recommends ẹbọ to achieve the victory.

Ìrúlá (dried okra) control your noise
Divined for Olúkòso là'lú* (Ṣàngó's alias)
Arábámbí*, rock fighter (*Ṣàngó's alias)
Who killed his enemies with wall plasters
The day he was angry
Ìrúlá (dried okra) control your noise
Divined for Ogbè
The day he went to appeal to Ṣàngó.

At the time of this mythological story, some enemies disrespected Ṣàngó. Ṣàngó was so enraged by these enemies' misbehavior that he visited them with serious thunder storms. The enemies became ill from the effect of the devastating thunder storm. When they realized their mistakes, they felt repentant and solicited Ọrúnmìlà's help to appeal to Ṣàngó on their behalf. Ọrúnmìlà told them to offer lots of edibles and to provide one male goat and 200 orógbó. Ọrúnmìlà took the 200 orógbó and the male goat to Ṣàngó. As soon as Ọrúnmìlà gave Ṣàngó the offerings, Ṣàngó instantly forgave the enemies of their misdemeanors. Instead of the ceaseless devastating rain storms going on, Ṣàngó released a peaceful curative





showers of rain. Ọrúnmìlà was yet to get back home from his visit to Ṣàngó's shrine when the rain started. Ọrúnmìlà said:

Ìrúlá (dried okra) control your noise
Divined for Olúkòso là'lú* (Ṣàngó's alias)
Arábámbí, rock fighter
Who killed his enemies with wall plasters
The day he was angry
Ìrúlá (dried okra) control your noise
Divined for Ogbè
The day he went to appeal to Ṣàngó.

2. Ifá foresees long life and recommends ẹbọ for victory over adversaries.

Ogbè bàràbàrà is the sound from indigo pounding
Its peak is potent medicine
Divined for the king of Iràgbèri
He who would not die young
And lived to a very old age
Even when he was summoned to heaven.

Àágbèrí was having constant nightmares, therefore, he decided to consult Ifá. The Babaláwo told him to make ẹbọ and gave him a list of things for the ẹbọ. Àágbèrí made the ẹbọ, and he was protected against attacks from his enemies. Soon after the ẹbọ, enemies started waging war on Àágbèrí once again, but by virtue of the ẹbọ that he made, evil deeds of the enemies returned to them, and they started dying. Àágbèrí started praising his Awo for their good work, the Awo thanked

Ifá, and Ifá [Ọ̀rúnmìlà] thanked Olódùmarè. With happiness, Àágbèrí said his Awo told him that:

Ogbè bàràbàrà is the sound from indigo pounding
Its peak is potent medicine
Divined for king of Irágbèrí
He who would not die young
And lived to a very old age
Even when he was summoned to heaven
He did not answer the call (he did not die)
Because Ifá protected him by virtue of a charm made on agogo Ifá for him
That charm caused heaven's gate to be locked against him.

3. Ifá says long life for whomever Ogbè Ọ̀bàrà comes out for. Ifá warns the person not to disrespect Ifá's advice and not to disobey any advice for ẹbọ. Ifá says make ẹbọ.

Hen-lay-small-quantity-of-eggs-to-be-able-to-hatch-them
Divined for eku (rat)
That plays around the snare for animals
Hen-lay-small-quantity-of-eggs-to-be-able-to-hatch-them
Divined for snake
That runs around àfọ̀n (a tree)
Hen-lay-small-quantity-of-eggs-to-be-able-to-hatch-them
Divined for snail
That crawls around àfọ̀n.

These three reptiles were advised to make ẹbọ to save their lives. The reptiles lived and did everything under àfọ̀n and





were told that death was lurking around them, but to make ẹbọ for prevention. Ìtí (parasitic plant on trees) on its own was in the middle of àfọ̀n. Iti told them not to make ẹbọ because he felt that nothing bad could happen to them, and that they should not mind the Babaláwo. Of the three reptiles, snail was the only one that made the ẹbọ. Soon after the Babaláwo's advise for ẹbọ, a strong wind occurred. Before then, however, snail had dug a hole and buried itself under the sand. The strength of the wind detached àfọ̀n from iti tree; it fell on rat and snake, and killed them, but snail was saved by having buried itself under the sand. When everywhere was calm again, snail crawled out from its hiding. This way, snail's life was saved and disobedience and disrespect for spiritual advice killed rat and snake.

4. Ifá says whomever this Odù Ifá comes out for must make ẹbọ to prevent sickness. The person must always make prescribed ẹbọ.

A germinating ọdúndún
Looks like a Euphorbia barteri's leaf
Divined for Àjídèwe Ẹ̀dú
Àjídèwe Ẹ̀dú is another name for Ọ̀rúnmìlà.

"Will I enjoy good health?" was the question Ọ̀rúnmìlà posed to Ifá. They [the Babaláwo] told him to make ẹbọ to ward off sickness. Ọ̀rúnmìlà asked what the ẹbọ requirements were. They told him; he made the ẹbọ. Ọ̀rúnmìlà had since then enjoyed good health. Therefore, he started to praise Olódùmarè saying:

A germinating ọdúndún
Looks like a Euphorbia barteri's leaf
Divined for Àjídèwe Ẹdú
Àjídèwe Ẹdú is another name for Ọ̀rúnmìlà.



# *Èje (7)*

## Ogbè Ọ̀kànràn

1. Ifá pé òun pé ire ọmọ fún ẹni tí ó dá Ogbè-Kànràn. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú. Ifá pé ìrìn àjò kan ni eléyiun fẹ́ lọ, kí ó rú'bọ kí ìbẹ̀ lè ba san án sí owó, kí ó san án sí ọmọ.

Ká bù'jẹ, ká bù tà
A d'Ífá fún Àwùjẹ
Tí ó ńlọ oko àléró l'ọ̀dún
Ó ní rí'rú ẹbọ níí gbe ni
Àìrú kìí gbè'níyàn.

Àwùjẹ tí Ifá ńsọ yìí ojú ọmọ ńpọn; kò rí ọmọ bí. Ló bá mú ééji kún ẹ̀ẹ́ta, ó lọ oko awo wípé báwo ni òun yí óò ṣe rí ọmọ bí, àti wípé òun fẹ́ rin ìrìn àjò, ǹjẹ́ ìbẹ̀ yí óò san òun ni ó dá Ifá sí. Wọ́n ní à rí ọmọ bí ní ìbẹ̀, wọ́n ní ẹbọ ni kí ó rú. Wọ́n yàn án l'ẹ̀bọ, ó sì rú ẹbọ náà. Kò pẹ́ tí Àwùjẹ di ọlọ́mọ púpọ̀. Ó wá nyin Awo, Awo ńyin Ifá, ó ní bẹ́ẹ̀ ni wọ́n wí:

Ká bù'jẹ, ká bù tá
A d'Ífá fún Àwùjẹ

Tí ó ńlọ oko àléró l'ọdún
Ó ni ri'rú ẹbọ nìi gbe ni
Àìrú kìí gbè'niyàn
Kèè pẹ́ o, kèè jìnà
Ẹ wá bá wa láàárín ọmọ
Àárín ọmọ làá bá'ni l'ẹsẹ̀ Ọbàrìṣà.

2. Ifá pé òun pé ire iṣẹ́gun ọ̀tá. Ifá pé òun yì óò yọ ọ́ láàárín ọ̀tá. Ifá pé òun yì óò jẹ́ kí ó rí ojútùú ayé e rẹ̀. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú.

Ọtapẹtẹmoso
A d'Ifá fún ọrọ́.

Ọrọ́ ti Ifá s'ọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí, àárín àwọn ọ̀tá ẹlẹyẹ ni ó wà dé ibi wípé wọn kò jẹ́ kí ó rí ojútùú ayé rẹ̀. Wọn kò jẹ́ kí ó níláárí. Ọrọ́ ro'nú títí wípé kíni òun lè ṣe, ló bá kọ'rí s'ílé aláwo. Wọn dá Ifá fún, wọn ni àwọn ọ̀tá ẹlẹyẹ ló ńba jà wípé ẹbọ ni kí ó rú. Kí ó rú ẹ̀kọ fífọ̀, ata pupa, abẹ́rẹ́ lọ́pọ̀lọpọ̀. Ọrọ́ tọ́'jú gbogbo nkan wọ̀nyí. Ni wọn bá rú'bọ fún. Wọn ṣe Ifá fún s'inú ẹ̀kọ fífọ̀; wọn fà ẹ̀kọ yìí pọ̀ mọ́ abẹ́rẹ́, ni wọn bá ni kí Ọrọ́ gbé ẹ̀kọ náà mu. Ọrọ́ gbé ẹ̀kọ náà mu. Bí ó ṣe mu ú tán, àwọn ẹlẹyẹ kò lè dé ọ̀dọ̀ rẹ̀ mọ́. Abẹ́rẹ́ ọjọ́ yẹn ni ẹ̀gún tí ó wà ní ara ọrọ́ di òní. Ẹ̀kọ ọjọ́ náà ni ó di oje ara rẹ̀, ata ọjọ́ náà ni ó wà l'ára oje rẹ̀ tí kò fi gbọ́dọ̀ dá sí ojú. Báyìí ni àwọn ẹlẹyẹ kò lè dé ọ̀dọ̀ ọrọ́ mọ́, tí ọrọ́ sì ṣẹ́'gun àwọn ẹlẹyẹ pátápátá.





3.
Ido apata ab'idi jẹjẹrẹ
A d'Ifá fún Ọlágbẹ̀gi
Tí ńlọ Òkìtì Ẹ̀fọ̀n
Tí ńlọ rèé bá wọn mú'lẹ̀ ibùdó.

Ọlágbẹ̀gi yìí ènìyàn ni. Nínú ìlú rẹ̀, àwọn ọ̀tá pọ̀ fún nítorí orúkọ rẹ̀. Orúkọ yìí ni àwọn ènìyàn fi ńbínú rẹ̀ wípé kòní tíì dé ibikan, tí yí óò fi di ẹni ńlá gẹ́gẹ́bí orúkọ rẹ̀. Àwọn ọ̀tá kò jẹ́kí ó dìde. Ó wa ro'nú wípé kíni òun lè ṣe. Ni ó bá mú ẹ̀ẹ̀jì kún ẹ̀ẹ̀ta ló lọ oko awo. Wọn ni kí ó kúrò nínú ìlú yìí kí ó lọ sí ìlú mìíràn, kí ó sì rú'bọ. Wípé tí ó bá ti rú'bọ, yí óò sì pa orúkọ rẹ̀ dà, ọ̀tọ̀ ni orúkọ tí yí óò ma jẹ́ tí yí óò fi di ẹni ńlá. Tí ó bá ti ri ṣe tán tí ó di ẹni ńlá, yí óò wá ma padà jẹ́ orúkọ rẹ̀. Ni Ọlágbẹ̀gi bá rú'bọ, ó pa orúkọ rẹ̀ dà. Ìgbàtí ó dé ìlú mìíràn, báyìí ni ó bẹ̀rẹ̀ sí rí ṣe, tí gbogbo ǹkan rẹ̀ ńdára, tí ó sì di ńlá. Ó ńyin Awo, Awo ńyin Ifá, Ifá ńyin Elédùmarè ọba l'ọ̀run. Nígbàtí ó de òde Òkìtì Ẹ̀fọ̀n, wọn bi í léèrè pé, ''Kínni orúkọ rẹ o?'' Ó dáhùn wípé Ọlájùwẹrẹ ni orúkọ òun jẹ́. Ni wọn bá bu ilẹ̀ ilé àti ilẹ̀ oko fún. Ló bá tẹ̀'lú dó síbẹ̀ náà. Òun ló wá kù tí ńjẹ́ ọba ni òde Ọ̀wọ̀ - Ọlágbẹ̀gi (Ọlọ́wọ̀ of Ọ̀wọ̀). Ifá pé òun yì óò bá eléyìun ṣẹ́'gun ọ̀tá. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú, kí ó sì má fi etí pàlàbà ẹbọ tí wọn bá ni kí ó rú.

4. Ifá pé ẹni tí ó dá Ogbè Ọ̀kànràn kí ó rú'bọ nítorí ajogun ibi fún eléyìun.

Àdàn l'awo arà rìrì rà rìrì
Ògbìgbì l'awo arà bàbàbà ka'lẹ̀
A d'Ifá fún Ogbè

L'ọ̀jọ́ tí ó ńlọ rèé kan ikú, kan òfò, kan ọ̀ràn, ní Ifẹ̀ Oòyè Lagbèmoró.

Ní ayé àtijọ́ àwọn ara Ifẹ̀ ni àwọn ajogun pọ̀ fún, tí wọ́n ńdà wọ́n láàmú, ni àwọn ara Ifẹ̀ bá ránṣẹ́ pé Awo wípé kí ó bá àwọn bèrè l'ọ́wọ́ Ifá. Ìgbàtí wọ́n ó dá Ifá, wọ́n dá Ogbè-Kànràn. Ifá ní kí wọ́n ó pa òrúkọ [òbúkọ] ńlá kan, kí wọ́n ó pe iyẹ̀ Ifá sí, kí wọ́n ó lọ rèé fi s'ẹnu odi ìlú. Kí wọ́n kàn-án mọ́ igi ńlá l'ẹ̀hin odi ìlú. Ní àwọn ará Ifẹ̀ bá ṣe ohun tí Ifá wí. Láti ọjọ́ tí wọ́n tí ṣe irúbọ yìí ni òfò, ikú òjiji, pẹ̀lú gbogbo ibi yòókù kò tí ṣẹlẹ̀ sí wọ́n mọ́, ni wọ́n bá ṣe àṣàrò wípé orúkọ wo ni wọ́n ó ma pé Odù yí, wọ́n ní Ogbè-Kànràn ni toripé òun ló lọ rèé kan ikú, tó kan òfò, tó kan iyà, tó kan ọ̀ràn n'Ífẹ̀ Oòyè Lagbèmoró.

***Translation:***

1. Ifá says he will bless the person that Ogbè Ọ̀kànràn comes out for with a child, but that the person should make ẹbọ. Ifá says the person is going on a journey; therefore, he/she should make ẹbọ so that the journey will be fruitful - fruitful for all *ire* - health, wealth, success, and good children.

To eat, to sell
Divined for Àwújẹ (kind of beans)
Who was going on a long journey
She said making ẹbọ has its bountiful reward
Refusal to make ẹbọ has its set back





Àwújẹ in reference here was childless, and she was very desperate for a child. As a result of this problem, she consulted Ifá for solution. In addition to the issue of childlessness, she also consulted Ifá for a journey she planned to make. Ifá assured Àwújẹ that she would be blessed with children but recommended ẹbọ. Ifá also assured her that her journey would be beneficial. The Babaláwo told Àwújẹ the things required for ẹbọ. Àwújẹ provided the things; ẹbọ was accordingly made for her. Soon after the ẹbọ, Àwújẹ started having children and money. Therefore, she thanked her Awo while the Awo thanked Ifá. Àwújẹ said:

To eat, to sell
Divined for Àwújẹ (kind of beans)
Who was going on a long journey
She said making ẹbọ has its bountiful reward
Refusal to make ẹbọ has its set back
Soon after the ẹbọ
We were blessed with children
Rejoice with us in the worship of the Òrìṣà.

2. Ifá foresees victory for whomever this Odù comes out for. Ifá says he will protect the person against all adversaries. Ifá says he will crown the person's efforts with success. Ifá recommends ẹbọ.

Ọtapẹtẹmoso
Divined for ọrọ́.

Ọ̀rọ́ in reference here was surrounded by witches who messed up his life. Ọ̀rọ́ was depressed and thought of what he could do to save himself from the witches claws. The solution that came to his mind was Ifá. Therefore, he went to a Babaláwo's house and consulted Ifá. The Babaláwo divined for him and confirmed that truly, witches were against him. The Babaláwo then advised him to make ẹbọ. Ọ̀rọ́ was told to provide **ẹ̀kọ** *(Yorùbá traditional food. Ẹ̀kọ is a corn starch meal)*, lots of cayenne pepper, lots of abẹ́rẹ́ *(needles)*. Ọ̀rọ́ provided the things, and ẹbọ was made for him. Special Ifá work was done on the ẹ̀kọ after which it was mixed with the abẹ́rẹ́. Ọ̀rọ́ was told to drink the concoction which he did. As soon as he drank the medicine, all the witches that were hitherto bothering him ran away. The abẹ́rẹ́ used for the Ifá medicine that day metamorphosed to be the thorn found on ọ̀rọ́ up todate. That day's ẹ̀kọ is the sap from ọ̀rọ́; the cayenne pepper of that day is the poison that comes with the sap which makes the sap poisonous to the eyes. Through this spiritual work, ọ̀rọ́ overcame his enemies - the witches.

3.

Ido apata..
Divined for Ọlágbẹ̀gi
When he was travelling to Òkiti Ẹ̀fọ̀n (a town)
When he was to take up permanent residence there.

Ọlágbẹ̀gi was a hard working, famous person. Everywhere he went, people respected him for the good name he made for himself. However, Ọlágbẹ̀gi's fame made his enemies uncomfortable, and they despised him gravely for that. These





enemies did awful things to keep Ọlágbẹ̀gi down, but his guardian angels protected him. Instinctively, Ọlágbẹ̀gi knew that some people were waging war against him, and this gave him a very serious concern. One day, he decided to consult Ifá through his Babaláwo. He went to his Babaláwo, and the Babaláwo consulted Ifá for him. Ifá told Ọlágbẹ̀gi to leave the town of his birth for another place. He was also advised to make ẹbọ and to change his name - for fast progress - as soon as he got to that other town. Furthermore, Ifá told Ọlágbẹ̀gi that as soon as he became successful, he should revert back to his real name. Ọlágbẹ̀gi made the ẹbọ and left.

As soon Ọlágbẹ̀gi got to this Ifá predicted town, Òkiti Ẹ̀fọ̀n, he changed his name according to Ifá's injunction. Each and everytime he was asked what his was, he would tell them that his name was *Olájinwẹ̀rẹ̀*. He began his new life there with hard work. Luckily for him, his business boomed, and he became prosperous. Soon, he earned the love and respect of the community. To show how much they loved him, the community gave him a large acreage of land. Ọlágbẹ̀gi built houses on the land while he used a large part of it for farming. Ọlágbẹ̀gi built many houses and took up permanent residence there. Soon, Ọlágbẹ̀gi was made the king of Ọ̀wọ̀, and he became known as Ọlágbẹ̀gi, the Ọlọ́wọ̀ (king) of Ọ̀wọ̀. He was so happy that he started singing the praise of his Awo while his Awo praised Ifá, and Ifá [Ọ̀rúnmìlà] praised Olódùmarè.

*Àṣẹ*: Ifá says he will make the person that this Odù comes out for victorious. Ifá recommends ẹbọ and warns the person never to disobey the advice.

4. Ifá says whomever Ogbè Ọ̀kànràn comes out for must make ẹbọ to ward off evil forces that surround him/her.

Àdán l'awo arà riri rà riri (description of a bat's movements)
Ògbìgbì l'awo arà bàbàbà ka'lẹ̀
(description of ògbìgbì's movements)
Divined for Ogbè
The day he was to combat death, combat sickness, combat losses, combat all problems in Ilé Ifẹ̀ during the reign of King Lagbémoró.

Once upon a time in ancient times, Ifẹ̀ people were constantly terrorized by ajogun (bad forces), and when they could not bear it any more, they sent for a Babaláwo to consult Ifá for them. When Ifá was to talk, Ifá talked to them through Ogbè-Kànràn. Ifá told them to offer a big male goat. Ifá instructed the Babaláwo to bless the offering with a special Ifá chant, nail the offering on a big tree outside the gate to the town. Ifẹ̀ people did the ẹbọ according to Ifá's instruction. Since the day that Ifẹ̀ people made the ẹbọ, death, sickness, losses, problems, and all the other bad things stopped happening to them. Thereafter, the people had a meeting and asked themselves, "What name should we call this Odù?" They unanimously answered, "Let us call the Odù, Ogbè Ọ̀kànràn because it was the Odù that nailed [buried] death, sickness, losses, and all problems in Ilé Ifẹ̀."



# Ẹ̀jọ (8)

## Ogbè Ògúndá (Ogbè Yọ́nú)

1. Ifá pé òun pé ire ọmọ fún ẹni tí ó dá Ogbè Yọ́nú. Ifá pé àwọn méjì ni ojú ọmọ ńpọ́n. Ifá pé kí wọn ó rú'bọ nítorí kí wọn ó le ba bí'mọ.

**Ẹbọ:** Ewúrẹ kan ni ẹbọ. Ẹ gbọ́ bí Ifá ti wí:

Ọká gbé'nú itẹ́
Ọká ńyọ'ri ọkà idada idada
Erè gbé'nú àbàtà ga'rùn oyè
A d'Ifá fún àgàn dúdú
A bù fún àgàn pupa
Ẹkún ọmọ ni wọ́n ńsun.

Ní ayé àtijọ́ àwọn àgàn méjì kan wà tí ojú ọmọ ńpọ́n. Àgàn àkọ́kọ́ ni óro, àgàn elékéjì ni ọsàn àgbàlùmọ̀. Ojú ọmọ ńpọn àwọn àgàn méjèèjì yí débi wípé ẹkún ni wọ́n ma á fi ṣe oúnjẹ. Wọ́n ro'nú títí wọn kò mọ ohun tí wọ́n le ṣe. Ní wọ́n bá mú ẹ́èjì kún ẹ̀ẹ́ta wọ́n lọ sí oko awo. Ǹjẹ́ àwọn lé bí'mọ bàyìí ni

wọ́n dá Ifá sí. Ifá ní wọn óò bí'mọ, ẹbọ ni kí wọn ó rú. Ní wọ́n bá yàn wọ́n l'ẹ́bọ. Ọsán àgbálùmọ̀ ló kọ́kọ́ rú'bọ, ó fi ewúrẹ́ kékeré rú'bọ tirẹ̀. Ìgbàtí yí óò fi bí'mọ, ọmọ rẹ̀ kéré. Bí òro ṣe gbọ́ wípé ọsán àgbálùmọ̀ l'óyún, ó bí'mọ, ọmọ rẹ̀ kéré, ni òro náà bá sáré mú ewúrẹ́. Ìgbàtí òun fẹ́ rú'bọ tirẹ̀, ewúrẹ́ nlá ni ó rú l'ẹ́bọ. L'ẹ́hìn irúbọ tirẹ̀ náà, oyún dé; nígbàtí yí óò bí'mọ, ọmọ tirẹ̀ tóbi. Inú àwọn méjèèji dùn, wọ́n nyin Awo, Awo nyin Ifá, Ifá nyin Elédùmarè. Wọ́n ní bẹ́ẹ̀ ni àwọn Awo wípé:

Ọká gbé'nú itẹ́
Ọká ńyọ'rí ọlá idada idada
Erè gbé'nú àbàtà ga'rún oyè
A d'Ifá fún àgàn dúdú
A bù fún àgàn pupa
Ẹkún ọmọ ni wọ́n ńsun.
Àgàn dúdú làá pé òro; àgàn pupa làá pé ọsán àgbálùmọ̀.

2. Ifá pé ẹni tí ó dá Ogbè Yọ̀nù, Ifá pé kí ó má ṣe yájú sí àwọn tí ó júù lọ. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú.

Ìbínú kò ṣe ǹkan rere fún ni
Sùúrù ni baba ìwà
Àgbà tí ó bá ní sùúrù
Ohun gbogbo ló ní
D'Ifá fún Ọ̀rúnmìlà
L'ọ́jọ́ tí ó ńṣawo r'òde Ìwó
Tí ó ńlọ rè e fẹ́ ìyà tii ṣe ọmọ Olúìwó.





Ọ̀rúnmìlà ló ṣ'awo lọ sí Òde Ìwó. Ìgbàtí ó de òde Ìwó ni Olúìwó bá pé é l'áwo. Ọ̀rúnmìlà kí Ifá fún Olúìwó, ó já Ifá. Ara kò rọ̀ wọ́n ni ilú Ìwó ni wọ́n dá Ifá sí. Ọ̀rúnmìlà ní ẹbọ ni kí wọn ó rú. Wọ́n rú'bọ. Gbogbo ǹkan tí ó le fún wọn ní ilú Ìwó, ara bẹ̀rẹ̀ sí ní rọ̀ wọ́n; ara kò ni wọ́n mọ́. Gbogbo ǹkan wọn bẹ̀rẹ̀ sí ní dára; ni Olúìwó bá ro'nú títí wípé kíni òun lè fi ta Ọ̀rúnmìlà l'ọ́rẹ. Olúìwó sì ní ọmọbìnrin kan, ni ó bá fi fún Ọ̀rúnmìlà wípé kó fi ṣe aya. Ni Ọ̀rúnmìlà bá mú ọmọbìnrin yìí lọ sí ilé rẹ̀. Bí Ọ̀rúnmìlà bá ṣe awo lọ, ìgbàtí yí óò bá fi padà dé ilé, ìyàwó rẹ̀ yí óò ti la ọpọ́n Ifá dá'ná. Ó sá à ńṣe ǹkan tí ó lè bí Ọ̀rúnmìlà nínú, ṣùgbọ́n kàkà kí Ọ̀rúnmìlà ó bínú, ó ńfi ara dà á. Ìgbàtí ó di ọjọ́ kan ni ìyàwó yìí náà bá ro'nú wípé ẹni tí òun ńṣe gbogbo àìdára wọ̀nyí sí tí kò bínú, à jẹ́ wípé yí óò lè sin òun. Báyìí ni ó yí ìwà padà tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí ní hu ìwà rere. Báyìí Ọ̀rúnmìlà padà wá sí ilé pẹ̀lú ìyàwó rẹ̀. Bí wọ́n ṣe rí obìnrin yìí ní ẹ̀yìn Ọ̀rúnmìlà wọ́n ńbèèrè l'ọ́wọ́ rẹ̀ wípé, "Tani eléyìí?" Ọ̀rúnmìlà wá ńdá wọn l'óhùn wípé, "Ìyà tí mo jẹ ní Ìwó niyi." Ìyà ni wọ́n ńpè ní ìyàwó. Ifá ńfi eléyìí kọ́ wa ní ẹ̀kọ́ wípé kí a ní ìfaradà l'órí ohun gbogbo.

3. Ifá pé òun pé ire àìkú fún ẹni tí ó dá Ogbè Yọ̀nù. Ifá pé òun yí óò ba ṣẹ́'gun ọ̀tá lọ́pọ̀lọpọ̀.

Sẹ̀gi dúdú l'awo inú igbó
Àyinrin a b'ẹ̀dọ̀ gọ̀lọ̀ǹtọ̀
Báàbà ni i ṣ'awo ayé
A d'Ifá fún Ngò-ni-ṣe-bàyìí-kú
Tí i ṣe ọmọ Onipàpósin
L'ọ́jọ́ tí i r'ayé alàiníikú.

Ngò-ni-ṣe-báyìí-kú ti Ifá ṣọ yìí, ènìyàn ni í ṣe. Àwọn ọ̀tá pọ̀ fún, wọ́n si ńléri si wípé àwọn yi òò ma wo bí yi òò ṣe gbé ilé ayé, wípé àwọn kò ni jẹ́ki ó ri ilé ayé gbé. Báyìí ni wọ́n ńrán àwọn ajogun ibi si. Kò mọ èyíti yi ó ṣe mọ̀. Ni ó bá gba oko aláwo lọ. Àwọn awo yàn án l'ẹ́bọ. Kí ó lè ṣẹ́'gun àwọn ọ̀tá rẹ̀ ni kí ó rú'bọ si. Báyìí ni ó bẹ̀rẹ̀ si ni iṣẹ́gun àwọn ọ̀tá rẹ̀. Ikú ti àwọn ọ̀tá rẹ̀ sọ wípé yi òò kú, Ngò-ni-ṣe-báyìí-kú kò kú mọ́. Àwọn ọ̀tá rẹ̀ lò bẹ̀rẹ̀ si ni kú. Ó ńyìn Awo, Awo ńyìn Ifá, Ifá ńyìn Elédùmarè ọba l'ọ̀run. Ó ni bẹ́ẹ̀ l'àwọn Awo wí pé:

Sẹ̀gí dúdú l'awo inú igbó
Ayìnrìn a b'ẹ̀dọ̀ gọ̀lọ̀ńtọ̀
Báábá ni i ṣ'awo ayé
A d'Ifá fún Ngò-ni-ṣe-báyìí-kú
Tí i ṣe ọmọ Onípàpósìn
L'ọ́jọ́ ti i r'ayé aláìníikú
Ifá ngò ni ṣe báyìí kú
À gbó ra koro ni ti igbín
Bí ẹyẹ ológoṣẹ́ bá gbógbógbó
A dábi èwe
Àgbò mí kàn ńkò kú mọ́
Ọdọọdún l'ewé erúwà ma ńhùn
Ajídèwe ni ti eku èlérí.

4. Ifá pé òun pé ire ọmọ fún ẹni tí ó dá Ogbè Ògúndá. Ifá pé ibeji ni yi òò bí. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú.

Àbọ̀ wá l'éré ọjà
A d'Ifá fún aláteòde
Tí yí òò l'óyún Ogbè òun Ògúndá ninú.





Aláteòde ti Ifá ńsọ yìí, àgàn ni. Ojú ọmọ pọ́n-ọn gidigidi. Ó bẹ̀rẹ̀ si ni ro'nú. Ó yá ó lọ réé ṣe àyẹ̀wò. Wọ́n ni yi òò bí'mọ, ẹbọ ni kí ó rú wípé ibeji ni yi òò fi bí. Ó rú'bọ. Ìgbàtí yi òò bí'mọ, ó bí ibeji. Idí niyi ti a fi ńpe orúkọ Odù yi ni Ogbè Yọ̀nú.

Àbọ̀ wá l'éré ọjà
A d'Ifá fún Aláteòde
Tí yí òò l'óyún Ogbè òun Ògúndá ninú
Aláteòde wa fi ohun okùn silẹ̀
Ide lọ̀ fi ńkẹ́ ọmọ
Àbọ̀ wá l'éré ọjà.

***Translation***

1. Ifá says *ire* for whomever Ogbè Ògúndá comes out for. Ifá says two people are desperate for children. Ifá says the people should make ẹbọ in order to have the children.

**Ẹbọ:** *1 female goat.* Ifá's authority for this message is as follows:

Oká (gaboon viper) marvels in its majestic throne
Oká behaves majestically
Erè (Royal python) marvels in its majestic mud-throne
Divined for a beautiful barren ***black*** woman
Divined same for a light complexioned one
They were crying for lack of children.

In ancient time, there were two barren people; they were òro (fleshy Yorùbá fruit) and *osàn àgbàlùmò* (a Yorùbá orange-like fruit). Òro and àgbàlùmọ̀ were so desolate with their childlessness that they cried all the time incessantly. Before giving up hope, however, they consulted Ifá. They asked Ifá if they would ever bear children. Ifá assured them that they would have children but to make ẹbọ. Àgbàlùmọ̀ was the first to make the ẹbọ, it offered a small goat for ẹbọ. Therefore, when àgbàlùmọ̀ started having children, the children were all small. Seeing that àgbàlùmọ̀ was able to have children by virtue of the ẹbọ, òro rushed to make its own ẹbọ and sacrificed a big goat. When òro was to have its own children, the children were all big. Àgbàlùmọ̀ and òro were happy for their precious gifts, and they praised their Awo. Their Babaláwo praised Ifá [Ọ̀rúnmìlà], and Ifá praised Olódùmarè. They said:

Ọká (gaboon viper) marvels in its majestic throne
Ọká behaves majestically
Erè (Royal python) marvels in its majestic mud-throne
Divined for the beautiful barren ***black*** woman
Divined same for the light complexioned one
Òro (personified) is the beautiful black barren person here
Àgbàlùmò (personified) is the light complexioned person here.

2. Ifá warns whomever Ogbè Yọ̀nù comes out for not to disrespect people who are his/her senior either by age or by position. Ifá also recommends ẹbọ.





Anger does no good
Patience is the father of good character
An elder blessed with the wisdom of patience
Has everything
Divined for Ọ̀rúnmìlà
The day he went on spiritual journey to Ìwó
When he went there to marry Ìyá, the daughter of the king of Ìwó.

Ọ̀rúnmìlà went on a spiritual journey to Ìwó town. When he got there, the king of Ìwó invited him for divination. Ọ̀rúnmìlà divined for the king and told him precisely what the problem with the king was. The problem was that the people of Ìwó were in hardship, and that was the main reason for the king's consultation with Ifá. Ọ̀rúnmìlà told them to make ẹbọ. Ìwó people made the ẹbọ, and their hardship disappeared as soon as the ẹbọ was made. Everything started being good for them. The king was happy and impressed by the Ifá work done for his people that he decided to show his gratitude to Ọ̀rúnmìlà. He thought of how best he could compensate Ọ̀rúnmìlà for the relief he brought to his people. Meanwhile, the king had a daughter who was ripe for marriage. The king, therefore, gave the daughter to Ọ̀rúnmìlà as wife. Ọ̀rúnmìlà took the princess as his wife and continued to live in Ìwó - for only a while though. Each and every time Ọ̀rúnmìlà went on his spiritual journey, the princess/apètèbí would destroy some of Ọ̀rúnmìlà's Ifá paraphernalia. One time she split ọpọ́n Ifá and used it as firewood. She did all these things to provoke Ọ̀rúnmìlà, but Ọ̀rúnmìlà never showed any anger. One day, however, the princess thought to herself that definitely Ọ̀rúnmìlà was the right man for her because Ọ̀rúnmìlà was probably

the only man who would take all the ugly things she did without a single revenge. The princess changed her bad attitude to a good one.

With this change of good character, Ọ̀rúnmìlà decided to go home, and he took the princess with him. As soon as Ọ̀rúnmìlà got home, neighbors and friends started asking him, "Who is this woman?" Ọ̀rúnmìlà's answer to the question was, "Ìyà tí mo jẹ ni Ìwó rè é," meaning "This is my suffering in Ìwó town." Therefore, "Ìyà tí mo jẹ ni Ìwó" metamorphosed to **ìyàwó.**

*Àṣẹ:* Ifá teaches us a lesson here that we should have patience in whatever we do.

3. Ifá predicts longevity for whomever Ogbè Ògúndá comes out for. Ifá also predicts victory over all adversaries.

Black sẹ̀gi is the divider of the wood
Báábá is the diviner for earth
Divined for *I-will-not-die-poor*
Child of Onípàpósin
When he was going to enjoy a "***life without end***".

*I-will-not-die-poor* was a person surrounded by many jealous enemies who prayed for his downfall. As part of their plot, these enemies sent spells and even contracted the help of evil forces to bring down *I-will-not-die-poor*. When *I-will-not-die-poor* was tired of running away from these enemies, he consulted Ifá for help and protection. The Babaláwo told him that he had to make ẹbọ to overcome the enemies.





*I-will-not-die-poor* made the ẹbọ. As soon as he made the ebo, evil machinations of the enemies went back to them; they died of their plots. Therefore, *I-will-not-die-poor* started praising the Babaláwo; the Babaláwo praised Ifá [Ọ̀rúnmìlà], and Ifá praised Olódùmarè in heaven. *I-will-not-die-poor* said his awo assured him that:

Black sẹ̀gi is the divider of the wood
Báábá is the diviner for earth
Divined for *I-will-not-die-poor*
The child of Onípàpósin
When he was going to enjoy a "***life without end***"
Ifá says, "*I-will-not-die-poor*"
Longevity, that is how the tortoise lives
Longevity, that is how the snail lives
The longer ológosẹ̀ (bird) lives, the younger it looks
I will not die anymore
Every year, I am alive
Baby-fresh is how eléri (rat) looks.

*Àṣẹ:* Ifá will make us victorious over our enemies.

4.
Ifá says he will bless the person that Ogbè Ògúndá comes out for with twin babies. Ifá says make ẹbọ.

Profit in sales makes the seller happy
Divined for Alátẹ̀ọ̀de (a seller)
Who was pregnant with Ogbè and Ògúndá.

Aláteọ̀de was a barren woman who was desperate for a child and was very troubled with the childlessness. To solve the problem, she went to a Babaláwo to consult Ifá. The Babaláwo assured her that she would have a child, but to make ẹbọ and that after the ẹbọ, she would have twins. Aláteọ̀de made the ẹbọ; she became pregnant. When it was time for delivery, she delivered twin babies. That is why this Odù is called Ogbè Yọ́nú.

Profit in sales makes the seller happy
Divined for Aláteọ̀de (a seller)
Who was pregnant with Ogbè and Ògúndá
Aláteọ̀de became so prosperous that
She pampered her children with expensive things
Profit in sales makes the seller happy.



# Ẹ̀sán (9)

## Ogbè-Sá

1.

Ọwọ́ ri iyán, ọwọ́ y'ókè
Àtàǹpàkò ló ri àgbàdo òjò ló ṣe mùlúnkú mùlúnkú
A d'Ifá fún Ọ̀rúnmìlà
Yí óò gb'ọ́mọ rẹ̀ sá g'àjà nítorí ikú.

Ọ̀rúnmìlà ni ó fura sí àwọn ọ̀tá nígbàtí wọ́n ńbá a jà; Ni ó bá gbé ọ̀kẹ́ìpọ̀nrí rẹ̀ ka'lẹ̀ ó pé àwọn Awo, wọ́n ba dá Ifá. Wọ́n ní ẹbọ ni kí ó rú. Wọ́n yàn-án l'ẹ́bọ, ó rú'bọ. Àsìkò tí àwọn ọ̀tá bá ńrán àwọn ajogun ibi, wọn kiì bá Ọ̀rúnmìlà ni ilé, wọn kò ni bá ọmọ rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni wọn kò ni bá ìyàwó rẹ̀. Ni àwọn ajogun ibi bá ńfi àbọ̀ s'órí àwọn ọ̀tá Ọ̀rúnmìlà. Ó ní:

Ọwọ́ ri iyán, ọwọ́ y'ókè
Àtànpàkò ló ri àgbàdo òjò ló ṣe mùlúnkú mùlúnkù
A d'Ifá fún Ọ̀rúnmìlà
Yí óò gb'ọ́mọ rẹ̀ sá g'àjà nítorí ikú
Ikú wọ'lé mi kò bá mi

Kèrègbè òfifo o mà kú àrin nù
Àrùn wọ'lé mi kò bá mi
Kèrègbè òfifo o mà kú àrin nù
Gbogbo ajogun ibi wọ'lé mi wọn kò bá mi
Kèrègbè òfifo o mà kú àrin nù.

2.
Ìbàjẹ́ owó kò lásànú
A d'Ifá fún Ọ̀rúnmìlà
L'ọ́jọ́ tí ó ńr'oko rèé lá.

Ọ̀rúnmìlà ni ó fẹ́ ṣ'awo lọ sí igbèriko, ni ominú wá ńkọ ọ́ wípé àbí kí òun ó lọ tàbí kí òun ó má lọ. Ni ó bá gbe òkèìpònrì rẹ̀ ka'lẹ̀, ó pé àwọn Awo, àwọn Awo ba dá Ifá, wọ́n ní ẹbọ ni kí ó rú wípé Ọ̀rúnmìlà yí óò lá wá'lé láti ibẹ̀ ni. Wọ́n bá yan Ọ̀rúnmìlà l'ẹ́bọ. Ó rú'bọ. Ó de ibẹ̀, ẹni tí kò rí ṣe, Ọ̀rúnmìlà ṣe Ifá fún wọn, onikálukú bẹ̀rẹ̀ sí rí ṣe. Báyìí ni wọ́n ṣe ńkó ẹrú kò ẹní fún Ọ̀rúnmìlà tí ó sì tí oko lá wá'lé. Ó ní:

Ìbàjẹ́ owó kò láṣànú
A d'Ifá fún Ọ̀rúnmìlà
L'ọ́jọ́ tí ó ńr'oko rèé lá
Ó ní Ogbè Sá òòò
Ogbè lá
Ogbè ló r'oko rèé lá.

*Àṣẹ:* Ifá pé kí ó rú'bọ kí ó le ba ni ire lọ́pọ̀lọpọ̀.





3. Ifá pé ẹni tí ó dá Ogbè-Sá, Ifá pé yí óò ní olùsin lọ́pọ̀lọpọ̀, ẹbọ ni kò rú.

Gbọ̀mù-gbọ̀mù ṣigidi
Ṣigidi gbọ̀mù -gbọ̀mù
A d'Ifá fún ọba l'Ọ̀yọ̀ọ́
Ọmọ amúgba igbin p'ẹ̀rọ̀ lóyè
Gbọ̀mù-gbọ̀mù ṣigidi
Ṣigidi gbọ̀mù-gbọ̀mù.

Ọba l'Ọ̀yọ̀ọ́ tí Ifá ńsọ yìí kò ní olùsin, ni ó bá pe Awo wípé kí wọn ó bá òun se iwádìí rẹ̀ ohun tí ó fàá. Wọ́n ní ẹbọ ni kí ó rú, kí ó fi igba igbin bọ Odù; wọ́n ní yí óò ní olùsin. Wọ́n yán-án l'ẹ́bọ. Ó rú'bọ. Wọ́n bá fi igba igbin bọ Odù. Kò i pẹ́ ni ọba 'Lọ́yọ̀ọ́ bá bẹ̀rẹ̀ sí ní olùsin. Alárá fi olùsin ránṣẹ́ sí ọba l'Ọ̀yọ̀ọ́, Ajerò náà fi ránṣẹ́, Ọwáràngún náà bẹ̀ẹ̀, báyìí ni ọba 'Lọ́yọ̀ọ́ bẹ̀rẹ̀ sí ní olùsin lọ́pọ̀lọpọ̀. Ó wa ńyin Awo, Awo ńyin Ifá. Ó ní:

Gbọ̀mù-gbọ̀mù ṣigidi
Ṣigidi gbọ̀mù -gbọ̀mù
A d'Ifá fún ọba l'Ọ̀yọ̀ọ́
Ọmọ amúgba igbin p'ẹ̀rọ̀ lóyè
Gbọ̀mù-gbọ̀mù ṣigidi
Ṣigidi gbọ̀mù-gbọ̀mù
Alárá a ó sin
Gbọ̀mù-gbọ̀mù ṣigidi
Ṣigidi gbọ̀mù-gbọ̀mù
Ajerò a ó sin
Gbọ̀mù-gbọ̀mù sigidi
Ṣigidi gbọ̀mù-gbọ̀mù

Ọwárángún a ó sin
Gbọ́mú-gbọ́mú ṣigidi
Ṣigidi gbọ́mú-gbọ́mú.

4.
Àtiòro Ìbíní
Ògòngò Ìjámọ̀
Àgbìgbò n'Ìwọnràn
Àwọn ni wọ́n ṣ'awo ọba 'Léyọ̀ kanhan
A d'Ifá fún Oridára
Tíí ṣe ẹrú Ọ̀ṣọ̀run àkọ̀kọ̀.

Oridara ti Ifá ńsọ yii, tálákà ni, kò rí ṣe; ojú npon ó gidigidi; ẹrú tún ni. Ó wá pinu wípé kinni òun lè ṣe, àti wípé ọ̀nà wo ni òun lè gbà tí yí óò fi dára fún òun. Ó ní ohun tí òun lè ṣe ni wípé kí òun ó fi ìlú sílẹ̀ lọ sí ibòmírán. Ṣùgbọ́n kí òun ó tó lọ, òun ó ṣe iwádìí. Ni ó bá lọ sí ọ̀dọ̀ àwọn Awo. Àwọn Awo ní kí ó tó lọ, kí ó rú 'bọ, kí orí rẹ̀ lè bá gbe dé ibi tí yí óò ti là. Ó gbọ́ rírú ẹbọ ó rú. Ẹbọ tún, ẹbọ dà, ni ó bá gbéra ó lọ. Ìgbàtí Oridára dé ibẹ̀, ẹsẹ̀ rẹ̀ gbe dé ibi tí yí óò tí là. Oridára bẹ̀rẹ̀ sí níí yọ̀, inú un rẹ̀ dùn. Ó ńyin Awo, àwọn Awo ńyin Ifá, ó ni bẹ́ẹ̀ l'àwọn Awo wí:

Àtiòro Ìbíní
Ògòngò Ìjámọ̀
Àgbìgbò n'Ìwọnràn
Àwọn ni wọ́n ṣ'awo ọba 'Léyọ̀ kanhan
A d'Ifá fún Oridára
Tíí ṣe ẹrú Ọ̀ṣọ̀run àkọ̀kọ̀
Ibi rere t'órí ńgbé mi rè, nkò mọ ibẹ̀





Ẹ̀fúfù lẹ̀lẹ̀ lò tí ńgb'àtiìòro rè 'Bini
Ibi rere t'órí ńgbé mi rè, nkò mọ bẹ̀.

*Àṣẹ:* Ifá pé ẹni tí ó dá Ogbè-Sá, Ifá pé ẹbọ ni ó rú, kí orí i rẹ̀ lè ba gbe dé ibi ire tí yió tí là.

*Translation:*

1.
Hand goes up when it sees *iyán* (pounded yam) - food
The big toe is happy on sighting fresh corns
Divine for Ọ̀rúnmìlà
Who will hide his children in the attic because of death.

Ọ̀rúnmìlà was very uneasy when enemies waged war against him as a result of which he consulted his Babaláwo for divination. They divined for him and told him to make ẹbọ. They gave him a list of the things required for ẹbọ. All the evil messages from Ọ̀rúnmìlà's enemies never touched him after he made the ẹbọ. The ẹbọ also shielded Ọ̀rúnmìlà's wife and children. As a result of the potency of the ẹbọ, the evil forces returned to the enemies. Ọ̀rúnmìlà said:

Hand goes up on sighting *iyán* (pounded yam) - food
The big toe is happy on sighting corns
Divine for Ọ̀rúnmìlà
Who will hide his children in the attic because of death
Death came to my house and missed me
Empty calabash, you just wasted your time

All evil forces came to my house and missed me
Empty calabash, you just wasted your time.

2.

No one throws away money even if it is dirty
Divine for Ọrúnmìlà
Who will be rich from dealing with people in the village.

Ọrúnmìlà was to go to a remote village for his spiritual work, but the prospect of the journey bothered him. He was, therefore, torn between two decisions - whether to go or not to go. To get a clear understanding, Ọrúnmìlà summoned his Awo to divine for him. His Awo consulted Ifá. They told him to make ẹbọ. They also assured him that the journey would profit him, and that he would reap lots of reward from the venture. They gave him a list of things needed for ẹbọ. Ọrúnmìlà provided everything, and ẹbọ was made for him. Ọrúnmìlà left for the journey as soon as the ẹbọ was finished. Getting to the village, people with various problems started consulting him. Ọrúnmìlà divined and solved all their problems. Those who were in hardship before Ọrúnmìlà got there experienced positive changes soon after the ẹbọ he made for them. Barren women started having children. The sick were healed. In fact everything changed from bad to good for people in the village. The people were so happy for the wonderful changes in their lives that they showered Ọrúnmìlà with lots of expensive gifts.

No one throws away money even if it is dirty
Divine for Ọrúnmìlà





Who will be rich from dealing with people in the village
He exclaimed, "Ogbè-Sá óòò, that is 'Ogbè-enriches'"
Ogbè went to a remote place to get riches.

*Àṣẹ:* Ifá says the person that Ogbè-Sá comes out for is planning to go on a journey. Ifá says the place that the person is going will be beneficial to him/her, that the person will reap plenty rewards from there. Ifá recommends ebo so that the person will not miss any of these good things that Ifá foresees.

3. Ifá says the person that Ogbè-Sá comes out for will have disciples (or followers or god-children), but to make ẹbọ.

Gbọ́mú-gbọ́mú ṣigidi
Ṣigidi gbọ́mú-gbọ́mú
Divined for Ọ̀yọ́ King
Who offered 200 snails to Ọbàtálá for peace in his domain
Gbọ́mú-gbọ́mú ṣigidi
Ṣigidi gbọ́mú-gbọ́mú.

The king that Ifá is talking about had no subjects during the time of this mythological story; therefore, he consulted his Babaláwos to help inquire what the problem was. They told him to make ẹbọ; they told him to offer 200 snails to Odù. They also assured him that if he did the ẹbọ, he would have many subjects. They gave him additional list of ebo things. The king made the ẹbọ. The Babaláwos offered the 200 snails to Odù. Soon after the ẹbọ, the king started having subjects. Alárá (king of Ìlárá Èkìtì) sent him many subjects, Ajerò (King of Ìjerò Èkìtì) sent him many subjects, Ọwárángún Àga (King of

Ọ̀ràngún Ìlà) sent him many subjects, all other kings sent him many subjects. Ọba 'Lọ́yọ̀ọ́ (King of Ọ̀yọ́) had many subjects by the generosities of his king-brothers. Therefore, he started praising his Awo, and his Awo [Babaláwo] praised Ifá saying:

Gbọ́mú-gbọ́mú ṣigidi
Ṣigidi gbọ́mú-gbọ́mú
Alárá we will worship
Gbọ́mú-gbọ́mú ṣigidi
Ṣígidi gbọ́mú-gbọ́mú
Ajeró we will worship
Gbọ́mú-gbọ́mú ṣígídi
Ṣigidi gbọ́mú-gbọ́mú
Ọwárángún we will worship
Gbọ́mú-gbọ́mú ṣigidi
Ṣigidi gbọ́mú-gbọ́mú.

4.

Hornbill of Benin town
Ostrich of Ìjamú town
Ògbigbò of Ìwọnràn town
They are the diviners for king of Ọ̀yọ́
Divined for Oridára *(good-destiny)*
Who was a slave to the first Ọ̀ṣọ̀run.

Orídára in reference here was a very poor man. His poverty was to the extreme. On top of that, he was a slave. He thought about his position in life and about what he could do to improve his life. He decided to leave that town for another place. At the same time, he decided to consult Ifá before going





on his mission. Therefore, he went to some Babaláwo. They divined for him and told him that before he left town, he should make ẹbọ to his *orí* so that his *orí* would lead him to a place that would benefit him in terms of success and good health. As soon as he was told the ẹbọ, he made the ẹbọ. Thereafter, he left for the journey. When he got there, his *feet* led his *orí* to a good spot. That good spot helped him to achieve all the good things he had aspired for in life. Oridára started having riches, and he was very happy for this positive changes in his life. Therefore, he started to praise the Babaláwo, and the Babaláwo praised Ifá saying:

Hornbill of Benin town
Ostrich of Ìjamú town
Ògbigbò of Ìwọnràn town
They are the diviners for king of Ọ̀yọ́
Divined for Oridára *(good destiny)*
Who was a slave to the first Ọ̀ṣọ̀run
The good place that *orí* is leading me, I do not know
It was a good wind that helped àtíòro to Benin town
The good place that *orí* is leading me I do not know.

*Àṣẹ:* Ifá recommends ẹbọ for whomever Ogbè-Sá comes out for so that the person's ori will help change his/her life for the better.

# Ẹ̀wá (10)

## Ogbè-Ká

1.

Ogbè-Ká re'lé ọmọ ọṣin
Ogbè Ká re'lé ọmọ ọrà
Ogbè Ká re'lé ọmọ alákòko gùnlele alede
Àkéké sayin sàyin tó bá yan pa gédé
A sì yan ṣe gédé
A d'Ifá fún Adéyẹri ọmọ Olówu Màyini.

Adéyẹri ti Ifá ńsọ yìí, wọ́n ní kí ó rú'bọ kí ó lè ba jèrè ọmọ. Àbíkú pọ̀ fun; tó bá bí'mọ, àwọn ọmọ kò dúró l'ọ́wọ́ Adéyẹri. Ó ro'nú kínni òun lè ṣe, ni ó bá gba ilé aláwo lọ. Òun lè j'èrè ọmọ ló dá Ifá sí. Wọ́n ní yí óò j'èrè ọmọ, ẹbọ ni kí ó rú. Wọ́n yan Adéyẹri l'ẹ́bọ, ó rú'bọ. Ẹbọ fín, ẹbọ dà. Òun ti ó ti ńbí àbíkú, kò bí àbíkú mọ; ọmọ bẹ̀rẹ̀ sí ni dúró l'ọ́wọ́ rẹ̀. Diẹ̀ diẹ̀ ó di ẹni ti ó ńjẹun ọmọ; ó di ẹni ti ó ńj'èrè ọmọ. Inú Adéyẹri bẹ̀rẹ̀ sí ni dùn. Ó nyin Awo, Awo nyin Ifá, Ifá ńyin Elédùmarè ọba l'ọ́run. Ẹnu ti ó yà kótó, orin awo ló bọ sí l'ẹ́nu, ó ní:



Ogbè-Ká re'lé ọmọ ọṣin
Ogbè Ká re'lé ọmọ ọrà
Ogbè Ká re'lé ọmọ alákòko gùnlẹlẹ alẹde
Àkéké sayin sayin to bá yan pa gede
A sì yan ṣe gédé
A d'Ifá fún Adéyẹri ọmọ Olówu Màyini
Ọmọ l'èrè ayé o, ọmọ l'èrè
Ọmọ l'èrè ayé o, ọmọ l'èrè
Adéyẹri dé ọmọ Olówu Màyini o
Ọmọ l'èrè ayé o, ọmọ l'èrè.

*Àṣẹ:* Ifá pé ẹni ti ó dá Ogbè-Ká ńbí àbíkú. Ifá pé ẹbọ ni ó rú ti yí óò fi j'èrè ọmọ.

2.

Apẹ̀rẹ̀bugbàjẹ̀
Ló d'Ifá fún ọkọ́ tuntun (Òrìṣà Oko)
Ti ńlọ Òde Ìràwọ̀ (ilú kan ní Ilẹ̀ Yorùbá)
Ti ó ńlọ rèé gbọ'ṣin, gb'ọrà.

Ọkọ́ tuntun ti Ifá ńsọ yìí ni ó fẹ́ rin irin àjò lọ sí Ìràwọ̀; ominú wá ńkọ ọ́ wípé òun kò mọ bí ibẹ̀ yí óò ti rí fún òun, bóyá ibẹ̀ yí óò dára fún òun tàbí ibẹ̀ kò ní san fún òun. Ló bá mú ééjì kún ẹ́ẹ̀ta, ó lo s'òko aláwo. Wọ́n dá Ifá, wọ́n ní ibikan ni eléyiun fẹ́ lọ wípé ẹbọ ni kí ó rú. Wọ́n yàn án l'ẹ́bọ. Ó rú'bọ. Ọkọ́ tuntun gbéra, ó lọ sí Òde Ìràwọ̀, ó de ibẹ̀, wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí ni pè é l'áwo, ó ńríṣe. Ibẹ̀ rọ̀ ọ́ l'ọ́run, ni ó bá nyin Awo, àwọn Awo nyin Ifá, ẹnu ti ó ṣe kótó, orin Awo ni ó bọ́ sí l'ẹ́nu ó ńṣe:

Apẹ̀rẹ̀bugbájẹ̀
Ló d'Ifá fún ọkọ̀ tuntun (Òrìṣà Oko)
Tí ńlọ Òde Ìràwọ̀ (ìlú kan ní Ilẹ̀ Yorùbá)
Tí ó ńlọ réé gbọ'ṣin, gb'ọrá
Kí l'Apẹ̀rẹ̀bugbájẹ̀
Awo rere l'Apẹ̀rẹ̀bugbájẹ̀
Awo rere.

3.
Bùtù-bùtù ọ̀nà ẹyọ
Ó k'ọmọ ní irin ẹsẹ̀
Yinyan ló ńk'ọmọ
A d'Ifá fún Ogbè [Ọ̀rúnmìlà]
L'ọ́jọ́ tí ó ńṣawo lọ Ọ̀yọ́ Ilé.

Ọ̀rúnmìlà ni ó ṣ'awo lọ sí òde Ọ̀yọ́. Ìgbàtí Ọ̀rúnmìlà dé Òde Ọ̀yọ́, ó bẹ̀rẹ̀ sí ṣe Ifá fún wọn. Gbogbo ǹkan wọn bẹ̀rẹ̀ sí ní dára l'Òde Ọ̀yọ́. Diẹ̀-diẹ̀ ni àwọn tí ó wà ní igbèríko bá tún ńpe Ọ̀rúnmìlà l'áwo. Ọ̀rúnmìlà kò fẹ́ padà s'ilé mọ́. Àwọn ará Ọ̀yọ́ kò fún l'áyè láti padà mọ́. Kò pẹ́ àárò ilé ńsọ Ọ̀rúnmìlà, lẹ́hìn ìgbàtí Ọ̀rúnmìlà ti gba ẹní gba ẹrú ni ó bá gbéra padà sí ilé pẹ̀lú inú dídùn. Ó la'nu, orin Awo ló bọ́ sí l'ẹ́nu, ó ní:

Ogbè-Ká re'lé o
Má sùn n'íjù
Awo tí ó gbọ́'Fá rere kìí gbé'jù.

*Àṣẹ:* Ifá kí eléyìun ó rú'bọ kí ire lè bá dé fún-un l'ọ̀nà irin àjò tí ó fẹ́ẹ́ lọ yẹn.





4.
Ogbè -Ká rè káá kàjà
A d'Ifá fún Ètìpọ́nọlá aya Ehoro.

Ètìpọ́nọlá tí Ifá ńsọ yìí, ìyàwó Ehoro ni í ṣe l'áyé àtijọ́. Ní o bá pinu láti kọ ọkọ rẹ̀ Ehoro sílẹ̀. Ní ó bá lọ se àyẹ̀wò l'ọ́dọ̀ àwọn Awo. Òun fẹ́ kọ ọkọ òun sílẹ̀ ni ó dá'Fá sí. Wọ́n ní kí ó ma kọ ọkọ rẹ̀ sílẹ̀. Wọ́n ní tí ó bá sì mọ̀ pé òun fẹ́ kọ̀ ọ́, kí ó rú'bọ. Wọ́n ní tí kò bá rú'bọ yì òò tún padà sí ọ̀dọ̀ Ehoro. Ètìpọ́nọlá fi gbígbọ́ ṣe aláìgbọ́ kò rú'bọ. Ní ó bá kọ Ehoro sílẹ̀. Ṣùgbọ́n nígbàtí ó dé ibòmíràn, kàkà kí ara ó dẹ̀ ẹ́, ńṣe ni ó túbọ̀ tún ńburú sí fún Ètìpọ́nọlá. Kò pẹ́ kò jìnà, ni ó bá tún ro'nú wò wípé ibití òun ti kúrò tún dára ju ibití òun wà yì lọ. Òun ó kúkú tún padà lọ sí ọ̀dọ̀ Ehoro. Ní Ètìpọ́nọlá bá tún padà sí ọ̀dọ̀ Ehoro, ni ó bá ńkorin wípé:

Ètìpọ́nọlá aya Ehoro
Ètìpọ́nọlá aya Ehoro
Ngó sì tún padà tún ọkọ ọ̀ mi fẹ́.

*Àṣẹ:* Ifá pé kí ẹni tí ó dá Ogbè-Ká kí ó má ṣe kọ aya rẹ̀ sílẹ̀, tàbí kọ ọkọ rẹ̀ sílẹ̀.

*Ẹ̀kọ́:* Ifá yìí kò wa pé kí a ní ìforíti pẹ̀lú gbogbo ohun tí a bá ńṣe.

***Translation:***

1.

Ogbè, devoted Awo, let us go home,
Ogbè, a rich Awo, let us go home,
Ogbè let us go home, protector of akòko (Ògún's) tree
Brave Ogbè
Divined for Adéyẹri - child of Olúwo Máyiní.

Adéyeri in reference here was told to make ẹbọ to stop the continuous losses of his children - he suffered greatly because his children always died in their infancies. Adéyẹri was assured that his children will live if only he would make ẹbọ. Adéyẹri asked for the things needed for the ẹbọ, he was given the list. He provided the things and ẹbọ was made for him. The ẹbọ manifested, and his subsequent children lived. Adéyẹri was happy for this change in his life particularly seeing his children live. Adéyẹri was so jubilant that he started singing saying:

Ogbè, devoted Awo, let us go home,
Ogbè, a rich Awo, let us go home,
Ogbè let us go home, protector of akòko (Ògún's) tree
Brave Ogbè
Divined for Adéyẹri - child of Olúwo Máyiní
Children are the salt of life
Children are the salt of life
Children are the salt of life
Adéyẹri, child of Olówu Máyiní is happy
Children are the salt of life.

*Aṣẹ:* Ifá says the person that this Odù comes out for had suffered the loss of a child or children; therefore, the person should make ẹbọ to stop further losses.





2.

Apẹ̀rẹ̀bugbàjẹ̀
Divined for Ọkọ̀ tuntun (Òrìṣà Oko's alias)
When he was going to Ìràwọ̀ town
To receive good things.

Ọkọ tuntun in reference was going on a journey to Ìràwọ̀ town, but he was concerned about the prospect of the journey. Therefore, he consulted some Babaláwo for divination. The Babaláwo divined for him. They told him to make ẹbọ before he left for the journey. They told him the things needed for the ebo. Ọkọ tuntun made the ẹbọ and left for the journey afterwards. Getting there, Ọkọ tuntun's story was that of an instant success as everybody started contacting him for divinations. Ọkọ tuntun was very successful, so happy was he that he started to sing:

Who is Apẹ̀rẹ̀bugbàjẹ̀
Good Awo
Apẹ̀rẹ̀bugbàjẹ̀ is a good Awo.

3.

Sandy road is not smooth to walk on
Instead, it teaches a child to walk softly
Divined for Ọ̀rúnmìlà
When he going on spiritual journey to ancient Ọ̀yọ̀ town.

Ọ̀rúnmìlà went on a missionary journey to ancient Ọ̀yọ̀ town. When he got there, he divined and gave them potent Ifá medicines. Lives improved for citizens of ancient Ọ̀yọ̀ town.

Neighboring towns and villages invited Ọrúnmìlà for spiritual blessings when they noticed the positive changes that took place in ancient Ọ̀yọ́. From village to village, town to town, Ọrúnmìlà was busy, so busy that he almost decided not go back home. At a stage during this lengthy stay in ancient Ọ̀yọ́ neighborhood, Ọrúnmìlà started to miss his family, therefore, he decided to go back. Meanwhile, he had acquired many properties and was happy about this. With happiness and fulfillment, Ọrúnmìlà went back home, singing:

Ogbè let us go home
Do not take up residency in the wood
A versatile Babaláwo does not live in the woods.

***Àṣẹ:*** Ifá recommends ẹbọ for the improvement of whomever Ogbè-Ká comes out for.

4.
Ogbè let us go to Ìká
Divined for Ètipọ́nọlá, wife of Ehoro (rabbit).

Ètipọ́nọlá in reference was rabbit's wife in ancient time. Ètipọ́nọlá went for divination when she decided to divorce her husband. The Babaláwo divined for her and warned her not to divorce her husband, but if she wanted to divorce her husband at all cost, she should make ẹbọ. They also told her that she would go back to the husband she planned to divorce if she failed to make the prescribed ẹbọ. Ètipọ́nọlá did not make the ẹbọ and went ahead all the same and divorced her husband. She married somebody else, but instead of peace, life





was worse for her in her new marriage. When she could no more endure the hardship in her second marriage, she decided to go back to her ex-husband, Ehoro; therefore, she went back to Ehoro singing:

Ètipọ́nọlá, Ehoro's wife
I will re-marry my ex-husband.

***Àṣẹ:*** Ifá warns whomever this Ifá comes out for never to divorce his wife or her husband.

**Lesson from the Odù:** This verse of Ogbè-Ká recommends perseverance on whatever one does in life.



**Ọkọ̀ Tuntun**
(Alias of Òrìṣà Oko)

# Ọ̀kànlá (11)

## Ogbè Òtúrúpọ̀n (Ogbè-T'ọ́mọpọ̀n)

1.

Ogbè-tún-ọmọ-pọ̀n
Ogbè-sún-mọ-si
À gbà pọ̀n ò l'ẹ́rẹ̀
B'ọ́mọ bá ńsunkún iyá rẹ̀ ni à ńgbe fún
A d'Ífá fún Ìjòkùn
Tí ó ńlọ ilé Ìlúgún.

Ìjòkùn tí Ifá sọ yìí, ojú ọmọ ló ńpọn; kò rí ọmọ bí, ojoojúmọ́ ló ńf'omi ojú sùngbéré ọmọ. Ó di ọjọ́ yìí, ló bá pinu, ó mú ẹ́ẹ̀ji kún ẹ̀ẹ́ta ó gba oko awo lọ. Òun lè di ọlọ́mọ l'áyé ló dá'Fá si. Wọ́n ní yí óò bí'mọ, ẹbọ ni kó rú. Àwọn Awo yàn-án l'ẹ́bọ. Ó rú'bọ. Kò pẹ́ kò jìnà ó l'óyún. Ó bẹ̀rẹ̀ sí ni bí'mọ. Báyìí ni Ìjòkùn di ọlọ́mọ, tí ó sì ni ire gbogbo. Ó ni bẹ̀ẹ̀ l'àwọn Awo wí pé:

Ogbè-tún-ọmọ-pọ̀n
Ogbè-sún-mọ-si



À gbà pọ̀n ò l'ẹ́rẹ̀
B'ọ́mọ bá ńsunkún iyá rẹ̀ ni à ngbe fún
A d'Ífá fún Ìjòkùn
Tí ó ńlọ ilé Ìlúgún
Ó ní rírú ẹbọ nii gbe'ni
Àìrú kii gbe èniyàn
Kò i pẹ́, kò i jìnà
Ẹ wá bá mi ní ìjẹ̀bútú ire
Ìjẹ̀bútú ire là á bá'ni l'ẹ́sẹ̀ Ọbàrìṣà.

*Àṣẹ:* Ifá yìí kọ́ wa wípé kí a ní ìforítì; ìforítì dára púpọ̀ jù. Kí a sì má ma ṣe ìfẹ́ inú-u wa, kí a má ṣe àìgbọ́ràn.

2.

Kí là ńwá
Ló d'Ífá fún orí
Ohun tí a bá ńwá làá rí
Ló d'Ífá f'ọrùn
Arí gìdì ọmọ Ọlọ́tà
Ló d'Ífá f'ẹ́ni ilẹ̀
Tí wọ́n kìí t'ẹ́ni fún
Ẹni ilẹ̀ tí wọ́n kìí t'ẹ́ni fún láà pè ajé
Ìbòsí ajé ò
Ajé sọ ẹ̀wè d'àgbà
Ajé l'ẹni ilẹ̀ tí wọ́n kìí t'ẹ́ni fún.

Ajé tí Ifá s'ọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ yìí, àti orí, àti ọrùn; àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ọ̀rẹ́ ni wọ́n, tí wọ́n kìí ya ara wọn. Àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ́n kò ní iyì. Ó bùṣe gàdà, ó bùṣe gẹ́dẹ́ àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta mú ẹ́ẹ̀jì kún ẹ̀ẹ́ta, wọ́n lọ sí ilé aláwo wípé báwo ni àwọn ó ṣe gbayì l'áyé. Wọ́n ní ẹbọ

ni ki wọn ó rú. Wọ́n yan ẹnikọ̀ọ̀kan wọn l'ẹbọ. Àwọn méjì ló rú'bọ; orí àti ọrùn nikan ló rú'bọ. Ajé kò rú'bọ. Ó bùṣe gàdà, ó bùṣe gèdè, àṣẹ di àṣẹ Èṣù, ohun ayọ̀ dé, Èṣù paradà ó bèrè l'ọ́wọ́ Awo wípé, "Ṣé àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta rú'bọ?" Awo ní, "Orí àti ọrùn nikan ni ó rú'bọ." Ìgbàtí wọn ó ma rọ ire kan oníkálukú, wọ́n gbé adé ka'lẹ̀, wọ́n kó ìlẹ̀kẹ̀ ka'lẹ̀. Ǹjẹ́ tani yí óò ma lo adé, wọ́n ni orí ni. Wọ́n gbé adé ka orí rẹ̀. Ìlẹ̀kẹ̀ ńkọ́? Wọ́n ni ọrùn ni, wọ́n kó ìlẹ̀kẹ̀ bọ ọrùn. Àwọn ǹkan wọ̀nyí bá ara wọn mu. Ǹjẹ́ ajé ńkọ́? Ti èniyàn bá pa'wó, báyìíówù kó pọ̀ tó, wọn a sọ wípé, "Ẹ dáa sí'lẹ̀ ńbẹ̀hun ki wọn ó káà." Làti ìgbàyí ni ajé ti di ẹni ilẹ̀, ti orí àti ọrùn di ẹni iyì.

Ki là ńwá
Ló d'Ifá fún orí
Ohun ti a bá ńwá làá rí
Ló d'Ifá f'ọrùn
Ari gidi ọmọ Ọlọ́tà
Ló d'Ifá f'ẹni ilẹ̀
Ti wọ́n kìí t'ẹ́ni fún
Ẹni ilẹ̀ ti wọ́n kìí t'ẹ́ni fún láá pé ajé
Ìbòsí ajé ó
Ajé sọ ewé d'àgbà
Ajé l'ẹni ilẹ̀ ti wọ́n kìí t'ẹ́ni fún
Orí dé, orí d'ádé
Ọrùn dé, ó di ẹni ilẹ̀kẹ̀
Ajé d'ẹni ilẹ̀ ti wọn kìí t'ẹ́ni fún.

*Àṣẹ:* Ifá pé ẹni ti ó dá Ogbè-T'ọ̀mọ̀pọ̀n, Ifá pé òun pé ire iyì fún ẹni náà. Ifá pé ẹbọ ni ki ó rú. Ki ó si má fi etí pálábá ẹbọ náà.





3.
Yangi a b'orí kugu
A d'Ifá fún ọ̀pẹ̀ ẹ̀lújù
Ti ó ńsunkún p'óun kò bí'mọ
Wọ́n ni ẹbọ ni ki ó rú.

Ọ̀pẹ̀ ẹ̀lújù ti Ifá sọ yìí obìnrin ni; ó ya àgàn dé ibi wípé kò tilẹ̀ ní oyún àárọ̀ di alẹ́ rí. Ọ̀rọ̀ ara rẹ̀ su toripé igbà gbogbo ló ma ńronú wípé k'óun tiẹ̀ bí ẹyọ kan. Ó di ọjọ́ kan, ló bá mú ẹ̀éjì kún ẹ̀ẹ́ta ó lọ sí oko awo. Wọ́n ni yí óò bí'mọ, ẹbọ ni ki ó rú. Ni wọ́n bá yan-án l'ẹbọ. Ọ̀pẹ̀ ẹ̀lújù ó ṣe'yé méjì ló bá kó ẹbọ rú. Ó rú'bọ, kó pẹ́ kó jìnà, àṣẹ di àṣẹ Èṣù, ló bá l'óyún. Olódùmarè bá fún ọ̀pẹ̀ ni ọmọ rere. Ó bẹ̀rẹ̀ si ni f'inú ṣ'oyún, ó ńf'ẹ̀hìn gb'ọ́mọ pọ̀n. Ló bá ńyin Elédùmarè ọba l'ọ́run, ó ní:

Yangi a b'orí kugu
A d'Ifá fún ọ̀pẹ̀ ẹ̀lújù
Ti ó ńsunkún p'óun kò bí'mọ
Wọ́n ni ẹbọ ni ki ó rú
Rírú ẹbọ ni í gbe'ni
Àìrú kì í gbe èniyàn
Kèè pẹ́, kèè jìnà
Ẹ wá bá wa láàárín ọmọ
Àárín ọmọ là á bá ni l'ẹsẹ̀ Ọbàrìṣà.

*Àṣẹ:* Ifá yìí kọ́ wá kí a ní ìforítì l'orí àáyé k'àáyé ti a bá wà; kí a si ni ìfọkànbalẹ̀ wípé ohun gbogbo ti a bá bèrè l'ọ́wọ́ Olódùmarè ni yí óò ṣe fún wa.

4.

Ìjòkùn ofala
Ló d'Ifá f'Ólúgán tó ńna'wọ́ ire
Tí kò rí're
Wọ́n ni yi óò rí ire
Ẹbọ ni kí ó rú
O rú'bọ
Ire ńto l'ọ́wọ́.

Olúgán tí Ifá sọ yìí, ó ṣe ṣe ire kò to l'ọ́wọ́. Bó bá na'wọ́ sí ire kò ni i to l'ọ́wọ́, pábo ni gbogbo ǹkan maá já sí fun. Ire kì i to l'ọ́wọ́. Kì í ṣe ọ̀gángán ire kankan. Ó mú ẹ́ẹ́jì kún ẹ̀ẹ́ta, ó lọ sí oko awo. Àwọn Awo yán-án l'ẹ́bọ kí ire ó lè bá a to l'ọ́wọ́ ni wọ́n bá yán-án l'ẹ́bọ. Ó rú'bọ. Olúgán bá ni ire. Gbogbo ohun tí kò tí to l'ọ́wọ́, ni ó ńto l'ọ́wọ́. Ó ńṣ'orí ire, inú-u rẹ̀ ndùn, Ó ńdúpẹ́ l'ọ́wọ́ Olódùmarè.

Ìjòkùn Òfàlà
Ló d'Ifá f'Ólúgán tó ńna'wọ́ ire
Tí kò rí're
Wọ́n ni yi óò rí ire
Ẹbọ ni kí ó rú
O rú'bọ
Ire ńto l'ọ́wọ́
Gbogbo Awo àti Ìjòkùn Òfàlà
Ẹ jẹ́ kí a dúpẹ́ f'Ólúgán wípé Ifá ṣeun.

*Àṣẹ:* Ifá yìí kọ́ wá pé kí a má a ní igbẹ́kẹ̀lé nínú Olódùmarè bí a bá wà nínú ìṣòro. Kò ṣòro fún Ifá láti mú ìṣòro náà kúrò.





***Translation:***

1.

Ogbè, strap the baby well
Ogbè, strap the baby good
Nothing is as good as having one's own baby
Whenever a baby cries
The baby is usually handed over to his/her mother
Divined for Ìjòkùn Òfàlà
Who was going to Ìlúgùn town
Because of a child.

Ìjòkùn, a woman, was barren, unhappy, and very desperate for a child. She was sad all the time because of her childless state. Then one day she decided to consult Ifá. Ìjòkùn asked Ifá if she could ever have a child in her life. The Babaláwo assured her that she would have children but to make ẹbọ. They told her the things to provide. She made the ẹbọ, and almost immediately after, she started having children. She then praised Ifá saying her Babaláwo assured her:

Ogbè, strap the baby well
Ogbè, strap the baby good
Nothing is as good as having one's own baby
Whenever a baby cries
The baby is usually handed over to his/her mother
Divined for Ìjòkùn Òfàlà
Who was going to Ìlúgùn town
Because of a child
She said, ''Making ẹbọ is good
To disobey advice ẹbọ is bad''
Soon after the ẹbọ

Rejoice with us
Because it is always with joyfulness that we
worship the Òrìṣà.

This verse of Ogbè T'ọ̀mọpọ̀n teaches us to practice patience in whatever we do in life.

2.
What-are-we-looking-for
Was the one that divined for *orí* (destiny)
We-get-whatever-we-seek
Was the one that divined for *ọrùn* (neck)
Arigidi, Ọlọ̀tà's child
Was he that divined for *ẹni-ilẹ̀*
*Ẹni-ilẹ̀* is an alias of money
Ooooh money!
Money rejuvenates the old
The joy of money comes from the vacuum it fills in one's life.

Ajé (money), *orí* (head - destiny), and orùn (neck) were intimate friends. The three of them lacked respect and honor. At a stage in their lives, they decided to consult Ifá about what to do to gain respect. They were told to make ẹbọ. Each of them was given lists of things needed for the ẹbọ. Two of them, *orí* and ọrùn, made the ẹbọ. The third one, money (personified), refused to make the ẹbọ. Soon after making the ẹbọ, Orí and ọrùn's prayers manifested through Èṣù's *àṣẹ (command)*. Money too benefited from the ẹbọ because his friends, orí and ọrùn, prayed for him. The three of them were very happy and jubilant. Èṣù changed form and asked the





Babaláwo if all of them - ajé, orí, and ọrùn - made the ẹbọ. The Babaláwo told Èṣù that it was only *orí* and *ọrùn* that did the ẹbọ. When the good things in life were to be distributed, *orí* (head) was given a crown, *ọrùn* (neck) got jewelries. As for ajé [money] it got nothing. This explains why ajé, up till now, can sometime be laid carelessly. From that time, money lacked honor - it can be put on the ground, unlike the crown and jewelry that command special care and attention when not in use.

What-are-we-looking-for
Was the one that divined for *orí* (destiny)
We-get-whatever-we-seek
Was the one that divined for *ọrùn* (neck)
Arigidi, Ọlọ̀tà's child
Was he that divined for *ẹni-ilẹ̀*
*Ẹni-ilẹ̀* is an alias for money
Ooooh money!
Money rejuvenates the old
The joy of money comes from the vacuum it fills in one's life.

3.
Yangi with its uneven head
Divined for ọ̀pẹ̀ ẹ̀lùjù [sacred palm tree]
That was crying because of childlessness
Ọ̀pẹ̀ was told to make ẹbọ.

The Ọ̀pẹ̀ in reference here was a barren woman who had never been pregnant in her life. Ọ̀pẹ̀ was bothered about her predicament until one day when she decided to consult Ifá.

The Babaláwo assured her that she would be blessed with children, but she needed to make ẹbọ. They gave Ọ̀pẹ̀ a list of things needed for the ẹbọ. Ọ̀pẹ̀ made the ẹbọ without hesitation. Soon after the ẹbọ and with the àṣẹ of Èṣù, Ọ̀pẹ̀ became pregnant. Olódùmarè blessed her with a good child. From one child, Ọ̀pẹ̀ started having more. She kept being pregnant and having babies until she was tired of having more babies. She was so happy that she praised Olódùmarè, the king in heaven saying:

Yangí with its uneven head
Divined for ọpẹ̀ ẹ̀lùjù [sacred palm tree]
That was crying because of childlessness
Ọ̀pẹ̀ was told to make ẹbọ
Making ẹbọ is good
Refusal to make prescribed ẹbọ is bad
Soon after making the ẹbọ
Join us in rejoicing for our special blessings from Olódùmarè.

*Àṣẹ:* This verse of Ogbè T'ọ̀mọpọ̀n recommends perseverance in whatever one does in life. It also assures that one's wishes to God will be granted.

4.
Ìjòkùn Òfàlà
Divined for Olúgàn
Who leaped for good things
But luck was never within his reach
They [Babaláwo] assured him of luck
But that he needed to make ẹbọ





Ìjòkùn Òfàlà made the ẹbọ
And started reaping bountiful luck.

Olúgàn in reference here tried everything he could for good luck but nothing ever worked. Sad about his situation but hopeful for a better future, he went to consult Ifá. The Babaláwo divined for him and told him to provide certain things for ẹbọ for improvement of his life. They told him to provide one male goat in addition to other things. Olúgàn made the ẹbọ, thereafter, his life improved. He was very glad and happy that things changed for good for him. He thanked Olódùmarè saying:

Ìjòkùn Òfàlà
Divined for Olúgàn
Who leaped for good things
But luck was never within his reach
They [Babaláwo] assured him of luck
But that he needed to make ẹbọ
Ìjòkùn Òfàlà made the ẹbọ
And started reaping bountiful luck
All Awo including Ìjòkùn Òfàlà
Let us give thanks to Olúgàn.

*Àṣẹ:* Ifá recommends that one should have faith in Olódùmarè particularly in times of problems or uneasiness because things that we human beings see as difficult is in fact very light in the spiritual sense of the problem.

# Èjìlá (12)

## Ogbè Òtúrá (Ogbè Alárá)

1.

Èmi ni ngori
Èmi ni ngori
A d'Ífá fún Ọ̀rúnmìlà
Yí òò mú ọmọ rẹ̀ wọ'lé àìkú.

Àwọn ọmọ Ọ̀rúnmìlà ni gbogbo ajogun ibi ńyọ l'ẹ́nu, pẹ̀lú Ọ̀rúnmìlà gan fúnra rẹ̀, pẹ̀lú ìyàwó rẹ̀. Ni Ọ̀rúnmìlà bá gbé òkè ìpọ̀nrí rẹ̀ ka'lẹ̀, ó bèrè wípé báwo ni òun ti ṣe lè ṣẹ́'gun gbogbo ajogun ibi wọ̀nyí. Wọ́n ni Ọ̀rúnmìlà ó ó ṣẹ́'gun, ẹbọ ni kí ó rú. Ó rú'bọ. Àwọn Awo ṣe Ifá fún. Láti àkókò yí ni Ọ̀rúnmìlà, ìyàwó rẹ̀, àti àwọn ọmọ rẹ̀ ti bọ́ l'ọ́wọ́ gbogbo ajogun ibi. Ọ̀rúnmìlà ńjó, ó ńyọ̀, ó ni bẹ́ẹ̀ l'àwọn Awo òun wí:

Èmi ni ngori
Èmi ni ngori
A d'Ífá fún Ọ̀rúnmìlà
Yí òò mú ọmọ rẹ̀ wọ'lé àìkú
Ilé àìkú mo múra mi wọ̀
Èmi ni ngori
Èmi ni ngori



Ilé àìkú mo mú aya mi wọ̀
Èmi ni ngori
Èmi ni ng'ori
Ilé àìkú mo mú ọmọ mi wọ̀
Èmi ni ng'ori
Èmi ni ng'ori.

*Àṣẹ:* Ifá pé òun pé ire àìkú fún ẹni ti ó dá Ogbè-Túá. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú, kí ó si má fi etí pàlábà ẹbọ rẹ̀.

2.

Ọ̀làlà awo ọ̀bẹ
D'Ifá fún ọ̀bẹ
Yí òò wọ'lé orò ìṣu titun l'ọ́dún.

Ọ̀bẹ ti Ifá s'ọ̀rọ̀ nipa rẹ̀ yí, òun àti àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ ọdọọdún ni wọ́n ma á wọ'lé orò ìṣu titun. Bí àwọn yókù bá wọ'lé wọ́n ki i lè jáde láti ṣe ọdún miiran. Ìgbàti ó kan ọ̀bẹ ni ọ̀bẹ mú ẹ́ẹ̀ji kún ẹ́ẹ̀ta, ó lọ̀ oko awo. Wọ́n ni ọ̀bẹ, "Kí o tó lè yege láti ṣe ọdún miiran ẹbọ ni kí o rú." Wọ́n yan ọ̀bẹ l'ẹ́bọ. Ó rú'bọ. Wọ́n ṣe Ifá fún, ni ọ̀bẹ bá wọ'lé orò ìṣu titun, ló bá jáde, ló bá di wípé láti igbà náà wá ọ̀bẹ ni wọ́n fi ma á pa ìṣu ni ọdọọdún. Ọdún kìí dun ki ọ̀bẹ ó má pa ìṣu. Ọ̀bẹ ńjó, ó ńyọ̀, ó ńyin Awo, ẹnu ti ó yà kótó, orin awo ló bọ́ si, ó ni:

Ọ̀làlà awo ọ̀bẹ
D'Ifá fún ọ̀bẹ
Yí ó wọ'lé orò ìṣu titun l'ọ́dún
Àwa ṣe ọdún èyí tán
A ó ṣe tẹ̀ẹ̀mìí
Ọ̀làlà awo ọ̀bẹ.

*Àṣẹ:* Ifá yìí kò wá wípé gbogbo òun tí a òò bá ṣe, kí a má a ṣe ìwàdìí gìdìgìdì, kí a sì má dáà ọ̀jà.

3.

'Fáwọlé yẹ ẹlẹ́ṣin
Bó fẹ bí kò to àgùntàn
A d'Ifá fún Ọlọmọ atà'rún s'ọ̀jà.

Ọlọmọ atà'rún s'ọ̀jà tí Ifá s'ọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí, àrùn ló ńbáa jà. Ó ṣ'òògùn ṣ'òògùn kò gbádùn. Ó já'wé títí, kò rán-án náà ló njá sí. Ó wá ro'nú títí kinni ó tún kù t'òun ó ṣe, ni ó bá mú ẹ́ẹ̀jì kùn ẹ́ẹ̀ta, ó lọ s'óko awo. Wọ́n ní ẹbọ ni kò'rú. Wọ́n yàn-án l'ẹ́bọ. Ó gbọ́ rírú ẹbọ ó rú'bọ; ó gbọ́ títù èrù, ó tù èrù. Wọ́n yàn-án ni òrúkọ (òbúkọ) àti ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ owó, ni wọ́n bá rú'bọ fún-un. Wọ́n se Ifá sí ara òrúkọ yìí. Igbàtí wọ́n ṣe Ifá sí ara ẹran yìí, wọ́n ni kó tún fà á lọ sí ọjà láti lọ tà. Ló bá lọ tà á s'ọ̀jà. Láti ìgbàyí ni Ọlọmọ atà'rún s'ọ̀jà ti bẹ̀rẹ̀ sí ni gbádùn, tí ó sì ní àlàfíà pátápátá. Ló bá ńjó, ló ńyọ̀, ó ní bẹ̀ẹ̀ l'àwọn Awo wí:

'Fáwọlé yẹ ẹlẹ́ṣin
Bó fẹ bí kò to àgùntàn
A d'Ifá fún Ọlọmọ atà'rún s'ọ̀jà
Rírú ẹbọ ni í gbe'ni
Àìrú kì í gbéniyàn
Kèè pẹ́, kèè jìnà
Ẹ wá bá mi bá àrúfìn ẹbọ.





4.

Ó kù díẹ̀ kò tó
Ló d'Ifá fún adìẹ
A bí ọ̀rán òṣì l'ọ̀rún.

Adìẹ tí Ifá ńsọ yìí ni wọ́n ni kí ó mú ọ̀rán burúkú kúrò l'ọ̀rùn nígbàtí gbogbo ọ̀rọ̀ rẹ̀ kò ni ojútùú, ojoojúmọ̀ ni ó ma ńdùràn. Ni wọ́n bá fi okùn sí ni ọrùn. Wọ́n kò lè fi okùn sí òun l'ọ̀rùn ni ó dá Ifá sí. Àwọn Babaláwo bá ni kí ó rú òkété mẹ́ta pẹ̀lú ọ̀kẹ́ mẹ́tàlélọ́gọ́ta àti okùn ẹran. Ni ó bá rú'bọ. Ni okùn bá bọ́ sí ọrùn ewúrẹ́. Ẹni tí ó bá dá Ogbè-Túá kí ó rú'bọ kí ó ma ba dá ọ̀ràn. Ìdí nìyí tí okùn wọn kò fi ma á fi sí ọrùn adìẹ mọ́.

Ó kù díẹ̀ kò tó
Ló d'Ifá fún adìẹ
A bí ọ̀ràn òṣì l'ọ̀rún
Èèwọ̀ Òrìṣà adìẹ kìí l'ọ̀rùn okùn.

*Àṣẹ:* Ifá pé kí eléyìun ó má fi etí pàlábà ẹbọ náà.

***Translation:***

1.

I will be victorious
I will be victorious
Divine for Ọ̀rúnmìlà
Who will take his children to an everlasting room
(initiate them into *Odù*).

Ọ̀rúnmìlà's children were being tormented by evil forces; Ọ̀rúnmìlà himself and his wives were not spared either. Therefore, Ọ̀rúnmìlà consulted his Ifá, and asked Ifá what he should do to overcome all the adversaries. Ifá assured Ọ̀rúnmìlà of victory but recommended ẹbọ. Ọ̀rúnmìlà made the ẹbọ. The Babaláwo that consulted Ifá for Ọ̀rúnmìlà gave Ọ̀rúnmìlà a specially prepared Ifá medicine. From thenceforth, Ọ̀rúnmìlà, his wives, and his children were protected against all evil forces. Ọ̀rúnmìlà was jubilant and said his awo assured him:

I will be victorious
I will be victorious
Divine for Ọ̀rúnmìlà
Who will take his children to an everlasting room, that is, initiate them into ***Odù*** after Ifá's initiation
I enter the everlasting room
I will be victorious
I take my wife (or husband) with me to the everlasting room
I will be victorious
I take all my children with me to the everlasting room
I will be victorious.

***Àṣẹ:*** Ifá foresees long life for whomever Ogbè Òtúrá comes out for. Ifá recommends ẹbọ and says never to disregard advice for ẹbọ.

2.
Ọ̀lálá, diviner for knife
Divine for the knife
Who will cut newly harvested yams.





Knife in reference here, together with his colleagues, always celebrated new yams. Each year, some of knife's colleagues will die in the mist of the annual yam festival. When it was knife's turn to cut a new yam for the festival, he went for consultation with Ifá. The Babaláwo told knife that, for him to survive the festival and celebrate another one, he should make ẹbọ. They told knife to provide certain ritual things. Knife made the ẹbọ. The Babaláwo gave knife special Ifá medicine. Knife cut through the yam during the annual festival and came out of it without incident. Since then, knife became the main instrument for cutting new yams during new yam festivals. Knife rejoiced for this success and praised his awo singing:

Ọ̀lálá, diviner for knife
Ọ̀lálá, diviner for knife
We made this year
We will see many more years
Ọ̀lálá, diviner for knife.

***Àṣẹ:*** This verse teaches us to consult the Òrìṣà, especially Ifá, on everything we do in life.

3.
'Fáwọlé the rich
Divined for Ọlọmọ-atà'rún-s'ọ̀jà. Meaning: Ọlọmọ that was healed by virtue of a special Ifá work cast on the sheep that he sold in the market.

Ọlọmọ-atà'rùn-s'ọ̀jà that Ifá speaks about here suffered a very rare disease. He spent a lot of money, time, and energy looking for cure, but all the medicine he used did not cure him. He thought of what else he could and then remembered Ifá. He went to some Babaláwo. The Babaláwo consulted Ifá on his behalf. They told him to make ẹbọ and gave him a list of the things to provide. The list for the ẹbọ included a male goat and money. Ọlọmọ-atà'rùn-s'ọ̀jà provided the things, and ẹbọ was made for him. A special Ifá medicine was made on the male goat, and Ọlọmọ-atà'rùn-s'ọ̀jà was instructed to take the goat to the market for sale. Ọlọmọ-atà'rùn-s'ọ̀jà did that and from that moment thenceforth, he was cured of his rare disease. He was jubilant as a result of this and said:

'Fáwọlé the rich
Divined for Ọlọmọ-atà'rùn-s'ọ̀jà
Making ẹbọ comes with lots of gains and rewards
Refusal to make ẹbọ has its downfall
Soon after making an ẹbọ
Join us in giving praise to the gods.

4.
Just a little bit more
Was he that divined for hen - *personified*
The troubled and unlucky hen.

The hen in reference here was advised to do away with its bad luck when hen was living a difficult life. Everyday, hen was always in some kind of trouble. To be rid of this nagging troubles, hen went for a divination. Its concern was to prevent





people from putting a leash on its neck. Hen was told to sacrifice *òkété (giant rat), a rope, and 73 bags of money*. Hen made the ẹbọ. By virtue of the ẹbọ, rope [leash] went from hen's neck to that of goat.

Just a little bit more
Was he that divined for the troubled hen
It is a taboo
Hen is never tied with a leash.

*Àṣẹ:* Whomever Ogbè-Òtúrá comes out for must make ẹbọ to avoid getting into big troubles. This is the reason why a leash is never used on a hen.

Ifá strongly advises whomever this Odù comes out for to make sure that he/she make recommended ẹbọs.

# Ẹ̀tàlá (13)

## Ogbè Ìrẹtẹ̀ (Ogbè Atẹ̀)

1.

O lé kénkésé l'óri odi
Òṣùpá mọ́'lẹ̀ ó jù 'ráwọ̀
A d'Ífá fún Kiniọ̀ṣe tií ṣ'ọmọ Àgbọnnirégùn
L'ọ́jọ́ tí ó nt'ọ̀run bọ̀ w'áyé
Ọmọ aráyé ní kò ní lè ṣe àṣeyọrí.

Kini-ó-ṣe tí Ifá s'ọ̀rọ̀ rẹ̀ yí, Olódùmarè ńran bọ̀ láti òde ọrun w'áyé. Àwọn ọmọ aráyé bẹ̀rẹ̀ ọ̀tẹ̀, wọ́n ní àwọn ó ní jẹ́ kí ó ṣe àṣeyọrí, wọ́n ní kò sí ọ̀nà tí yí óò gbegbà, àwọn kò ní jẹ́ kí ó ní láárí l'áyé. Ní ó bá tọ Ọ̀rúnmìlà lọ, ni Ọ̀rúnmìlà bá gbé òkè ipọ̀nri rẹ̀ ka'lẹ̀, ó pe àwọn Awo, wọ́n dá Ifá, wọ́n ní ẹbọ ni kí Ọ̀rúnmìlà ó rú. Ó bẹ̀rẹ̀ ńkan ẹbọ, wọ́n yan Ọ̀rúnmìlà l'ẹ́bọ, ó rú'bọ. Wọ́n ṣe Ifá fún Kini-ó-ṣe w'áyé. Diẹ̀-diẹ̀ ó ńdàgbà, àwọn ọ̀tá tí wọ́n ńlérí wọn kò lè ṣe ǹkankan fun mọ́. Èyítí ó bá sì ṣe búburú sí Kini-ó-ṣe, kò ní ràn-án. Ní Kini-ó-ṣe bá bẹ̀rẹ̀ sí d'àgbà, gbogbo ire ńto l'ọ́wọ́, inú rẹ̀ dùn, inú Ọ̀rúnmìlà náà dùn, ó ní bẹ́ẹ̀ l'àwọn Awo wí:



O lé kénkésé l'óri odi
Òṣùpá mọ́'lẹ̀ ó jù'ráwọ̀
A d'Ífá fún Kini-ó-ṣe tií ṣ'ọmọ Àgbọnnirègùn
L'ọ́jọ́ tí ó nt'ọ̀run bọ̀ w'áyé
Ọmọ aráyé ní kò ní lè ṣe àṣeyọrí
Ọ̀rúnmìlà ní irọ́ ni wọ́n ńpa
Ó ní èké ni wọ́n ńṣe
Ifá ní igba l'ewé orósè
Èmi à ṣà i ṣe tèmi
Igba l'ewé orósè
Ní iṣojú olóko ní ilá ṣe kó
Igba l'ewé orósè
Èmi à ṣà i ṣe tèmi
Igba l'ewé orósè
Ṣ'ojú olóko ní ikàn ṣe w'ẹ̀wù ẹ̀jẹ̀
Igba l'ewé orósè
Èmi à ṣà i ṣe tèmi
Igba l'ewé orósè
Ṣ'ojú olóko ní ààlà ṣe wọ̀'gbẹ̀
Igba l'ewé orósè
Èmi à ṣà i ṣe tèmi
Igba l'ewé orósè.

***Àṣẹ:*** Ẹ̀kọ́ tí Ifá yìí kọ́ wá ni wípé kí a má a fura l'órí ohun gbogbo tí a bá ńṣe, kí a má gbàgbé ara wa, kí a sì má gbàgbé orírun wa.

2.

Àkùkọ tó kọ l'ánàá
Ìkọ ire ló kọ

A d'Ìfá fún erin
Erin ńsunkún p'óun ò l'ọ̀lá
Àkùkọ tó kọ l'ánàá
Ìkọ ire ló kọ
A d'Ìfá fún ẹfọ̀n
Ẹfọ̀n ńsunkún p'óun ò n'íyì
Àkùkọ tó kọ l'ánàá
Ìkọ ire ló kọ
A d'Ìfá fún ẹṣin
Ẹṣin ńlọ oko àlérò l'ọ́dún.

Àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí Ifá s'ọ̀rọ̀ rè yìí ni oníkálukú ńsunkún ohun tí ó ndùn-ún l'ọ́kàn, wọ́n mú ẹ́ẹ̀jì kún ẹ̀ẹ́ta wọ́n lọ oko Awo. Wọ́n ni ẹbọ ni kí wọ́n ó rú. Wọn bẹ̀rẹ̀ kínni ǹkan ẹbọ, wọ́n yán wọ́n l'ẹ́bọ. Àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ló rú'bọ, ni wọ́n bá ṣe Ifá fún wọn. Erin tí kò l'ọ̀lá, ó l'ọ̀lá; ẹfọ̀n tí kò ní iyì, ẹfọ̀n ní iyì; ẹṣin rẹ̀é òun náà di ọlọ́mọ rẹpẹtẹ l'óko. Wọ́n wá ńjó, wọ́n ńyọ̀, wọ́n ní bẹ́ẹ̀ l'àwọn Awo wí:

Àkùkọ tó kọ l'ánàá
Ìkọ ire ló kọ
A d'Ìfá fún erin
Erin ńsunkún p'óun ò l'ọ̀lá
Wọ́n ni ẹbọ ni kí ó ṣe
Erin l'ọ̀lá
Àkùkọ tó kọ l'ánàá
Ìkọ ire ló kọ
A d'Ìfá fún ẹfọ̀n
Ẹfọ̀n ńsunkún p'óun ò n'íyì
Wọ́n ni ẹbọ ni kí ó ṣe
Ẹfọ̀n ní iyì





Àkùkọ tó kọ l'ánàá
Ìkọ ire ló kọ
A d'Ìfá fún ẹṣin
Ẹṣin ńlọ oko àlérò l'ọ́dún
Wọ́n ni ẹbọ ni kí ó ṣe
Erin l'ọ̀lá.

***Orin:*** Erin l'ọ̀lá o, ẹfọ̀n níyì o
Erin l'ọ̀lá o, ẹfọ̀n níyì o
Ẹṣin ló r'oko rè é là ò.

3.
Mo gbà, mo tẹ̀ ni irègún Ifá
Ìrègún Ifá tán
Ìrègún Ifá ò tán
Ìrègún Ifá kù l'ẹ́hìn đanyin đanyin
A d'Ìfá fún Ọ̀rúnmìlà
Ifá ńlọ rèé gb'Ódù n'íyàwó.

Ọ̀rúnmìlà ni ọkọ Odù, Odù wá níyì ojú ọmọ ńpọn, ni ó wá mú ẹ́ẹ̀jì kún ẹ̀ẹ́ta ni ó lọ sí oko awo. Àwọn Awo dá'Fá. Ni wọ́n bá ni kí Odù rú'bọ. Ó si rú'bọ. Ni ó wá bí ọmọ lọ́pọ̀lọpọ̀, ni ó wá nyin Babaláwo, ni Babaláwo nyin Ifá, Ifá nyin Elédùmarè ọba l'ọ̀run.

Mo gbà, mo tẹ̀ ni irègún Ifá
Ìrègún Ifá tán
Ìrègún Ifá ò tán
Ìrègún Ifá kù l'ẹ́hìn đanyin đanyin
A d'Ìfá fún Ọ̀rúnmìlà

Ifá ńlọ rèé gb'Ódù n'iyàwó
Odù nikan ni ó bí'mọ bàwọ̀nyí
Ẹ wá wo ọmọ Odù bẹrẹrẹ.

*Àṣẹ:* Ifá pé òun pé ire ọmọ fún ẹni ti ó dá Ogbè-Atẹ̀. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú, kí ó si má fi eti pàlábà rè. Ifá pé ẹbọ ni kí ó rú. Ifá pé òun yí òò ṣe gbogbo ire ti ó ńfẹ́ fún-un.

**Ẹbọ:** Ìgbín mẹ́rindinlógún, abo adìẹ mẹ́rindinlógún, ọ̀kẹ́ owó mẹ́rindinlógún.

4.
Ọ̀rúnmìlà wí ará yá mi
Ifá wí ará nyá mi
Ifá ní ara igi wo ló nyá
Wọ́n ní ata oluweere ni
Ọ̀rúnmìlà ní irọ́ ni
Ó yá l'éso ni, kò yá l'égbò, bẹ́ẹ̀ ni kò yá l'ewé
Ọ̀rúnmìlà wí ará yá mi,
Ifá wí ara nyá
Ifá ní ara igi wo ló yá
Wọ́n ní igi ata ni
Ó ló ya l'égbò ni kò yá l'éwé
Ọ̀rúnmìlà wí ará yá mi
Ifá wí ara nyá
Ifá ní ara igi wo ló yá
Wọ́n ní àwọn kò mọ̀ ọ́
Ifá ní ara iyèré nikan lóyá
Ó yá l'égbò, ó yá l'éso, ó yá l'éwé
Ó ní t'éwé t'egbò l'ara iyèré yá.





***Translation:***

1.
It stands tall on the border
Moon is brighter than stars
Divined for What-will-he-do
Àgbọnnirègún's [Ọ̀rúnmìlà] child
When he was coming from heaven to earth
People said he would never prosper in life.

When Kini-ó-ṣe [What-will-he-do] was sent to earth by Olódùmarè, earth-bound people vowed that they would keep him down. They also vowed to do everything within their power to block his progress. Because of these threats, Kini-ó-ṣe went to Ọ̀rúnmìlà for divination. Ọ̀rúnmìlà summoned his Awo to consult Ifá for Kini-ó-ṣe. The Awo divined and told Kini-ó-ṣe to make ẹbọ. Ọ̀rúnmìlà asked for the list of things to provide. They [the Babaláwo] gave him the list. Ọ̀rúnmìlà provided everything and ẹbọ was made for Kini-ó-ṣe. The Awo also gave Kini-ó-ṣe specially prepared Ifá medicine for use on his earth-bound journey. Kini-ó-ṣe was born in human flesh; he went through all the passages of human growth and became an adult. Meanwhile, the enemies, who had vowed to keep him down tried all they could to achieve their evil goals, but none of their evil plots affected him. Kini-ó-ṣe grew to adulthood and started having all the good things of life. He was happy for this positive results in his life. Ọ̀rúnmìlà too was happy and said his Awo assured him that:

It stands tall on the border
Moon is brighter than stars
Divined for What-will-he-do

Àgbọnnirègùn's [Ọ̀rúnmìlà] child
When he was coming from heaven to earth
People said he would never prosper in life
Ọ̀rúnmìlà, said they lied
He said they were joking
He said '200 are the leaves of *oróṣè*
I will live my own life
200 are the leaves of *oróṣè'*
Okra dried on its tree with the full knowledge of the farmer
200 are the leaves of *oróṣè*
I will live my own life
200 are the leaves of *oróṣè*
Ikàn (egg-plant) goes *bad* with the full knowledge of the farmer
200 are the leaves of oróṣè
I will live my own life
200 are the leaves of *oróṣè*
The farmer was there when the farmland was divided
200 are the leaves of *oróṣè*
I will live my own life
200 are the leaves of *oróṣè*.

**Lesson from the Odù:**
Ifá teaches that we should always take care of ourselves spiritually, and that we should always consult with our destinies on constant basis.

2.
The cock [rooster] that crowed yesterday
Did the right thing





Divined for elephant
Elephant was sad because of its small size
The cock [rooster] that crowed yesterday
Did the right thing
Divined for buffalo
Buffalo was sad because no animal respected him
The cock [rooster] that crowed yesterday
Did the right thing
Divined for eṣin (kind of pumpkin)
Eṣin was going for his annual farming.

The above two mentioned animals and *eṣin* (plant) went to Ifá for divination because of their individual yearnings, wants, and aspirations. They were told to make ẹbọ. The animals and eṣin asked for the list of things needed for the ẹbọ. They were given the list. They all made the ẹbọ, and the Babaláwo gave them specially prepared Ifá medicines. Elephant that was small prior to that ẹbọ became big, buffalo that lacked respect gained respect; and *eṣin* multiplied in the farm. They were happy and jubilant. They started praising the Babaláwo saying:

The cock [rooster] that crowed yesterday
Did the right thing
Divined for elephant
Elephant was sad because of its small size
He was told to make ẹbọ
Elephant made the ẹbọ, and he became big
The cock [rooster] that crowed yesterday
Did the right thing
Divined for buffalo

Buffalo was sad because no animal respected him
He was told to make e̩bo̩
Buffalo made the e̩bo̩, and he gained respect
The cock [rooster] that crowed yesterday
Did the right thing
Divined for e̩sin (kind of pumpkin)
E̩sin was going for his annual farming
He was told to make e̩bo̩
E̩sin multiplied.

***Song:*** Elephant became big )
Buffalo gained respect) (twice)
E̩sin went to the farm to multiply.

3.

To accept and be initiated will stop Ifá from bothering one
Ifá's initiation is the best, but
There are greater lessons to be learn about Ifá
There is everlasting pride in Ifá
Divined for Ò̩rúnmìlà
Ifá [Ò̩rúnmìlà] was going to marry Odù.

Ò̩rúnmìlà was the husband of Odù. Odù in her own case was barren. Because of this, she consulted many Babaláwo for divination. The Babaláwo consulted Ifá for her. The Babaláwo first of all made their own e̩bo̩ and told her to make e̩bo̩ also. Odù made the e̩bo̩. She had many children thereafter. Therefore, she started praising her Babaláwo; the Babaláwo praised Ifá [Ò̩rúnmìlà] while Ò̩rúnmìlà praised Olódùmarè, the King in heaven.





To accept and be initiated will stop Ifá from bothering one
Ifá's initiation is the best, but
There are greater lessons to be learn about Ifá
There is everlasting pride in Ifá
Divined for Ò̩rúnmìlà
Ifá [Ò̩rúnmìlà] was going to marry Odù
Odù is the mother of all these [many] children
See how plenty Odù's children are.

*Às̩e̩:* Ifá foresees many children for whomever Ogbè Atè̩ comes out for. Ifá recommends e̩bo̩; Ifá also says that the person should never disregard advice for e̩bo̩. Ifá promises to bless the person with all the good things he/she aspires for.

**E̩bo̩:** 16 snails
16 hens
16 bags of money.

4.

Ò̩rúnmìlà says, "I am happy"
Ifá says, "I am happy"
Ifá asks, "Which tree is hot all over"
They told him it was *pepper*
Ò̩rúnmìlà says, "That is not correct"
It is only pepper (the seeds) that are hot, the tree is not hot, and the root is not hot
Ò̩rúnmìlà says, "I am happy"
Ifá says, "I am happy"
Ifá asks, "Which tree is hot all over"
They told him it was *pepper* tree

Ọ̀rúnmìlà says, "That is not correct"
It is the root that is hot, the leaves are not hot
Ọ̀rúnmìlà says, "I am happy"
Ifá says, "I am happy"
Ifá asks, "Which tree is hot all over"
They told him that they did not know
Ọ̀rúnmìlà says, "It is *ìyèré* that is hot all over
The leaves are hot, the root is hot, the bark is hot, the tree is hot.
Ìyèré's leaves are hot, the root is hot."



# *Ẹ̀rìnlá (14)*

## Ogbè-Ṣẹ́

1.

Ogbè-ṣé rẹ́'rin-in ṣẹkẹ
A d'Ifá fún Akinlàwọ̀n
Tí oníṣẹ́ ayé ńrán 'ni pè
Tí t'òde ọ̀run ná à ńrán 'ni pè.

Akinlàwọ̀n tí Ifá s'ọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí, àwọn ọ̀tá ni ó ńbá a jà. Bó bá sùn, orun burúkú ló ńsùn, àlá tí kò dára ló ńlá, àláfíà ò to. Ọ̀sán gangan nàà si niyi àwọn ọ̀tá níwájú, ọ̀tá l'ẹ̀hìn ni fún ni gbogbo igbà. Kò ri ibi rin si, èrò ki ó kú ni wọ́n ńgbà sí i. Ìgbàtí ọ̀rọ̀ ara rẹ̀ su, ni ó bá mú ẹ́ẹ̀jì kún ẹ́ẹ̀ta, ó lọ oko awo. Wọ́n ní ẹbọ ni kí ó rú, yí óò ṣẹ́'gun ọ̀tá; gbogbo ǹkan rẹ̀ yí óò si dára. Ni wọ́n bá yan Akinlàwọ̀n ní ẹbọ. Ó rú'bọ. Wọ́n ṣe Ifá fún. Ẹbọ rẹ̀ dà, ó ńṣẹ́'gun ọ̀tá, àlá burúkú tí ó ńlá kò là àlá búburú mọ́. Ó ńsùn dáadáa. Àwọn tó ńgba èrò ikú fún, àwọn gan-an ló ńkú. Akinlàwọ̀n ò kú mọ́. Ló bá ńjó, ó ńyọ̀, ó ní bẹ́ẹ̀ l'àwọn Awo wí:

Ogbè-ṣẹ́ rẹ́'rin-in ṣẹkẹ
A d'Ifá fún Akinlàwọ̀n
Tí oníṣẹ́ ayé ńrán 'ni pè

Ti t'òde ọrun nà à ñràn 'ni pé
Akinlàwọn Olọ̀tà, òun gbé l'áyé, t'òde ọrun ñṣàisàn

2.

Ojú tí ñpọn wọn àpọ̀nkú kọ̀
Ìyà tí ñjẹ wọ́n, àjẹlà ni
Bó pẹ́ títí, a ó fi ọ̀ràn tó lé kókó ṣ'ẹ̀rín rín
A d'Ifá fún Òrìṣà-Nlá Ọ̀ṣẹ̀ẹ̀rẹ̀màgbò
Tí ó fi arọ ṣe àkọ̀rà ẹrú

Òrìṣà bèrè wípé ọjà tí òun fẹ́ rà yìí, ó lè lálùbárìkà ló rèé d'Ifá si. Àwọn Awo sọ fún Òrìṣà pé ọjà rẹ̀ ni yi òò jẹ́. Òrìṣà dé ọjà Èjìgbòmẹ̀kùn ló bá ra arọ l'ẹ́rú nígbàtí kò rí ẹlẹ́sẹ̀ rà. Nígbàtí ó mú arọ dé'lé, ó ní iṣẹ́ kíni arọ ó ṣe; arọ l'óko ni fún Òrìṣà. Ni arọ bá ñdáko l'ágbàlá Òrìṣà. Ó gbin àgbàdo rẹpẹtẹ, àgbàdo gbó, àgbàdo gbẹ. Àkókò yìí ni ìyàn dé sí àwọn ẹyẹ nínú igbó tí wọn kò rí oúnjẹ jẹ. Ni wọ́n bá ñjẹ àgbàdo tí arọ gbin. Èṣù darí gbogbo wọn s'inú àgbàdo yìí. Níbẹ̀ ni arọ ti fi ọ̀bẹ rẹ́ àwọn àgbàdo nídìí, bí àwọn ẹyẹ odidẹrẹ́ yìí ti ñbà lé àgbàdo yìí ni wọn ñṣubú lu'lẹ̀, ni arọ bá ñko wọn s'inú àgò. Arọ ñtu èko idí i wọn, ó wá ñfi sín adé fún Òrìṣà. Gbogbo àwọn ẹgbẹ́ Òrìṣà tí wọ́n bá tí ñdé, wọn ó rí adé l'órí Òrìṣà. Wọn ó wá ma ki Òrìṣà pé, "Pẹ̀lẹ́ o aládé Ìko." Arọ tún nsín adé yìí fún àwọn ènìyàn lọ́jà-lọ́jà, l'ádé-l'ádé, àwọn ọba-ọba ñlá ni igbiigba ọkẹ́. Ni Òrìṣà bá là. Òrìṣà ní, "Ẹrú tí mo rà ló sọ mi d'ọba." Àti igbà náà ni wọ́n tí ñpa á l'ówe pé, "Arọ tí kò lè rìn, ó ní ọgbọ́n nínú."

*Àṣẹ:* Ifá pé ọjà tí a fẹ́ rà yi òò dára o.

**Ẹbọ:** Ká fi ọ̀pọ̀lọpọ̀ igbin bọ Òrìṣà.





3.

Màjowere màjowere
A d'Ifá fún afọ̀'jú
A d'Ifá fún arọ tí ó ñsògbògbò àrùn
Tí ó ñnajú àti dide
Njẹ́ b'ẹni ó kú
Ẹni ajòwere diẹ̀
Màjowere màjowere.

Afọ̀'jú àti arọ ni àwọn méjèèjì d'Ifá pé àisàn tí ñṣe àwọn, àwọn lè bọ́ nínú rẹ̀, tí kò ní pa àwọn báyìí bí? Wọ́n ní ki afọ̀'jú tọ́jú
*igi ọ̀pá méjì, òkété, àkùkọ adìẹ, ọkẹ́ mẹ́tàlélógójì;*
ki arọ tọ́jú
*yangí kan àti ọkẹ́ mẹ́tàlélógún.*
Ki àwọn méjèèjì gbé ẹbọ lọ ojú odò. Afọ̀'jú gbé arọ rù, arọ njúwe ọ̀nà. Nígbàtí wọ́n dé odò, afọ̀'jú sọ arọ ka'lẹ̀, ni arọ sọ fún afọ̀'jú pé òun òò kò sí odò nítòun. Arọ ju yangí sínú omi, ni afọ̀'jú ñfi ọ̀pá tú inú omi pé, "Ẹni tí ó gbé òun ti kò s'odò." Níbití afọ̀'jú ti njòwere ni ó bá ba arọ l'ẹ́sẹ̀, ni ẹsẹ̀ bá nà, hàà tí afọ̀'jú ó wìí, ni ojú afọ̀'jú bà là. Ni ọ̀rọ̀ àwọn méjèèjì bá là.

*Àṣẹ:* Ifá sọ pé àwọn méjì tí àisàn ñṣe, Ifá sọ pé ki wọn ó ma ba ọkàn jẹ́ o, pé ebọ ni ki wọn ó rú. Wọn ó sì borí iṣòro wọn.

4.

Ifá pé ẹnikan nù u tó lá àlákálàà. Ifá pé ki ó rú ẹbọ ikú, ki ó má ba kú s'ójú oorun. Ẹ gbọ́ ohun tí Ifá wí:

Ifá ni ilé gbókin rẹ ya ọrun
Ẹwù gbókin rẹ̀ ka ọrun

Gbugburu gbùgbūrù làá ri ihò imú erin
A d'Ifá fún Ọ̀rúnmìlà
L'ọ́jọ́ tí òlògbò ilé Baba rẹ̀
Ó ma gbò mọ́ ọ
Má gbò mí adẹ́ṣẹ̀
Òlògbò má gbò mí adẹ́ṣẹ̀.

Ọ̀rúnmìlà ló sùn tí ó ńrí àpẹrẹ ikú pé wọ́n ńpe òun l'ọ̀run. Ó gbé Ifá ka'lẹ̀, ó dá Ifá. Ó rú òkèípọ̀nrí rẹ̀. Ó ní báwo ni òun kò ṣe ní t'ojú orun d'ójú ikú. Ọ̀rúnmìlà dá Ogbè-Ṣẹ́. Wọ́n ní ẹbọ ni kí ó rú. Wọ́n ní kó mú *abo adìẹ, kí ó ma fi gbo'lẹ̀ ní yàrá tí ó ńsùn.* Ọ̀rúnmìlà bá ṣe bẹ́ẹ̀. Ó bá ńfi ẹyin adìẹ gbo'lẹ̀, ó bá nkọ'rin báyìí pé:

Má gbò mí o
Adẹ́ṣẹ̀ o
Òlògbò má gbò mí o, adẹ́ṣẹ̀.

Níbi tí ó ti nsọ bẹ́ẹ̀ ni wọ́n gbó'hùn rẹ̀ ní òde ọ̀run, ni wọ́n sọ pé ẹni tí ó ńfi adìẹ gbo'lẹ̀ báyìí pé kí wọ́n gba adìẹ náà l'ọ́wọ́ rẹ̀, kí ó ma gbé ilé ayé. Ọ̀rúnmìlà ò bá kú mọ́. Kò bá rí àpẹrẹ ikú mọ́.

***Àṣẹ:*** Ifá pé ẹnikan ńlá àlá kálàá tí kò dára. Ifá pé ẹbọ kí ó má ba kú lójijì ni kí ó rú.





***Translation:***

1.

Ogbè-Ṣẹ́ smiles when doing good
Divined for Akínláwọ̀n
Who kept receiving death threats from human beings
Heavenly beings too sent death messages to him.

Akínláwọ̀n that Ifá is talking about here was surrounded by enemies. He always had nightmares, he was even afraid to walk freely during the day; enemies were everywhere he turned; he was sickly too, and the enemies' wishes for him was death.

At a stage when he could not bear the problem any longer, he consulted his Babaláwos. They told him to make ẹbọ. They assured him that with the ẹbọ, he would overcome his enemies' atrocities. They told him what ẹbọ things to provide. Akínláwọ̀n provided the things and ẹbọ was made for him. The Babaláwo gave him special Ifá medicine. Ẹbọ/prayer manifested, he became victorious over all his enemies; his nightmares stopped, and he actually enjoyed his sleep afterward. Those who wished him death started to die themselves. As a result of this victory, Akínláwọ̀n was happy and he started dancing, saying my Babaláwos said that:

Ogbè-Ṣẹ́ smiles when doing good
Divined for Akínláwọ̀n
Who kept receiving death threats from human beings
Heavenly beings too sent death messages to him.
Akínláwọ̀n Ọlọ́tà lives for ever while his enemies became sick.

2.

The hard time being experienced is a temporary one
The sufferings will end with smiles
The hard time and the suffering will eventually become history
Divined for Òrìṣà-Ńlá Ọ̀ṣẹ̀ẹ̀rẹ̀màgbò (Ọbàtálá)
Who bought a lame man as his first slave.

Òrìṣà-Ńlá sought Ọ̀rúnmìlà's opinion about a financial investment he wanted to make. Ọ̀rúnmìlà told Òrìṣà-Ńlá that the investment would be a profitable one. With that assurance, Òrìṣà-Ńlá went to Ejìgbòmẹkùn market [in Ilé Ifẹ̀] for his purchase. By the time Òrìṣà-Ńlá got to the market, there were no more healthy slaves; therefore, he bought a lame one and carried him home. When they got home, Òrìṣà-Ńlá asked the slave what he could do. The slave told Òrìṣà-Ńlá that he could farm. Òrìṣà-Ńlá took the slave to the wood behind his house and told him to farm there. The slave planted a big acreage of corn. The corn grew and later dried. At that particular time of the slave's farming, there was a severe famine for birds; therefore, the birds started feeding on the slave's corns. Èṣù mysteriously directed all the birds to the farm. To control the influx of the birds and to reduce losses, the slave hid knives in strategic places in the corn. As soon as the birds **(odídẹrẹ́ - parrot)** parched on the corns to eat, they would fall off; and the moment they fell off, the slave would pick them, put them inside his àgò (cage) and then pluck their feathers. He made a crown for Òrìṣà-Ńlá with the feathers. The crown was so beautiful that the other Òrìṣà could not resist giving compliments to Òrìṣà-Ńlá for the crown. In their compliment, the other Òrìṣà would say, "Ah Òrìṣà-Ńlá, your feather-crown is wonderful." From this first crown for Òrìṣà-Ńlá, the slave





started making feather-crowns for kings and all royalties. The crowns were sold for a great deal of money. Òrìṣà-Ńlá became rich from these sales. As a compliment to the slave, Òrìṣà-Ńlá started saying, "The slave that I bought makes me rich." This story brought fought a Yorùbá popular proverb that says, "A lame man has wisdom." Meaning that because somebody is handicapped does not mean that the person is stupid.

*Àṣẹ:* Ifá says the investment that the person, who this **Odù** comes out for, wants to make will be a profitable one.

**Ẹbọ:** Ifá says the person should offer plenty snails to Òrìṣà-Ńlá.

3.

I will dance, I will dance
Divined for the blind
Divined also for the lame
Both were seriously sick and were greatly disturbed by their plights
If one lives
One will dance sometime
I will dance, I will dance.

The blind and the lame consulted Ifá asking, "Ifá, are we ever going to be healed of our sickness and not die of them?" The Babaláwo told *the blind* to provide two (2) canes, a giant rat, a rooster, 43 bags of money; while *the lame* was told to provide yangi and 23 bags of money. They provided the things and ẹbọ was made for them. They were told to take the ẹbọ

to the river. *The blind* carried the *lame* on his shoulders while *the lame* gave directions to *the blind*. When they got to the river, *the blind* put down Mr. *lame*. Mr. *lame* told *Mr. blind* that he (the lame) would crawl into the river; but what he actually did was that he (*the lame*) threw his consecrated yangi inside the river. When *the blind* heard the splash of water, he thought *the lame* had actually entered the river and had supposedly committed suicide. Therefore, *the blind* tried to reach the lame by using his cane as a guide. While doing this, the came accidentally hit *the lame* on his leg and his legs straightened. *The blind* cried, "Ah!" apologetically for accidentally hitting *the lame* with his cane. Mysteriously at that time of the blind's exclamation, his eyes opened, and he could see. By this stroke of chance, both of them became healed.

*Àṣẹ:* Ifá says two people who are sick will be healed, and that they should not loose hope. They should make ẹbọ. Ifá also says that they would overcome their difficulties.

4. Ifá says someone is having nightmares. Ifá recommends ẹbọ so that the person would not die in his/her sleep. This is what Ifá says about the message:

Sky is observable from an old dilapidated house
Shoulder is observable from a badly torn suit or dress
Divined for Òrúnmìlà
When he was lonesome
"Don't bother me, dear ancestor"
Don't bother me.





Every night when Ọ̀rúnmìlà slept, he always had the feeling that he was being summoned to heaven, therefore, he consulted his Ifá and asked to know what he could do to prevent him from *going to heaven (that is, die)* in his sleep. The Odù Ifá that came out for Ọ̀rúnmìlà was Ogbè-Ṣẹ. He was told to make ẹbọ. He was told to roll an egg on the floor of his bedroom. Ọ̀rúnmìlà bought an egg and started rolling the egg on the floor of his room. While doing that, he sang:

Don't bother me
Dear ancestors
Don't bother me
Dear ancestors.

Ọ̀rúnmìlà was heard in heaven as he was singing this song; therefore, they [heavenly people] decided among themselves to accept the hen that he was rolling on the ground which was in fact an offering to the evil forces bothering him. They blessed Ọ̀rúnmìlà and allowed him to live on earth. Ọ̀rúnmìlà did not die as a result of the ebo. His nightmare stopped also.

*Àṣẹ:* Ifá says someone is having a nightmare. Ifá says the person should make ẹbọ so that he/she will not die in his/her sleep.

# *Áàrúndínlógún*

## *(15)*

## Ogbè-Fún

1. Ifá pé òun pé ire àìkú fún eni ti ó dá Ogbè-Fún. Ó ní ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ *igbin ni kí ó lọ* fi bọ Odù àti Ifá; abo adìẹ mẹ́rin, ewúrẹ́ pẹ̀lú igba ọkẹ́.

Orun kan ta tan ọjọ́ yẹ látàrí
A d'Ifá fún Ọlọ́fin Eriwò Awo
Ọmọ a mú'gba igbín ṣ'ọ̀run.

O d'Ifá pé ẹ̀mí òun lè gùn báyìí. Wọ́n ní ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ènìyàn ni yí óò ma sin-ín kí ó tó di ọdún èyí ti ó mbọ̀. Àwọn Awo ṣe Ifá fún. Kí ó tó ká'dún ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ènìyàn ni ó ti npé si-ín. Ó nyin Babaláwo, Babaláwo nyin Ifá, ó ní:

Mo mú igba igbín ṣ'ọ̀run, èmi kò kú mọ́
Kí ó tó di ìwòyí àjọ̀dún
Igba ẹni kàṣài bá mi jọ́sin, igba ẹni.



2. Ifá pé ẹni ti ó dá Ogbè-Fún kí ó má ṣe ojúkòkòrò nípa owó, kí ojúkòkòrò kí ó má ba ṣe àkóbá fún nípa kòtò kòtò mi. Ẹ gbọ́ bí Ifá ti wí:

Òkiti kọ̀nkọ̀
Awo ami ló d'Ifá fún ami
Nijọ́ tí ojú owó ńpọ́n ọ.

Ami ti Ifá s'ọ̀rọ̀ kàn yí, ẹdá ènìyàn ni, ojú ńpọn, iyà ńjẹ é, òṣì nta á. Nígbàtí iyà jìjẹ pọ̀ fún, ó wá mú ẹ̀ẹ́jì kún ẹ̀ẹ́ta, ó lọ sí oko aláwo. Ǹjẹ́ ojú tí ó ńpọn òun yìí lè dẹ báyìí, tí òun kò fi ní kú sínú òṣì. Àwọn Awo kí Ogbè-Fún fún-un, wọ́n ní yí óò là, tí yí óò ní ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ owó, wọ́n ní kí ó jẹ́ kí dìẹ̀ ó tó o. Wọ́n yàn-án ní ***ẹyẹlẹ́ mẹ́fà, ọgọ́fà ọ̀kẹ́ owó***. Ó rú'bọ náà. Wọ́n ṣe ewé Ifá fún. Nígbàtí ó ńwọ igbó lọ ti ó lọ ṣẹ́'gi tí yí óò tà ni ó bá já sí ẹ̀gbúrú owó. Ni ó bá gbẹ́'lẹ̀ tí ó wa owó ẹyọ, nígbàtí ó wa bí agbọ̀n mẹ́rìndínlógún, owó ya bóó l'órí mọ́'lẹ̀ nínú kòtò, ni ó bá tún mú ọkọ́, ó tún ńwa owó, ni owó bá ya lù ú mọ́'lẹ̀; ni owó bá pa á.

Ǹjẹ́ òkiti kọ̀nkọ̀
Awo ami ló d'Ifá fún ami
Ẹrò okùn, ẹrò ọ̀sà,
Ajé mà pa ami o.

Èyíun ni a ma ńsọ nígbàtí ẹnikan bá nwá owó tí owó ná à bá dé tán tí ẹ̀mí i rẹ̀ kò bá gùn mọ́.

3.

Màriwò ọpẹ̀ ba'lẹ̀ ṣe si
A d'Ífá fún Aláààyè
A bù f'Ọlọ́yẹ̀
Wọ́n ni ki wọn ó rú'bọ
Ki ibi ò má ba ṣẹlẹ̀ si wọn.

Aláààyè àti Ọlọ́yẹ̀ ti Ifá ńsọ yìí ọ̀rẹ́ timọ́-timọ́ ni àwọn méjèèji. Wọ́n ni kí àwọn méjèèjì ó rú'bọ ki ibi ó ma ba ṣe bá wọn, wọ́n yàn wọ́n l'ẹ̀bọ. Aláààyè nikan ló rú'bọ. Ọlọ́yẹ̀ kò rú'bọ. Ìgbàti yi òò di ààrọ̀, iyàwó Aláààyè bí'mọ. Ni ayé igbà náà, ńṣe ni wọ́n ńgbé ibi ọmọ sọnù. Àsikò ti Ọlọ́yẹ̀ ḿbọ̀ wá ki Aláààyè si ni wọ́n gbé ibi ọmọ júnú láti àgbàlá si ẹ̀hìn òde, déédé ọrùn Ọlọ́yẹ̀ ni ibi ọmọ ṣe. Ibi ọmọ wọ Ọlọ́yẹ̀ l'ọ̀run. Ìgbàti yí ó fi di alẹ́, ibi bá Ọlọ́yẹ̀.

**Ẹ̀kọ́** ti Ifá kọ́ wa ni ki a má ma ṣe eti kunkun si ẹbọ, ki a má jẹ̀ẹ́ adẹ́jàá.

4.

Ogbè-Fún ruru
A d'Ífá fún àgùntàn
Ti ò nsunkún wipé òun kò bí'mọ.

Àgùntàn ti Ifá ńsọ yìí ó jẹ́ ẹni ti kò ri ọmọ bí ni ayé àtijọ́, ojoojúmọ́ ẹkún òun ò bí'mọ ni í ma á sun. Ó di ọjọ́ kan ni ó bá pinu, ó mú ẹ̀ẹ́jì kún ẹ̀ẹ́ta, ó lọ oko awo. Wọ́n ni ẹbọ ni ki ó rú. Wọ́n yàn-án l'ẹ̀bọ. Àgùntàn rú ẹbọ. Wọ́n ṣe Ifá fún, àgùntàn l'ọ́yún, ó bẹ̀rẹ̀ si ni ma bí'mọ. Inú u rẹ̀ dùn, ó ńjó, ó nyọ̀, ó ni:





Ogbè-Fún ruru
A d'Ífá fún àgùntàn
Ti ó ńsunkún wipé òun kò bí'mọ
Rírú ẹbọ ni í gbe'ni
Àìrú kìí gbéniyàn
Kèè pẹ́, kèè jìnà
Ẹ wá bá mi láàárín ọmọ
Àárín ọmọ làá bá ni l'ẹsẹ̀ Ọbàrìsà.

*Àṣẹ:* Ifá pé eléyiun ojú ọmọ ni ó ńpọ́n ọ, ki ó rú'bọ, ki ó lè ba bí'mọ lọ́pọ̀lọpọ̀. Ifá pé ẹbọ ni ki ó rú.

***Translation:***

1. Ifá predicts long life for whomever Ogbè-Fún comes out for. Ifá says the person should offer plenty snails to Odù. The person should feed Ifá and provide four (4) hen, 1 (one) female goat, and igba owó (200 bags of money) as part of the ẹbọ materials

Orun kan ta tan ọjọ́ yẹ̀ látàrí
Divined for Ọlọ́fin èríwò
He that offers 200 snails to Òrìṣà (Ọbàtálá), on regular basis, for long life.

Ọlọ́fin consulted Ifá with the question, "Will I live a long life?" The Babaláwo told him that he would live long and that many people would worship him before that year ran out. They prescribed ẹbọ for Ọlọ́fin He made the ẹbọ. After the

ẹbọ, the Babaláwo gave him special Ifá medicine. By the end of that year, many people started worshipping him. Ọlọ́fin praised his Babaláwo, the Babaláwo praised Ifá [Ọ̀rúnmìlà]. Ọlọ́fin said:

"I offered 200 snails for the betterment of my life
I will live an everlasting life
By this time of my anniversary
At least 200 people will join me in praising the Òrìṣà
At least 200 people."

2. Ifá warns whomever Ogbè-Fún comes out for not to be greedy about money. If he/she is greedy, the greediness will land him/her in a live threatening trouble. Hear what Ifá says about this:

Òkiti kọ̀nkọ̀
Ami's diviner divined for ami
When ami was in abject poverty.

Ami that Ifá is talking about here was a very poor person whose poverty was grave, and whose suffering was much. When he could not bear his suffering any longer, he went to the Babaláwo for divination. His question to Ifá was, "Will I ever get out of this poverty and not die of it?" The Babaláwo recited this verse of Ogbè Òfún for him and told him that he would be rich because he was destined to be rich. The Babaláwo warned ami, however, never to be greedy. The Babaláwo told ami to bring the following for ebo: *6 pigeons, 6 bags of money*. Ami provided the things, and he made the





ẹbọ. The Babaláwo gave him special Ifá medicine. Ami went about his usual business of firewood selling. One day while collecting firewood in the wood, he suddenly discovered a treasure site. Examination of the site revealed that lots of *owó ẹyọ* (cowrie shells) were buried there. Ami dug and dug and dug the shells (which were money in those days). Ami dug until he was tired. Because of greediness, however, Ami could not stop himself from digging. He kept digging until he dropped dead. Ami died of the excitement of money.

Òkiti kọ̀nkọ̀
Ami's diviner divined for Ami
When ami was in abject poverty
People of Òpo town
People of Òfà town
Too much love of money can kill.

This mythological story is usually recited by the Yorùbá people whenever somebody dies as a result of the excitement or greediness of money.

3.
The palm frond drops heavily on the ground
Divined for Aláàáyè
Recite same for Ọlọ́yẹ̀
They were told to make ẹbọ
In order to avoid bad/negative influences in their lives.

Aláàáyè and Ọlọ́yẹ̀ were good, intimate friends. They were both told to made ẹbọ to avoid bad things happening

to them. They were given the list of the ẹbọ requirements. Aláààyè was the only one that made the ebo, Ọlọ̀yẹ̀ refused to make the ẹbọ. The following morning after Aláààyè made the ẹbọ, his wife gave birth to a baby. In the ancient time, placentas (known as *ibi ọmọ*) were usually thrown away into the woods. At the time this placenta was to be thrown away, Ọlọ̀yẹ̀ was coincidentally behind Aláààyè's house because he going there to congratulate them for their new baby. The placenta was thrown and it landed on Olòyè's head. Because placenta is called **ibi** (bad luck) in Yorùbá language and it is a bad omen for it to land on anybody's head, by the evening of the day the **ibi** (placenta) landed on Ọlọ̀yè, bad things started happening to him.

**Lesson from the Odù:** Ifá teaches us here not to disobey Ọ̀rúnmìlà's advice for ẹbọ.

4.

Archy Ogbè-Fún
Divined for Àgùntàn (sheep)
When crying because of her inability to have children.

Àgùntàn (personified) that Ifá is talking about was a barren woman in the olden days. Àgùntán's everyday cries were because of her inability to have children. One day, she decided to consult Ifá for her problems. She went to the Babaláwo. They told her to make ebo and also told her the things to provide. Àgùntán made the ebo. The Babaláwo gave àgùntán specially prepared Ifá medicine. Àgùntán became pregnant and started having children. Àgùntán was very happy, so happy that she started dancing and singing, saying:





Archy Ogbè-Fún
Divined for àgùntàn (sheep)
When crying because of her inability to have children
Making prescribed ẹbọ has its rewards
Refusal to make ẹbọ results in downfall
Soon after making an ẹbọ
Join one in the joy of having children
One is always surrounded with children in the Òrìṣà worship.

# Glossary

**Àgbálùmọ̀n** - Chrysophyllum Africanum: an orange colored or apricot-colored fruit. The fruit is yellowish
**Agogo** - Metal gong
**Àfọ̀n** - Treculia Africana (African breadfruit)
**Ajé** - Money
**Apèrè** - A covered box decorated with an antelope skin used as a foot support by the king
**Àwàdà** - jest, joke
**Ẹbọ** - Sacrifice, ritual
**Elédiro** - Hen
**Ẹní** - Mat
**Ẹni-ilẹ̀** - Alias for money
**Ètùtù** - Offering to Ifá or to any of the other Òrìṣà for peace. The regular 5-days obi àbàtà supplications is, to some extent, an ètùtù
**Ikún** - Squirrel family
**Ìrẹ̀lẹ̀** - The Òrìṣà that found Ìkirun settlement
**Ìrúlá** - Dried okra
**Ìtá** - One of Òrìṣà Orò's *ẹrú** (*domestic servant)
**Ìtí** - Parasitic plant
**Olódùmarè** - GOD
**Olúigbó** - Head-of-the-forest
**Orí** - Head, destiny
**Ọrọ̀** - one of the gods
**Òro** - Irvingia Gabonensis. It bears pulpy fruits





**Ọró Adẹ́tẹ̀** - Euphorbia Barteri: a candelabrum-like tree up to 20 feet high with fleshy, wing-like angled branches armed with spines.
**Ọrùn** - Neck
**Òpipi** - Hen with scattered feathers
**Pákòkò** - One of Orò's *ẹrú** (*domestic servant)
**Sayaarun** - Joke
**Ṣigidì** - Wooden Èṣu doll most times employed for delivery of cruel messages to marked victims

## Ilé Ọ̀rúnmìlà Communications

Books in Print

**Fundamentals of the Yorùbá Religion (Òrìṣà Worship)**, by Chief FAMA Adéwálé-Somadhi, 251 pages, paper $19.95

**Ìwé Odù Ifá: Ogbè Ọ̀yẹ̀kú - Ogbè Òfún** (Vol.1 of the Combination Series), by Chief 'Fáyẹmi Bógunmbẹ̀, 138 pages, paper $14.95

**16 Mythological Stories of Ifá**, by Chief FAMA Adéwálé-Somadhi, paper $14.95

You can order these books from us, or buy them at your local bookstore, occult supply store or botanica.

**Ilé Ọ̀rúnmìlà Communications**
**P. O. Box 2265**
**San Bernardino, CA. 92405**

## Ilé Ọ̀rúnmìlà Afrikan Imports

**Your dependable supplier of authentic Ifá and Òrìṣà paraphernalia all the way from Yorùbáland, West Africa. Call us for your order at (909) 886-6023, or write us at P. O. Box 2265, San Bernardino, CA. 92405. Businesses should enquire about our wholesale deal.**

**Àbọrú àbọyè àbọṣíṣẹ**

**Chief Bógunmbẹ̀'s trained Ifá students/god-children include:**

1. Awo Oyèélékè Ògúntáyọ̀
2. Ifáṣèyí Ògúnyinká Bógunmbẹ̀
3. Awódélé 'Fákóredé
4. 'Fákáyọ̀dé Awórindé
5. Awóyẹmí Abídoyè
6. Awóyẹmí Alágbe
7. 'Fáṣọlá Èjìkẹ́yẹ
8. 'Fágbámilá Americco Serrano, New York City, U.S.A.
9. Ìyá Awo 'Fáfúnkẹ́ Americco Serrano, New York City, U.S.A.
10. Dr. I. B. Ọdẹ́yẹmí
11. 'Fáwọlé Ọlárógbà
12. 'Fárintó Bámigbádé
13. Oyètúndé Oyèbísí
14. Ifáfọre Kimya Bonner, Las Vega, U.S.A.
15. Ifámáyọ̀wá Bọ́lárinwá
16. Ìdòwú Oyèélákin
17. Ìyá Awo Ọládùnúnní 'Fádoórà
18. Chief 'Fátádé 'Ládiipọ̀
19. Ìyá Awo 'Fárinọ̀lá Ẹfúnyalé, Washington D.C., U.S.A.
20. Awolọlá Thomas Anderson, Maryland, U.S.A.
21. Ìyá Awo 'Fákẹ́mi Shirley Dickey, Washington D.C., U.S.A.

**Other books by Chief Bógunmbẹ̀ are:**

Ifá Guidelines for the Child Naming Ceremony
The Wisdom of the Elders
Ìdí Abájọ (The Reason Why)

## About the Author

Chief 'Fayemi Bógunmbé was born on February 11, 1938 in Ìbàdàn, the capital city of old Òyó Empire now Òyó State, Africa's largest city South of Sahara.

He started his preliminary training in Ifá divination in 1949 and completed it in 1959. He was trained by Chief Oniwide Àlàbí, the Okunieri Awo of Ìbàdànland.

He undertook his advanced studies in Ifá under Chief Gbàdébo Dòsunmú and Chief 'Fawole Àlàbí, between 1959 to 1962 and 1962 to 1965. After 18 years of rigorous training, he set up his own practice in Ìbàdàn where he is an acknowledged leader in Ifá.

Chief Bógunmbé, who had served as the Secretary of the Association of Ifá Adimúlà, Òyó State Chapter, is the Asiwaju Ìjo Òsé-Méjì (Òsé-Méjì Temple), Ìbàdàn and the Òdòfin Àlàbolà of Òlà town in Ejigbò Local Government of Òsun State, Nigeria.

Chief Bógunmbé has published some books on Ifá, and he has trained many Ifá priests both within and outside Nigeria, his homeland.

**Ilé Òrúnmìlà Communications**
**P. O. Box 2265**
**San Bernardino, CA. 92405**

ISBN 0-9644247-1-1

ISBN 0-9644247-1-1
51495>
9 780964 424715

**U.S.A. $14.95**